18

# JOBU

**(B.C. 1520)**

ORI 1.

**Ìbẹ̀rẹ̀ igbeaye Jobu.**

OKUNRIN kan wa ni ilẹ Usi, orukọ ẹni ti nję Jobu; ọkunrin naa si jẹ́ olootọ, o duro ṣinṣin; ẹni ti o bẹ̀ru Ọlọrun, ti o si korira ìwà buburu. (Jer 25:20; Esk 14:14; Jak 5:11; Gen 6:9; 17:1; Eks 18:21.)

2. A sì bi ọmọkunrin meje ati ọmọbinrin mẹta fun un. (Job 42:13.)

3. Ohun-ọ̀sìn rẹ̀ si jẹ ẹẹdẹgbaarin agutan, ati ẹgbẹẹdogun rakunmi, ati ẹẹdẹgbẹta ajaga ọ̀dá-malu, ati ẹẹdẹgbẹta agbo kẹtẹkẹtẹ, o si pọ; bẹẹ ni ọkunrin yìí si pọ ju gbogbo awọn ọmọ ara ila-oòrùn lọ. (Job 42:12.)

4. Awọn ọmọ rẹ̀ si maa lọ njẹun àsè ninu ile ara wọn, olukuluku ni ọjọ rẹ̀; wọn a si maa ranṣẹ pe arabinrin wọn mẹtẹẹta lati jẹun ati lati mu pẹlu wọn.

5. O si ṣe, nigba ti ọjọ àsè wọn pé yika, ni Jobu ranṣẹ lọ yà wọn sí mímọ́, o si dide ni kutukutu owurọ, o si rú ẹbọ sísun niwọn iye gbogbo wọn; nitori ti Jobu wi pe: boya awọn ọmọ mi ti ṣẹ̀, wọn kò sì ṣọpẹ fun Ọlọrun lọ́kàn wọn. Bẹẹ ni Jobu maa nṣe nigba gbogbo. (Eks 19:10; Gen 8:20; 1 A.Ọba 21:10,13.)

**Ọlọrun fun èṣù láyè lati dán Jobu wò.**

6. Nję, o di ọjọ kan, nigba ti awọn ọmọ Ọlọrun pejọ niwaju Oluwa, Satani si wà pẹlu wọn. (Job 38:7; 1 Kro 21:1.)

7. Oluwa si bi Satani wi pe: "Nibo ni iwọ ti wá?" Nigba naa ni Satani dá Oluwa lohun wi pe: "Nilílọ síwa sẹhin lori ilẹ ayé, ati ni irinkerindo ninu rẹ̀." (1 Pet 5:8.)

8. Oluwa si sọ fun Satani pe, "Iwọ ha kiyesi Jobu iranṣẹ mi, pe, kò si ekeji rẹ̀ ni ayé, ọkunrin ti o jẹ́ olootọ́, ti o si duro ṣinṣin, ẹni ti o bẹru Ọlọrun, ti o si korira ìwà buburu." (Job 52:7,8; ẹsẹ 1.)

9. Nigba naa ni Satani dá Oluwa lohun wi pe: "Jobu ha bẹ̀rù Oluwa ninu asán bí? (1 Tim 6:5.)

10. Iwọ kò ha ti ṣọgba yi i ká, ati yi ilé rẹ̀ ati yi ohun ti o ni ka ni iha gbogbo? Iwọ bụsi iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀, ohun-ini rẹ̀ si npọ si i ni ilẹ̀. (Job 29:2–6; Psm 128:1,2; Job 31:25.)

11. Nję nawọ́ rẹ nisinsinyìí, ki o si fi tọ́ ohun gbogbo ti o ní; bi ki yoo si bọ́hùn loju rẹ." (Job 2:5; 19:21.)

12. Oluwa si dá Satani lohun wi pe: Kiyesi i, ohun gbogbo ti o ni nbẹ ni ikáwọ rẹ, kìkì oun tikararẹ̀ ni iwọ kò gbọdọ fi ọwọ́ rẹ kàn." Bẹẹ ni Satani jade lọ kuro niwaju Oluwa.

**Satani gba gbogbo ọrọ̀ Jobu, o si pa awọn ọmọ rẹ̀.**

13. O si di ọjọ́ kan, nigba ti awọn ọmọ rẹ̀ ọkunrin ati obinrin nję, ti wọn nmu ọti-waini ninu ile ẹ̀gbọ́n wọn ọkunrin:

14. Onişẹ kan si tọ Jobu wa wí pé: "Awọn ọ̀dá-malu ntulẹ, awọn kẹtẹkẹtẹ si nję ni ẹ̀bá wọn;

15. Awọn ara Saba si kọlù wọn, wọn si kó wọn lọ, pẹlupẹlù wọn ti fi idà ṣá awọn iranṣẹ pa, emi nikanṣoṣo ni o sá àsálà lati ròhìn fun ọ." (Job 6:19.)

16. Bi o si ti nsọrọ yìí lọ́wọ́, ẹnikan dé pẹlu ti o si wí pé: "Ina nla Ọlọrun ti ọ̀run bọ́ si ilẹ̀, o si jó awọn agutan ati awọn iranṣẹ ní àjórun; emi nikanṣoṣo ni o sálà lati ròhìn fun ọ." (Gen 19:24; Lef 10:2; Num 11:1–3; 2 A.Ọba 1:10.)

17. Bi o si ti nsọrọ yìí lọwọ, ẹnikan si de pẹlu ti o wi pé: "Awọn ara Kaldea pin ara wọn si ọ̀nà mẹta, wọn si kọlu awọn rakunmi, wọn si kó wọn lọ,

pẹlupẹlu wọn si fi idà ṣá awọn iranṣẹ pa; emi nikanṣoṣo ni o sa àsálà lati ròhìn fun ọ." (Gen 11:28,31.).

18. Bi o si ti nsọ̀rọ̀ yìí lọwọ ẹnikan dé pẹlu ti o si wi pe: "Awọn ọmọ rẹ ọkunrin ati ọmọ rẹ obinrin njẹ, wọn nmu ọti-waini ninu ile ẹgbọn wọn ọkunrin. (ẹsẹ 4,13.)

19. Si kiyesi i, ẹ̀fúùfù nlanlà ti ìhà ijù fẹ́ wá kọlu igun mẹrẹrin ile, o si wolu awọn ọdọmọkunrin naa, wọn si ku, emi nikanṣoṣo ni o yọ lati ròhìn fun ọ. (Jer 4:11; 13:24.)

**Jobu fi èmí ipamọra hàn.**

20. Nigba naa ni Jobu dide, o si fa aṣọ igunwa rẹ̀ ya, o si fari rẹ̀, o wólẹ̀, o si gbadura. (Gen 37:29; 1 Pet 5:6.)

21. Wi pe, "Níhòhò ni mo ti inu ìyá mi jade wá, nihòòhò ni emi o si tun pada lọ sibẹ: Oluwa fifunni Oluwa si gbaa lọ, ibukun ni orukọ Oluwa. (Onws 5:15; 1 Tim 6:7; Job 2:10; Ef 5:20; 1 Tess 5:18.)

22. Ninu gbogbo èyí Jobu kò ṣẹ̀, bẹẹ ni kò sì fi wèrè pe Ọlọrun lẹ́jọ́. (Job 2:10.)

## ORI 2.

**Ọlọrun gbà fun Satani ki o dan Jobu wò lẹẹkeji.**

O si tun di ọjọ kan nigba ti awọn ọmọ Ọlọrun tun pejọ niwaju Oluwa, Satani si wà pẹlu wọn, lati farahàn niwaju Oluwa. (Job 1:6.)

2. Oluwa si bi Satani pe, "Nibo ni iwọ ti wá?" Satani si dá Oluwa lohun pe, "Nipa lilọ síwá sẹ́hìn lori ilẹ ayé ati ni irinkerindo ninu rẹ̀." (Job 1:7.)

3. Oluwa si wi fun Satani pe, "Iwọ ha kiyesi Jobu iranṣẹ mi, pe, ko si ekeji rẹ̀ ni ayé, ọkunrin ti o jẹ́ olootọ́ ti o si duro ṣinṣin, ẹni ti o bẹ̀rù Ọlọrun ti o si korira ìwà buburu, bẹẹ ni o si di ìwà otitọ rẹ̀ mu ṣinṣin, bi iwọ tilẹ ti dẹ mi si i lati run un láìnídìí." (Job 1:1,8; 27:5,6; 9:17.)

4. Satani si da Oluwa lohun wi pe, "Àwọ̀ fun àwọ̀; ani ohun gbogbo ti eniyan ni, oun ni yoo fi ra ẹ̀mí rẹ̀.

5. Ṣugbọn nawọ rẹ nisinsinyìí, ki o si fi tọ́ egungun rẹ̀ ati ara rẹ̀, bi ki yoo si bọ́hùn loju rẹ." (Job 1:11.)

6. Oluwa si wi fun Satani pe, "wo o, o nbẹ ni ikawọ rẹ, ṣugbọn da ẹmi rẹ̀ si." (Job 1:12.)

**Satani pọn Jobu fúnrararẹ̀ loju.**

7. Bẹẹ ni Satani jade lọ kuro niwaju Oluwa, o si sọ Jobu ni oowo kikankikan lati atẹlẹsẹ̀ rẹ̀ lọ dé atari rẹ̀. (Job 7:5.)

8. Oun si mu apadi o fi nhà ara rẹ̀, o si jókòó ninu eerú. (Job 42:6; Esk 27:30; Matt 11:21.)

**Jobu tun fi ẹmí ipamọra hàn si i.**

9. Nigba naa ni aya rẹ wi fun un pe, "Iwọ di ìwà otítọ́ rẹ mu sibẹ! fi Ọlọrun bú ki o sì kú."

10. Ṣugbọn oun da a lohun pe, "iwọ sọ̀rọ̀ bi ọkan ninu awọn obinrin alaimoye ti nsọ̀rọ̀; awa o ha gba ire lọwọ Ọlọrun, ki a má sì gba ibi!" Ninu gbogbo eyi Jobu ko fi ètè rẹ̀ ṣẹ̀. (Job 1:21,22; Psm 39:1.)

**Awọn ọ̀rẹ́ Jobu.**

11. Nigba ti awọn ọ̀rẹ́ Jobu mẹta gburo gbogbo ibi ti o ba a, wọ́n wá, olukuluku lati ibùjókòó rẹ̀ wá; Elifasi, ara Tema, ati Bildadi, ara Sua, ati Sofari, ara Naama: nitori pe wọn ti pinnu lati pade pọ̀ lati ba a ṣọ̀fọ̀ ati lati ṣìpẹ̀ fun un. (1 Kro 1:45; Gen 25:2; Job 42:11.)

12. Nigba ti wọn si ri i ni okere réré, ti wọn kò sì mọ ọn, wọn gbe ohun wọn soke, wọn sọkún: olukuluku si fa aṣọ igunwa rẹ̀ ya, wọn si ku erupẹ̀ si ojú ọ̀run si ara wọn lori. (Jos 7:6; E.Jer. 2:10; Esk 27:30.)

13. Bẹẹ ni wọn jokòó ti i ni ilẹ̀ ni ijọ meje tọsan toru, ẹnikẹni kò si ba a dá ọ̀rọ̀ kan sọ nitori ti wọn ri pe,ibanujẹ rẹ̀ pọ̀ gidigidi. (Gen 50:10; Esk 3:15.)

## ORI 3.

**Jobu fi ọjọ ìbí rẹ̀ ré.**

LEHIN eyi ni Jobu yanu o si fi ọjọ ibi rẹ̀ ré.

2. Jobu sọ, o si wi pe,

3. "Ki ọjọ ti a bi mi di ìgbàgbé, ati oru naa, ninu eyi ti a wi pe; a loyun ọmọkunrin kan." (Job 10:18; Jer 20:14.)

4. Ki ọjọ naa jasi òkùnkùn; ki Ọlọrun má ṣe kà á si lati ọrun wá, bẹẹ ni ki imọlẹ maṣe mọ si i.

5. Ki òkùnkùn ati ojiji iku fi ṣe ti ara wọn: ki ikuukuu awọsanma bà le e, ki ìṣúdùdù ọ̀jọ̀ naa dẹ́yà fò ó. (Job 10:21; Psm. 23:4; Jer 2:6.)

6. Ki òkùnkùn ṣubo oru naa biribiri; ki o má ṣe yọ pẹlu ọjọ́ ọdun naa: ki a má ṣe kà a mọ iye ọjọ oṣù. (Job 23:17.)

7. Ki oru naa yàgàn; ki ohun ayọ kan má ṣe wọnu rẹ̀ lọ.

8. Ki awọn ti nfi ọjọ́ gegun fi i gegun, awọn ti wọn mọ bi a ti nru Lefiatani soke. (Job 41:10.)

9. 'Jẹ ki ìràwọ̀ afẹmọjumọ ọjọ rẹ̀ ṣókùnkùn; ki o maa wá imọlẹ, ṣugbọn ki o má si, bẹẹ ni ki o ma ṣe ri owuro. (Job 41:18.)

10. Nitori ti kò sé ilẹkun inu ìyá mi, bẹẹ ni kò si pa ìbanujẹ mọ́ kuro loju mi.

**Jobu beere ìdí ti ko fi kú lati inú wá.**

11. "Eeṣe ti emi kò fi kú lati inú wá, tabi ti emi kò fi kú nigba ti mo ti inu jade wá? (Job 10:18.)

12. Eeṣe ti eékún gbà mi, tabi ọmú ti emi o mu? (Gen 30:3; Isa 66:12.)

13. Njẹ! nisinsinyìí, emi ì bá ti dubulẹ jẹ, emi a si dakẹ, emi ì bá ti sùn: njẹ emi ì bá ti sinmi!

14. Pẹlu awọn ọba ati awọn olugbìmọ̀ ayé, ti wọn tún ibi-iparun kọ́ fún ara wọn. (Job 12:17,18; 15:28.)

15. Tabi pẹlu awọn ọmọ-alade ti o ni wura, ti wọn si fi fadaka kun inu ile wọn.

16. Eeṣe ti emi kò fi dabi ìgbésìn ọmọ ti ọjọ rẹ̀ kò pé, ani bi awọn ìkókó-ọmọ ti ko tilẹ ri ìmọ́lẹ̀? (Onws 6:3.)

17. Nibẹ ni ẹni-buburu ṣíwọ́ iyọnilẹnu, nibẹ ni ẹni-aarẹ̀ wà ninu isinmi. (Job 17:16.)

18. Nibẹ ni awọn ìgbèkùn sinmi pọ̀, wọn kò si gbohun amúnisìn mọ́.

19. Ati ewe ati àgbà wa nibẹ, ẹrú si di ominira kuro lọwọ olówó rẹ̀."

**Jobu kigbe ninu irora rẹ̀.**

20. "Nitori kinni a ṣe fi imọlẹ fun otoṣi, ati iyè fun ọlọkan kikorò. (1 Sam 1:10; Owe 31:6; Isa 38:15; Esk 27:31.)

21. Ti wọn duro de ikú, ṣugbọn oun kò wá, ti wọn walẹ̀ wá a ju iṣura ti a bò mọlẹ pamọ lọ. (Ifh 9:6.)

22. Ẹni ti o yọ̀ gidigidi, ti inu wọn si dùn nigba ti wọn wá iboji òkú ri.

23. Kinni idi ti a fi fi imọlẹ fun ẹni ti ọ̀nà rẹ̀ fi ara pamọ, ti Ọlọrun ṣọgbà yí ká? (Job 19:6,8,12; E.Jer. 3:7.)

24. Nitori pe imi-ẹdun mi wá ṣaaju ounjẹ mi, ikẹrora mi si tu jade bi omi. (Psm 42:3,4.)

25. Nitori pe ohun naa ti mo bẹ̀rù gidigidi ni o dé bá mi yii, ati ohun ti mo fòyà rẹ̀ ba mi o si ṣubu lù mi.

26. Emi kò wà lailewu ri, bẹẹ ni emi kò ni isinmi, bẹẹ ni emi kò ni ìfàyàbalẹ̀, sibẹ-sibẹ iyọnu dé."

## ORI 4.

**Ọrọ Elifasi: Ọlọrun ki i fi ìyà jẹ olododo.**

NIGBA naa ni Elifasi, ara Tema, dahun wi pe,

2. "Bi awa ba fi ẹnu le e, lati ba ọ sọ̀rọ̀, iwọ o ha banujẹ? Ṣugbọn tani o le pa ọ̀rọ̀ mọ ẹnu laisọ? (Job 32:18–20.)

3. Kiye si i, iwọ sa ti kọ́ ọ̀pọ̀ eniyan, iwọ ṣa ti mu ọwọ́ alailera le. (Isa 35:3; Heb 12:12.)

4. Ọ̀rọ̀ rẹ ti gbé awọn ti nṣubu lọ duro, iwọ si ti mu eékún awọn ti nwárìrì lera (Isa 35:3; Heb 12:12.)

5. Ṣugbọn nisinsinyìí o dé ba ọ, o si rẹ̀ ọ, o kọlù ọ, ara rẹ kò lélẹ̀. (Job 6:14; 19:21.)

6. Ìbẹru Ọlọrun rẹ ko ha jẹ́ igbẹkẹle

rẹ? Ati iduro-ṣinṣin ọ̀nà rẹ kò ha si jẹ ireti rẹ? (Job 1:1.)

7. "Emi bẹ ọ ranti, tani o ṣègbé rí laiṣẹ̀, tabi nibo ni a gbe gé olododo kuro ri? (Psm 37:25.)

8. Ani bi emi ti ri i pe: awọn ti nṣe itulẹ ẹ̀ṣẹ̀, ti wọn si fun irugbin iwa buburu, wọn a si ká èso rẹ̀ naa. (Owe 22:8; Hos 10:13; Gal 6:7,8.)

9. Nipa eemí Ọlọrun wọn a ṣègbé, ati nipa fifẹ ibinu rẹ̀ wọn a parun (Job 15:30; Isa 30:33; Psm 59:13.)

10. Bibu ramúramù kinniun ati ohùn ònrorò kinniun ati ehin awọn ẹgbọrọ kinniun ni a ká (Psm. 58:6.)

11. Alagbara kinniun ṣegbe, nitori airi ohun-ọdẹ, awọn ẹgbọrọ abo-kinniun ni a túkákiri (Psm 34:10.)

**Ẹlẹṣẹ ni lati ṣègbé.**

12. "Njẹ nisinsinyií a fi ọ̀rọ̀ kan han fun mi, ni ikọ̀kọ̀ eti mi si gbọ́ isọ-kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ rẹ̀. (Job 26:14.)

13. Ninu ero loju iran òru, nigba ti oorun ìjìká bá kun eniyan

14. Ẹrù bà mi, ati ìwárìrì, ti o mu gbogbo egungun mi gbọ̀n. (Jer 23:9.)

15. Nigba naa ni iwin kan kọjà lọ niwaju mi, irun ara mi dide ró ṣánṣán. (Matt 14:26.)

16. Oun duro jẹ, ṣugbọn emi kò lè wo ìrísí rẹ̀, aworan kan hàn niwaju mi, idakẹ rọ́rọ́ wà, mo si gbohun kan wi pe:

17. "Njẹ ẹni kiku le jẹ́ olododo niwaju Ọlọrun? Eniyan ha lè mọ́ ju Ẹlẹda rẹ̀ lọ bi?" (Job 9:2; 35:10.)

18. Paapaa, oun ko gbẹ́kẹ̀lé awọn iranṣẹ rẹ̀, ninu awọn angẹli rẹ̀ ni o si ri ẹ̀ṣẹ̀. (Job 15:15.)

19. Ambọtori awọn ti ngbe inu ile amọ̀, ẹni ti ìpìlẹ̀ wọn jasi erupẹ eyi ti yoo di rírun niwaju kòkòrò. (Job 10:9; 22:16.)

20. A npa wọn run laarin owurọ ati alẹ́, wọn ṣegbe laelae láìsí ẹni ti nfiyesí i. (Psm 90:5,6; Job 20:7.)

21. A kò ha ge okùn ìyè won kuro bi? Wọn ku, ani lailọgbọn." (Job 36:12.)

ORI 5.

**Ijiya jẹ́ eso aiṣododo.**

PE nisinsinyìí! bi ẹnikan bá wà ti yoo da ọ lohun, tabi tani ninu awọn ẹni-mimọ ti iwọ yoo yiju si? (Job 15:15.)

2. Nitori pe ibinu pa alaimòye, owú si pa òpè eniyan. (Owe 12:16.)

3. Emi ti ri alaimoye ti o fi gbongbo mulẹ̀, ṣugbọn lojukan naa mo fi ibujoko rẹ̀ bú (Psm 37:35.).

4. Awọn ọmọ rẹ̀ kò jinna sinu ewu, a si tẹ̀ wọn mọlẹ loju ibode, bẹẹ ni kò sí alaabò kan. (Amos 5:12.)

5. Ikore oko rẹ̀ ni ẹni ti ebi npa jẹ, ti o si wọ inu ẹgun lọ kó, awọn igárá si poungbẹ ohun-ìní rẹ̀. (Job 18:8–10.)

6. Nitori ipọnju kò tinu erúpẹ̀ jade wá, iyọnu ko si tinu ilẹ̀ hu jade wá.

7. Ṣugbọn a bi eniyan sinu wahala, gẹgẹ bi pẹ́pẹ́ iná ti maa nta soke (Job 14:1.)

**Elifasi bẹ Jobu lati wá Ọlọrun.**

8. "Bi o ṣe temi ni, emi yoo wá Ọlọrun ati lọwọ Ọlọrun ni emi yoo maa fi ọ̀ràn mi lé. (Psm 35:23.)

9. Ẹni ti o ṣe ohun ti o tobi, ti a kò lè ṣe awari, ohun iyanu laini iye. (Psm 40:5; 72:18.)

10. Ti nrọ̀jọ̀ si ilẹ ayé, ti o si nrán omi sinu ilẹkilẹ. (Psm 65:9.)

11. Lati gbe awọn onirẹlẹ lékè, ki a lè gbe awọn ẹni ibanujẹ ga si ibi ailewu. (1 Sam 2:7; Psm 113:7.)

12. O yi ìmọ̀ awọn alarekérekè po, ki ọwọ́ wọn má baa ṣe aṣeyọri. (Neh 4:15; Psm 33:10; Isa 8:10.)

13. O mu awọn ọlọgbọn ninu arekereke ara wọn, ati imọ awọn aṣetinuẹni ni o mú wá sí òpin kiakia.

14. Wọn súré wọ inu òkùnkùn ni ọ̀sán, wọn si nfọwọ́-wá ọna ni ọsangangan bi ẹni pe ni òru. (Job 12:25; Deut 28:29.)

15. Ṣugbọn o gba alainibaba là kuro lọwọ idà ẹnu wọn, ati talaka lọwọ awọn alágbára (Psm 35:10.)

16. Bẹẹ ni ireti wà fun talaka,

ṣugbọn aiṣotitọ pa ẹnu rẹ̀ mọ́. (Psm 107:42.)

17. "Kiyesi i, alabukun fun ni ẹni ti Ọlọrun bawí, nitori naa ma ṣe gan ibawi Olodumare (Psm 94:12; Jak 1:12; Heb 12:5–11.)

18. Nitori ti oun nmu ni lara kan, ṣugbọn a si di ìdì itura, o ṣa lọ́gbẹ́, ṣugbọn ọwọ rẹ̀ a si mu jinna. (Isa 30:26.)

19. Yoo gbà ọ ninu ipọnju mẹfa, ani ninu meje ibi kan ki yoo ba ọ. (Psm 34:19; 91:10.)

20. Ninu iyan yoo gbà ọ lọwọ iku, ati ninu ogun yoo gbà ọ lọwọ idà. (Psm 33:19; 144:10.)

21. A o pa ọ mọ́ kuro lọwọ iná ahọn, bẹẹ ni iwọ ki yoo bẹru iparun nigba ti o ba de. (Psm 31:20; 91:5,6.)

22. Iparun ati ìyàn ni iwọ yoo rẹ́rìn sí, bẹẹ ni iwọ ki yoo bẹru ẹranko ilẹ ayé. (Psm 91:13; Eks 34:29.)

23. Nitori pe iwọ o bá okuta igbẹ mulẹ̀, awọn ẹranko igbẹ yoo wà pẹlu rẹ ni alaafia. (Psm. 91:12; Isa 11:6–9.)

24. Iwọ o si mọ̀ pe alaafia ni ibujokòó rẹ wà, iwọ o si maa ṣe ibẹwo ibujokòó rẹ, iwọ ki yoo ṣìnà. (Job 8:6; 21:9.)

25. Iwọ o si mọ̀ pẹlu pe iru-ọmọ rẹ yoo si pọ, ati awọn ọmọ-ọmọ rẹ yoo ri bi koriko ìgbẹ́ (Psm 72;16; 112:2.)

26. Iwọ o wọ iboji rẹ lọ ni ogbologbo ọjọ́ gẹgẹ bi àpò-ọkà ti o gbó, ti a si nkó ni igba ikore rẹ̀. (Gen 15:15; Owe 9:11.)

27. Kiyesi i, eyí ni a ti wadi rẹ̀, bẹẹ ni o ri! gba a gbọ́, ki o si mọ̀ pe fun ire ara rẹ ni!"

## ORI 6.

**Idahun Jobu si ọrọ Elifasi.**

JOBU si dahun o si wi pe,

2. "A! a ba lè wọn ibanujẹ mi, ki a si gbe wahala mi lé ori òṣùwọ̀n! (Job 31:6.)

3. Njẹ nisinsinyìí, iba wuwo ju iyanrin òkun lọ: nitori naa ni ọ̀rọ̀ mi ṣe ntàsé. (Owe 27:3.)

4. Nitori pe ọfa Olodumare wọ̀ mi ninu, oró eyí ti ẹ̀mí mi mu; ipáyà-ẹ̀rù Ọlọrun dótì mí. (Psm 38:2; Job 21:20; Psm 88:15.)

5. Njẹ kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ìgbẹ́ a maa dún, nigba ti o ba ni koriko, tabi ọda-malu a maa dun sori ijẹ rẹ̀?

6. A ha lè jẹ ohun ti kò ni adun laini iyọ̀, tabi adùn ha wà ninu funfun ẹyin?

7. Ohun ti ọkan mi kọ̀ lati fọwọ́bà, oun ni o dabi ounjẹ mi ti kò ni adùn.

8. "A! emi ì bá lè ri ibéèrè mi gbà; ati pe, Ọlọrun ì bá lè fi ohun ti emi ṣafẹri fun mi. (Job 14:13.)

9. Ani Ọlọrun ì bá jẹ pa mi run, ti oun ì bá jẹ na ọwọ rẹ̀ ki o si ge mi kurọ. (1 A.Ọba 19:4.)

10. Nigba naa ni emi ì bá ni ìtùnú sibẹ, ani emi ì bá mu ọkan mi le ninu ibinujẹ mi ti kò da ni sí: nitori emi kò sẹ́ ọrọ Ẹni Mimọ ri. (Job 23:11,12; Lef 19:2; Isa 57:15; Hos 11:9.)

11. Kinni agbara mi ti emi ọ fi reti? Ki ṣi ni òpin mi ti emi o fi kọ́ suuru? (Job 21:4.)

12. Agbara mi ha nṣe agbara okuta bi, tabi ẹran ara mi nṣe idẹ?

13. Lotitọ́, iranlọwọ kò si ninu mi, ọgbọ́n ti salọ kuro lọdọ mi. (Job 26:2,3.)

**Jobu pe awọn ọrẹ rẹ̀ ni alaiṣootọ́.**

14. "Ẹni ti o ndaku lọ ni a ba maa ṣaanu fún lati ọdọ ọrẹ rẹ̀ wá, ki o má baa kọ ibẹru Olodumare silẹ.

15. Awọn ara mi ṣẹ̀tàn bi odò ti nṣan, ani bi iṣàn omi odò ti wọn nṣan kọja lọ. (Psm 38:11; Jer 15:18.)

16. Ti o dudu nitori omi-dídì, ati nibi ti òjò-dídì gbe lùmọ̀ si.

17. Nigbakugba ti wọn ba gbóná, wọn a si yọ́ sànlọ, nigba ti oòrùn ba mú, wọn a si gbẹ kuro ni ipo wọn. (Job 24:19.)

18. Awọn ẹgbẹ èrò a si yipada kuro ni ọ̀nà wọn, wọn a si goke si ibi asan, wọn a si parun.

19. Ẹgbẹ́-èrò Tema nwoye, awọn arinrin-àjò Ṣeba duro dè wọ́n. (Gen 25:15; Isa 21:14; 1 A.Ọba 10:1.)
20. Wọn já tilẹ̀, nitori ti wọn gbẹ́kẹ̀ wọn lée; wọn débẹ̀, wọn si daamu. (Jer 14:3.)

**Jobu beere ẹ̀rí fun awọn ẹṣẹ rẹ̀.**

21. Njẹ nisinsinyìí, ẹyin dabi wọn; ẹyin ri iṛẹsilẹ mi, aya si fò yín.
22. Emi ha wi pe, "ẹ mu ohun wa fun mi" tabi pe, 'Ẹ bùn mí ní ẹ̀bùn ninu ohun ìní yin?'"
23. Tabi, 'Ẹ gbà mi ni ọwọ́ ọ̀tá?' Tabi, 'Ẹ rà mi padà kuro lọwọ àninilára?'
24. Ẹ kọ mi, emi o si pa ẹnu mi mọ́; ki ẹ si mu mi mòye ibi ti mo gbe ti ṣìnà.
25. Wo o! bi ọ̀rọ̀ otitọ ti lagbara tó! ṣugbọn kinni aroye ibawi yin jásí? (Onws 12:10,11.)
26. Ṣe ẹyin ṣebi ẹ lè bá ọ̀rọ̀ wí, ani isọ̀rọ̀ ẹni ti o nṣàárẹ̀, ti o si dabi afẹ́fẹ́. (Job 8:2.)
27. Ẹyin yoo tilẹ̀ ṣẹ́ gègé lori alainibaba; ẹyin si dá iye le ọ̀rẹ́ yin! (Joel 3:3; 2 Pet 3:3.)
28. "Nitori naa ki eyi tó fun yin: ẹ maa wò mi! nitori pe ó hàn gbangba pe: loju yin emi ki yoo ṣèké. (Job 27:4.)
29. Emi bẹ̀ yin, ẹ pada, ki o ma ṣe jasi ẹ̀ṣẹ̀; ani ẹ si tun pada, àre mi nbẹ ninu ọ̀ràn yìí.
30. Aiṣedeede ha wà ni ahọn mi bi? Njẹ ìtọ́wò ẹnu mi ha lè mọ ohun ti o buruju? (Job 27:4; 12:11.)

## ORI 7.

**Jobu ha ni ìrètí bi?**

NJẸ iṣẹ lile kò ha si fun eniyan lori ilẹ̀, ọjọ rẹ̀ pẹlu kò dabi ọjọ alagbaṣe? (Job 10:17; 14:14; Isa 40:2; Job 14:6.)
2. Bi ọmọ-ọ̀dọ̀ ti maa nṣafẹri ọ̀jìji, ati bi alagbaṣe ti maa nṣafẹri owo iṣẹ rẹ̀. (Lef 19:13.)
3. Bẹẹ ni a mu mi ni ibanujẹ ni ọpọlọpọ oṣù, òru idani-lagara ni a si là silẹ fun mi. (E.Jer. 1:17; Psm 6:6.)
4. Nigba ti mo dubulẹ, emi wi pe, 'nigbawo ni emi o dide,' òru yoo si kọja lọ? Sugbọn mo nyi sihin yi sọhun títí yoo fi di afẹmọjumọ. (Deut 28:67.)
5. Kòkòrò ati ogulutu erùpẹ̀ ni a fi wọ̀ mi laṣọ, awọ ara mi le, o si bú jade.
6. Ọjọ́ mi yara ju ọkọ̀-iwunṣọ lọ, o si wá sí òpin rẹ láìní ìrètí. (Job 9:25; 13:15; 17:15,16.)

**Jobu gbadura si Ọlọrun rẹ̀.**

7. "A! ranti pe afẹfẹ ni ẹ̀mí mi; oju mi ki yoo pada ri rere mọ́. (Psm 78:39; Job 9:25.)
8. Oju ẹni ti o ri mi, ki yoo ri mi mọ́, nigba ti oju rẹ bá tẹ̀ mọ́ mi, emi yoo ti lọ. (Job 20:9; ẹsẹ 21.)
9. Bi ikuukuu awọsanma ti nparun, ti si nfo lọ, bẹẹ ni ẹni ti nlọ si isà-òkú, ti ki yoo padà wa mọ́. (Job 30:15; 11:8; 2 Sam 12:23.)
10. Ki yoo pada sinu ile rẹ̀ mọ, bẹẹ ni ipo rẹ̀ ki yoo mọ ọn mọ́. (Job 10:21; Psm 103:16.)
11. "Nitori naa emi ki yoo pa ẹnu mi mọ́, emi o maa sọ ninu irora ọkàn mi, emi o maa ṣe ìràhùn ninu kikoro ọkan mi. (Psm 40:9; 1 Sam 1:10.)
12. Emi a maa ṣe ejò òkun bi, tabi erinmi odò, ti iwọ fi yan oluṣọ tì mí? (Esk 32:2,3.)
13. Nigba ti mo wi pe, ibusun mi yoo tù mi lara, itẹ́ mi yoo mu ara mi fuyẹ pẹlu. (Job 9:27.)
14. Nigba naa ni iwọ fi àlá dáyà fò mi, o si fi iran òru dẹruba mi. (Job 9:34.)
15. Bẹẹ ni ọkàn mi yàn lati pokùnso, ki nsi ku ju egungun mi lọ. (1 A.Ọba 19:4.)
16. Ò sú mi, emi ko lè wà títí: fi mi silẹ̀, nitori pe asán ni ọjọ́ mi. (Job 10:1; Onws 7:15.)
17. Kinni eniyan ti iwọ o maa kokiki rẹ̀? Ati ti iwọ iba fi gbe ọkàn rẹ le e? (Psm 8: 4; 144:3; Heb 2:6.)
18. Ati ti iwọ o fi maa wá bẹ̀ ẹ́ wò ni

orowurọ, ti iwọ o si maa dán an wò nigbakugba!

19. Yoo ti pẹ́ to ki iwọ to fi mi silẹ lọ, ti iwọ o fi fi mí silẹ jẹ́ titi emi o fi le dá itọ́ mi mì.

20. Emi ti ṣè, kinni emi ṣe si ọ, iwọ Oluṣọ eniyan? "Eeṣe ti iwọ fi fi mi ṣe ohun ìsàmì sí rẹ, bẹẹ ni emi si di ẹrù-wúwo fun ọ? (Job 35:3,6; ẹsẹ 12; Job 16:12.)

21. Eeṣe ti iwọ kò si dari ìrékọja mi jì mi, ki o si mu aiṣedéédé mi kuro? Njẹ nisinsinyìí ni emi iba sùn ninu erùpẹ̀, iwọ iba si wá mi kiri ni owurọ, emi ki ba ti sí." (Job 10:14; Psm 104:29; ẹsẹ 8.)

## ORI 8.

**Bildadi pe Jobu lati ronupiwada iwà àgàbàgebè rẹ̀.**

NIGBA naa ni Bildadi, ara Ṣua, dahun wi pe,

2. "Iwọ o ti maa sọ nkan wọnyìí pẹ to? Ti ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ yoo si maa dabi ẹfufu nla?

3. Ọlọrun a há maa yi idajọ po bí? Tabi Olodumare maa nfi otitọ ṣẹ̀tàn bi? (Gen 18:25; Deut 32:4; 2 Kro 19:7; Dan 9:14; Rom 3:5.)

4. Nigba ti awọn ọmọ rẹ̀ ṣẹ̀ si i, o sì gbà wọ̀n kuro nitori irekọja wọn. (Job 1:5, 18:19.)

5. Bi iwọ o ba wá Ọlọrun ti iwọ yoo si gbadura ẹbẹ si Olodumare. (Job 5:8; 11:13; 9:15.)

6. Bi iwọ bá mọ́ ti o sì duro ṣinṣin: njẹ nitootọ́ nisinsinyìí oun yoo dide fun ọ, oun a si tun sọ ibujokòó ododo rẹ di pupọ. ( Psm 7:6.)

7. Ipilẹṣẹ rẹ iba tilẹ kere ri, bẹẹ ni igbẹhin rẹ yoo pọ̀ si i gidigidi. (Job 42:12.)

8. "Emi bẹ̀ ọ, njẹ, bèèrè lọwọ awọn ara igbaani, ki o si kiyesi iwadi awọn baba wọn. (Deut 4:32; 32:7; Job 15:18.)

9. Nitori pe ọmọ-àná ni àwa, a kò si mọ̀ nkan, nitori pe ojìji ni ọjọ́ wa láyé. (Gen 47:9; 1 Kro 29:15; Job 7:6.)

10. Awọn ki yoo ha kọ́ ọ, wọn ki yoo si sọ fun ọ, wọn ki yoo si sọ̀rọ̀ lati inu ọkan wọn jade wá?

11. "Koriko odò ha lè dàgbà laini ẹrẹ̀, tabi iféfèé ha lè dàgbà lailomi?

12. Nigba ti ó wà ni tútù, ti a kò ge e lulẹ, ó rọ danu ṣaaju eweko miran gbogbo. ( Psm 129:6; Jer 17:6.)

13. Bẹẹ ni ipa ọ̀nà gbogbo awọn ti o gbàgbé Ọlọrun, ireti awọn alágàbàgebè yoo parun. (Psm 9:17; Job 11:20; Owe 10:28.)

14. Ifọkàntán ẹni ti a o ge kuro, ati igbẹkẹle ẹni ti yoo dabi ile alántakùn. (Isa 59:5,6.)

15. Yoo fi ara ti ile rẹ̀, ṣugbọn ki yoo lè duro, yoo si di i mú ṣinṣin ṣugbọn ki yoo le duro pẹ́. (Job 27:18.)

16. Ó tutu niwaju oorun, ẹka rẹ̀ si yọ jade ninu ọgbà rẹ̀. (Psm 37:35; 80:11.)

17. Gbongbo rẹ̀ ta yi ebè ká, o si wó awọn ibi okuta.

18. Bi o ba si parun kuro ni ipò rẹ̀, nigba naa ni ipo naa yoo sẹ́ ẹ pe: 'emi kò ri ọ rí!' (Job 7:10; Psm 37:36.)

19. Kiyesi i, eyi ni ayọ̀ ọna rẹ̀ ati lati inu ilẹ̀ ni omiran yoo ti hù jade wá. (Job 20:5; Onws 1:4.)

20. "Kiyesi i, Ọlọrun ki yoo ta ẹni-otitọ nù, bẹẹ ni ki yoo ran oniwa-buburu lọwọ. (Job 4:7; 21:30.)

21. Titi yoo fi fi ẹrin kun ọ lẹnu, ati ètè rẹ̀ pẹlu ihó ayọ̀. ( Psm 126:2; 132:16.)

22. Itiju ni a o fi bo awọn ti o korira rẹ, ati ibùjókòó eniyan buburu ki yoo sí mọ́." (Psm 35:26; 109:29; ẹsẹ 15.)

## ORI 9.

**Jobu fun Bildadi lesi nipa ẹkọ ati ẹri idajọ Ọlọrun.**

JOBU si dahun o si wi pe,

2. "Emi mọ̀ pe bẹẹ ni nitootọ! bawo ni eniyan yoo ha ṣe jẹ alare niwaju Ọlọrun? (Psm 143:2; Rom 3:20.)

3. Bi o ba ṣe pe, yoo bá a jà, oun ki

yoo lè da a lòhun ohun kan ninù ẹgbẹrun ọ̀ràn.

4. Ọlọgbọ́n-ninu ati alagbara ni ipá ni oun; tani o ṣe agídí sí i rí, ti o si bori!

5. Ẹni ti o ṣi oke ni ìdí, ti wọn kò sí mọ́: ti o bì wọ́n ṣubu ni ibinu rẹ̀. (Mika 1:4.)

6. Ti o mi ilẹ̀ ayé tìtì kuro ni ipo rẹ̀, ọ̀wọ̀n rẹ̀ si mi tìtì. (Isa 2:19,21; Hag 2:6; Heb 12:26; Job 26:11.)

7. Ti o paṣẹ fun oòrùn, ti oun kò si là, ti o si dí irawọ mọ́.

8. Oun nikanṣoṣo ni o na ojú ọrun, ti o si nrin lori igbi òkun. (Gen 1:6; Psm 104:2,3.)

9. Ẹni ti o dá irawọ Beari, Orioni ati Pleiade ati iyara pupọ ti gúsù. (Gen 1:16; Job 38:31; Amos 5:8.)

10. Ẹni ti nṣe ohun ti o tobi kọja àwárí lọ, ani ohun iyanu laini iye. ( Psm 71:15.)

11. Kiyesi i, o nkọja lọ ni ẹba ọ̀dọ̀ mi, emi ko sì ri i, o si kọja siwaju, bẹẹ ni emi ko ri ojú rẹ̀. (Job 23:8,9; 35:14.)

12. Kiyesi i, o jáagbà lọ, tani yoo dá a pada? Tani yoo bi i pe, 'Kinni iwọ nṣe yìí?'' (Isa 45:9; Rom 9:20; Job 11:10.)

**Jobu gba ara rẹ̀ ni ẹlẹṣẹ.**

13. "Ọlọrun kò ni fa ibinu rẹ̀ sẹhin, awọn oniranlọwọ igberaga a si tẹriba labẹ rẹ̀. (Job 26:12; Isa 30:7.)

14. Kinni ṣe ti emi o fi da a lohun, ti emi o fi maa ṣe àwáwí? (ẹsẹ 3,32.)

15. Bi o tilẹ ṣe pe mo ṣe olódodo, emi kò gbọdọ da a lohùn, ṣugbọn emi o gbadura ẹ̀bẹ̀ mi sọdọ onidajọ mi. (Job 10:15; 8:5.)

16. Bi emi ba si ké pe e, ti oun si dá mi lohun, emi ki yoo si gbagbọ pe, oun ti feti si ohùn mi.

17. Nitori pe o fi ẹfufu nla ṣẹ́ mi tútú, o sọ ọgbẹ́ mi di púpọ̀ lainidi. (Job 16:12,14; 2:3.)

18. Oun ki yoo jẹ ki emi fa èémí mi, ṣugbọn o fi ohun kikoro kun un fun mi. (Job 27:2.)

19. Bi mo ba sọ ti agbara, wo o! alagbara ni, tabi ni ti idajọ, tani yoo da àkókò fun mi lati rò?

20. Bi mo tilẹ dá ara mi lare, ẹnu ara mi ni yoo dá mi lẹbi; bi mo wi pe olódodo ni emi, yoo si fi mi hàn ni ẹni ti nṣaigbọran. (ẹsẹ 15,29.)

21. Olootọ ni mo ṣe, sibẹ emi ko kiyesi ẹ̀mí mi, iwa mi ni emi ìbá maa gàn. (Job 1:1; 7:16.)

22. Ohun kannaa ni, nitori naa ni emi ṣe sọ ọ: oun yoo pa ẹni-òtítọ́ ati eniyan buburu pẹlu. (Onws 9:2,3; Esk 21:3.)

23. Bi jàmbá bá pa ni lojijì, yoo fi ìdààmú aláìṣẹ̀ rẹ́rìn. ( Psm 64:4; Heb 11:36; 1 Pet 1:7.)

24. A fi ayé lé ọwọ eniyan buburu; o si bo awọn onidajọ rẹ̀ loju; bi kò ba ri bẹẹ, njẹ tani? (Job 10:3; 12:6; 12:17.)

**Jobu fi ẹsun kan Ọlọrun.**

25. Njẹ nisinsinyìí ọjọ́ mi yara ju ẹni ti nsare lọ, wọn fò lọ, wọn kò ri ire. (Job 7:6,7.)

26. Wọn kọja lọ bi ọkọ̀-ìféfèé ti nsure lọ; bi idì ti o nyara si ohun ọdẹ. (Hab 1:8.)

27. Bi emi bá wi pe, 'Emi o gbagbe ohun-ẹ̀dùn mi, emi o fi ọkàn lelẹ̀, emi o si rẹ ara mi lẹkun.' (Job 7:13.)

28. Ẹrù ìbànújẹ́ mi gbogbo bà mi, emi mọ̀ pe iwọ ki yoo mu mi bí alaiṣẹ. ( Psm 119:120; Job 7:21.)

29. Bi o ba ṣe pe eniyan buburu ni emi, njẹ kinni emi nṣe laalaa lasan sí?' (ẹsẹ 20.)

30. Bi mo tilẹ fi omi òjò dídì wẹ ara mi, ti mo fi omi-aró wẹ ọwọ́ mi mọ́. (Jer 2:22.)

31. Sibẹ iwọ o gbe mi bọ inu iho ọ̀gọ̀dọ̀, aṣọ ara mi yoo sọ mi di ẹni-irira.

32. Nitori oun ki iṣe eniyan bi emi, ti emi o fi da a lohùn ti awa o fi pade ni idajọ. (Onws 6:10; Rom 9:20; ẹsẹ 3; Psm 143:2.)

33. Bẹẹ ni ko si alatunṣe kan laarin wa, ti ìbá pari ìjà laarin awa mejeji. (1 Sam 2:25.)

34. Ki oun sa mu ọ̀pá rẹ́ kuro lara mi, ki ibẹru rẹ̀ ma si ṣe dáyà fò mi. (Job 13:21; Psm 39:10.)

35. Nigba naa ni emi ìbá sọ̀rọ̀, emi kò ba sì bẹ̀rù rẹ̀; ṣugbọn kò ri bẹẹ fun mi. (Job 13:22.)

## ORI 10.

**Aroye Jobu ntẹsiwaju.**

AGARA ìwà ayé mi da mi tán, emi o tu aroye mi sode lọdọ mi, emi o maa sọ ninu kíkorò ibanujẹ ọkàn mi. (1 A.Ọba 19:4; Job 7:16; 7:11.)

2. Emi o wi fun Ọlọrun pe, Maṣe dà mi lẹbi; fi hàn mi nitori idi ohun ti iwọ fi nba mi jà. (Job 9:29; Hos 4:1.)

3. O ha tọ́ si ọ ti iwọ ìbá maa ninilára, ti iwọ iba fi maa gan iṣẹ́ ọwọ rẹ, ti iwọ o fi maa tan imọlẹ si ìmọ̀ eniyan buburu? (ẹsẹ 8; Job 21:16; 22:18.)

4. Oju rẹ ha nṣe oju eniyan bi? Tabi iwọ a maa riran bi eniyan ti nriran? (1 Sam 16:7.)

5. Ọjọ́ rẹ ha dabi ọjọ eniyan, tabi ọdun rẹ ha dabi ọdun eniyan? ( Psm 90:4; 2 Pet 3:8.)

6. Ti iwọ fi nbèèrè aiṣedeede mi, ti iwọ si fi wá ẹṣẹ mi ri?

7. Iwọ mọ̀ pe emi kii ṣe oniwa-buburu, ati pe kò si ẹni ti ngbà kúrò lọwọ rẹ. (Job 9:21; 9:12.)

**Jobu gba Ọlọrun ni Ẹlẹda ati Olupamọ.**

8. Ọwọ́ rẹ ni o mọ mi, ti o si da mi; sibẹ iwọ tún yipada sí mi lati jẹ mí run. ( Psm 119:73.)

9. Emi bẹ̀ ọ, ranti pe iwọ ti mọ mi bi amọ̀; iwọ o ha si tun mu mi pada lọ sinu erùpẹ̀? (Gen 2:7; 3:19; Isa 64:8.)

10. Iwọ kò ha ti tú mi dà jade bi wàrà, iwọ kò si mu mi dìpọ̀ bi wàràkàṣì? (Psm 139:14–16.)

11. Iwọ sa ti fi awọ ati ẹran-ara wọ̀ mi, iwọ si fi egungun ati iṣan wun mí pọ.

12. Iwọ ti fun mi ni ẹ̀mí ati oju rere, ìbẹ̀wò rẹ si pa ọkàn mi mọ́. (Job 33:4.)

13. Nkan wọnyìí ni iwọ si ti fi pamọ ninu rẹ; emi mọ̀ pe, eyi nbẹ lọdọ rẹ.

**Jobu tun fi ẹ̀sùn kan Ọlọrun.**

14. Bi mo ba ṣẹ̀, nigba naa ni ki ọ sami si mi, ki o má si dari aiṣedeede mi jì. (Job 13:27; 9:28.)

15. Bi mo ba ṣe ẹni-buburu, ègbé ni fun mi! bi mo ba si ṣe ẹni-rere, bẹẹ ni emi kò sì lè gbe ori mi soke. Emi dààmú, mo si wo ipọnju mi. (Isa 3:11; Job 9:12,15; Psm 25:8.)

16. Bi emi bá gbe ara mi soke, iwọ nṣọdẹ mi bi kinniun; ati pẹlu, iwọ si nṣiṣẹ àrà si mi lara. (Isa 38:13; E.Jer. 3:10; Job 5:9.)

17. Iwọ si tún sọ awọn ẹlẹri rẹ si mi di ọ̀tun, iwọ si sọ irunu rẹ di pupọ si mi, ayipada ati ogun dó ti mi. (Job 16:8; 7:1.)

18. "Njẹ nitori kinni iwọ ṣe bí mi jade lati inú wá? A! emi ìbá kúkú ti kú, ojúkójú kì ìbá ti ri mi! (Job 3:11.)

19. Emi ìbá dabi ẹni ti kò sí rí, à bá ti gbe mi lati inu lọ si iboji.

20. Ọjọ́ mi kò ha kúrú bí? Dawọ duro, ki o si fi mi silẹ̀ ki emi fi àyà balẹ diẹ. (Job 14:1; 7:14,19; 9:27.)

21. Ki emi to lọ sibi ti emi ki yoo pada sẹhin mọ́, ani si ilẹ òkùnkùn ati òjìji iku. (Psm 88:12; 23:4.)

22. Ilẹ òkùnkùn bi òkùnkùn tìkárárẹ̀, ati ti òjìji ikú, nibi ti imọlẹ dabi okunkun."

## ORI 11.

**Sofari fi ẹ̀sùn irọ́ pipa ati aiṣootọ́ kan Jobu.**

NIGBA naa ni Sofari, ara Naama, dahun o si wi pe. (Job 8:2.)

2. "A ha le ṣe ki a má dahun si ọpọlọpọ ọ̀rọ̀, a ha si lè dare fun ẹni ti ẹnu rẹ̀ kun fun ọ̀rọ̀ sisọ?

3. Àmọ̀tán rẹ ha lè mu eniyan pa ẹnu wọn mọ́ bí? Bi iwọ ba yọṣùtì si ni, ki ẹnikẹni ma si doju ti ọ bi? (Jak 3:5; Job 17:2; 21:3.)

4. Nitori iwọ saa ti wi pe, ìlànà-ẹ̀kọ́ mi mọ́, emi si mọ́ loju Ọlọrun.' (Job 6:10; 10:7.)

5. Ṣugbọn o ṣe! Ọlọrun iba jẹ́ sọ̀rọ̀, ki o si ya ẹnu rẹ̀ si ọ lara.

6. Ki ó si fi àsiri ọgbọ́n hàn ọ pé, o pọ̀ ju òye eniyan lọ; nitori naa mọ̀ pe Ọlọrun kò bèèrè lọ́wọ́ rẹ tó bi ẹ̀bi-ẹ̀ṣẹ̀ rẹ títo. (Job 28:21; Esra 9:13.)

**O sọrọ nipa agbara ijọba Ọlọrun ati ailopin rẹ̀.**

7. Iwọ hai lè ṣe àwárí ohun ìjìnlẹ̀ Ọlọrun bí? Iwọ ha lè ridi Olodumare de opin rẹ̀ bi? (Onws 3:11; Rom 11:33.)

8. O dàbí giga ọrun, kinni iwọ lè ṣe? O jinlẹ ju isà-òkú lọ, kinni iwọ lè mọ̀? (Job 22:12; 17:16; Matt 11:23.)

9. Iwọ̀n rẹ̀ gun ju ayé lọ, o si ni ìbú ju òkun lọ.

10. Bi oun ba rekọja, ti o si hámọ́, tabi ti o si mu ni wá si idajọ, nje, tani yoo di i lọ́wọ́? (Job 9:12; Ifh 3:7.)

11. Oun sa mọ eniyan lasan, bi o ba si ri iwa-buburu pẹlu, oun kò ha ni bẹẹ wò bí? (Job 34:21–25; Psm 10:14.)

12. Ṣugbọn òmùgọ̀ eniyan yoo di ọlọ́gbọn, nigba ti ọmọ-kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́ ba bi eniyan.

**Sofari mu un dá Jobu loju pe bi ó bá ronupìwàdà Ọlọrun yoo mu un bọ̀ si ipò.**

13. "Bi iwọ ba tun ọ̀kan rẹ ṣe, iwọ yoo si na ọwọ rẹ sọdọ rẹ̀. (Psm 78:8; 88:9.)

14. Bi aiṣedéédé kan ba nbẹ lọwọ rẹ, mu un kuro si ọ̀nà jinjin réré, maṣe jẹ ki iwakiwa wà ninu àgọ́ rẹ. (Job 22:23; Psm 101:3.)

15. Nigba naa ni iwọ o gbe oju rẹ soke laini àbàwọ́n, ani iwọ o duro ṣinṣin, iwọ ki yoo si bẹ̀rù. (1 Jhn 3:21; Psm 27: 3.)

16. Nitori pe iwọ o gbagbe ọ̀ṣì rẹ, iwọ o si ranti rẹ̀ bi omi ti o ti ṣàn kọja lọ. (Isa 65:16; Job 22:11.)

17. Ọjọ aye rẹ yoo si mọ́lẹ̀ ju ọ̀sán gangan lọ, bi òkùnkùn tilẹ bò ọ́ mọlẹ nisinsinyìí, iwọ o dabi owurọ. (Psm 37:6; 112:4; Isa 58:8,10.)

18. Iwọ o si wà lailewu, nitori pe ireti wà, ani iwọ o rin ilé rẹ wò, iwọ o si sinmi ni alaafia. (Psm 3:5; Owe 3:24.)

19. Iwọ o si dubulẹ pẹlu ki yoo sì sí ẹni ti yoo dẹruba ọ, ani ọpọ eniyan yoo maa wá oju-rere rẹ. (ẹsẹ 18.)

20. Ṣugbọn oju eniyankeniyan yoo kùnà, wọn ki yoo lè sálà, ireti wọn a si dabi ẹni ti o nmi eemí rẹ̀ ìkẹhìn." (Deut 28:65; Jer 15:9.)

## ORI 12.

**Jobu kò gba ẹsùn ti Sofari fi kàn án.**

JOBU si dahun o si wi pe,

2. "Laisi iyemeji, ẹ̀yin ni awọn eniyan naa, ọgbọn yoo si kú pẹlu yin.

3. Ṣugbọn emi ni iyè ninu gẹgẹ bi ẹ̀yin: emi ki i ṣe ọmọ-ẹ̀hìn yin: ani, tani kò mọ̀ nkan bi iru wọnyìí? (Job 13:2.)

4. Emi dabi ẹni ti a nfi ṣe ẹlẹya lọdọ aladugbo rẹ̀. Emi ti mo nke pe Ọlọrun, ti o si da mi lohun: olootọ ẹni-iduro ṣinṣin, a fi mi nrẹ́rìń ẹlẹ́yà. (Job 6:10,20; 21:3; Psm 91:15; Job 6:29.)

5. Ninu ero ẹni ti ara rọ̀, ibẹ ni ẹ̀gàn fún oṣi wà. (Psm 123:4.)

6. Àgọ awọn ọlọṣa ngbèrú, awọn ti o si nmu Ọlọrun binu wà lailewu, awọn ẹni ti o si gbá oriṣa mu lọwọ wọn. (Job 9:24; 21:9; 22:18.)

**Jobu fi han pe Ọlọrun nri ohun gbogbo.**

7. "Ṣugbọn ni isinsinyìí, bi awọn ẹranko leere, wọn o kọ ọ ni ẹkọ, ati ẹyẹ oju-ọrun, wọn o si sọ fun ọ.

8. Tabi, ba irúgbìn ilẹ̀ sọ̀rọ̀, yoo si kọ́ ọ, awọn ẹja inu òkun yoo si sọ fun ọ.

9. Tani kò mọ̀ ninu gbogbo wọnyìí pe, ọwọ Oluwa ni o ṣe nkan yìí? (Isa 41:20.)

10. Lọwọ ẹni ti ohun alààyè gbogbo gbé wà ati ẹmi gbogbo aráyé. (A.A. 17:28.)

11. Eti kìí dan ọ̀rọ̀ wò bi, tabi adùn ẹnu ni ki i si tọ́ ounjẹ rẹ̀ wò? (Job 34:3.)

12. Awọn arúgbó ni ọgbọ́n wà fun, ati ninu gigun ọjọ ni òye. (Job 32:7.)

**Jobu fi titobi Ọlọrun hàn.**

13. "Pẹlu rẹ ni ọgbọn ati agbara, oun ni imọ̀ ati òye. (Job 9:4; 11:6.)
14. "Kiyesi i, o biwó, a kò si lè gbe ró mọ́, o sé eniyan mọ́, kò si sí iṣisilẹ kan. (Job 19:10; 37:7.)
15. "Kiyesi i, o da awọn omi duro, wọn si gbẹ, o si rán wọn jade, wọn si ṣẹ bo ilẹ ayé yípo. (1 A.Ọba 8:35; Gen 7:11.)
16. Pẹlu rẹ̀ ni agbara ati ọgbọn, ẹni ti nṣina ati ẹni ti nmu ni ṣìnà tirẹ̀ ni wọn nṣe. (ẹsẹ 13; Job 13:7,9.)
17. O mu awọn olugbimọ lọ nìhòhò, a si sọ awọn onidajọ di wèrè. (Job 3:14; 19:9; 9:24.)
18. O tú ìdè ọba, o si fi amure di wọ́n lọ́jàá. ( Psm 116:16.)
19. O mu awọn alufa lọ níhòhò, o si tẹ ori awọn alagbara ba.
20. O mu ọ̀rọ̀-ẹnu ẹni-igbẹkẹle kuro, o si ra awọn agbagba ni iyè. (Job 32:9.)
21. O bu ẹ̀gàn lu awọn ọmọ-alade, o si tu àmùrè awọn alagbara. (Psm 107:40; ẹsẹ 18.)
22. O ṣí ọ̀gbun kuro ninu òkùnkùn, o si mu òkùnkùn biribiri wá sinu imọlẹ. (Dan 2:22; 1 Kor 4:5; Job 3:5.)
23. O mú orilẹ-èdè tobi, o si run wọn, o sọ orilẹ-èdè di nla, o si lé wọn jade. (O.D. 107:38; Isa 9:3; Jer 25:9; Deut 12:20; Psm 78:61.)
24. O gba òye kuro lọwọ ìjòyè ayé, o si mu wọn rin kaakiri ninu iju nibi ti ọ̀nà kò si. (ẹsẹ 20; Psm 107:40.)
25. Wọn nfi ọwọ ta ilẹ̀ ninu òkùnkùn laisi ìmọ́lẹ̀, o si mu wọn ta gbọn-ọ́n-gbọn-ọ́n bi ọ̀mùtí. (Job 5:14; Psm 107:27.)

## ORI 13.

**Jobu fi ibinu hàn si awọn ọrẹ rẹ̀.**

WOO, oju mi ti ri gbogbo eyi ri, eti mi ti gbọ, o si ye e. (Job 12:9.)
2. Ohun ti ẹyin mọ̀, emi mọ̀ pẹlu, emi ki i ṣe ọmọ-ẹhin yin. (Job 12:3.)
3. Nitootọ emi yoo ba Olodumare sọ̀rọ̀, emi si nfẹ ba Ọlọrun sọ asọye. (Job 23:3,4; ẹsẹ 15.)
4. Ẹyin ni onihumọ èké, oniṣegun lásán ni gbogbo yín. ( Psm 119:69; Jer 23:32.)
5. O ṣe! ẹ ba kúkú pa ẹnu yin mọ́ patapata! eyiyìí ni ìbá si jẹ́ ọgbọn yin (Owe 17:28.)
6. Ẹ gbọ awiye mi nị isinsinyìí, ẹ si feti-silẹ si àròye ẹnu mi.
7. Ẹyin fẹ sọ isọkúsọ fun Ọlọrun? Ki ẹ si fi ẹ̀tàn sọ̀rọ̀ gbè e? (Job 36:4.)
8. Ẹyin fẹ ṣojusaju rẹ̀, ẹyin fẹ gbeja fun Ọlọrun.
9. O ha lè dara fun yin bi oun ba tu yin sita? Tabi ẹyin le tan an bi a ti ntan eniyan? ( Psm 44:21; Gal 6:7.)
10. Yoo maa ba yin wi nitootọ́, bi ẹyin ba ṣojusaju eniyan nìkọ̀kọ̀. (ẹsẹ 8.)
11. Iwa ọlá rẹ̀ ki yoo ba yin lẹẹru bi? Ipáyà rẹ̀ kì yoo pá yin láyà? (Job 31:23.)
12. Ọrọ òye yin dabi òwe eerú, odi-ilu yin dabi odi amọ̀. (Job 15:3.)

**Jobu fi iduro ṣinṣin rẹ̀ hàn.**

13. "Ẹ pa ẹnu yin mọ́, emi yoo si sọ̀rọ̀, ohun ti nbọ̀ wá ba mi, ki o maa bọ̀. (ẹsẹ 5.)
14. Njẹ nitori kinni emi o ṣe fi ehín mi bu ẹran ara mi jẹ, ti un o si gbe ẹ̀mí mi lé ara mi lọ́wọ? (1 Sam 19:5.)
15. Bi o tilẹ pa mi, sibẹ emi o maa gbẹ́kẹ̀le e, ṣugbọn emi o maa tenumọ ọ̀nà mi niwaju rẹ̀. ( Psm 23:4; Owe 14:32; Job 27:5.)
16. Eyi ni yoo si ṣe igbala mi pe: àgàbàgebè eniyan ki yoo wa siwaju rẹ̀. (Psm 5:5.)
17. Ẹ gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu mi ni ifayabalẹ, ati asọye mi leti yin. (Job 21:2.)
18. Wo o ni isinsinyìí emi ti làdí ọ̀ràn mi silẹ; emi mọ̀ pe a o da mi lare. (Job 23:4; 9:2.)
19. Tani ẹni ti yoo ba mi ṣaroye? Njẹ nigba naa emi yoo pa ẹnu mi mọ́, un ò si kú. (Isa 50:8; Job 40:4.)
20. Ṣugbọn kìkì pe ki o ṣe ohun meji

yìí si mi, nigba naa ni emi ki yoo si fi ara mi pamọ́, kuro fun ọ. (Job 9:34.)

21. Fa ọwọ́ rẹ sẹhin kuro lara mi; ma si jẹ ki ẹ̀rù rẹ pá mi laya. (Psm 39:10.)

22. Nigba naa ni ki o pè, emi o si dahun, tabi jẹ ki nmaa sọ̀rọ̀, ki iwọ si dá mi lohun. (Job 14:15.)

**Jobu bèèrè òye ẹ̀ṣẹ̀ ti oun ṣẹ̀.**

23. Melo ni aiṣedeede ati ẹṣẹ mi? Mu mi mọ̀ irekọja ati ẹṣẹ mi! (1 Sam 26:18.)

24. Nitori kinni iwọ ṣe pa oju rẹ mọ́, ti o si yàn mi lọta rẹ? (Deut 32:20; Psm 13:1; Job 19:11.)

25. Iwọ ha lè pá ewé láyà ti a nfẹ́ síhìn sọ́hùn; ki o si lepa akemọ̀le pòròpórò gbigbẹ! (Isa 42:3.)

26. Nitori pe iwọ kọwe ohun kíkorò si mi, o si mu mi jogun aiṣedeede èwe mi. (Psm 25:7.)

27. Iwọ kan àbà mọ mi lẹsẹ pẹlu, iwọ si nwo ipa ọna ìrìn mi ni àwòfín, iwọ si nfi ààlà yi gigisẹ mi ká. (Job 33:11.)

28. Ẹni ti nku lọ, bi ohun ti o ti rà bàjẹ́, ani bi aṣọ ti kòkòrò jẹrun. (Isa 50:9; Jak 5:2.)

## ORI 14.

**Jobu bá Ọlọrun sọ̀rọ̀.**

ENIYAN ti a bi ninu obinrin ọlọjọ diẹ ni, o si kun fun ipọnju. (Job 5:7; Onws 2:23.)

2. O jade wá bi itanna eweko, a si ge e lulẹ̀, o si nfò lọ bi òjìji, ko si duro pẹ́. (Psm 90:5,6; Jak 1:10; 1 Pet 1:24.)

3. Iwọ si nṣiju rẹ wo iru èyí yìí, iwọ si mu un wá sinu idajọ pẹlu rẹ. (Psm 144:3, 143:2.)

4. Tani o le mu ohun mimọ jade wá lati inu àìmọ́? Kò si ẹnikan! (Psm 51:2,10; Jhn 3:6; Rom 5:12; Ef. 2:3.)

5. Njẹ bi a ba ti pinu ọjọ rẹ̀, ti iye oṣù rẹ̀ nbẹ lọ́wọ́ rẹ, ti iwọ si ti pààlà rẹ̀ ti oun kò lè kọja rẹ̀. (Psm 139:16; Job 21:21; A.A. 17:26.)

6. Yipada kuro lọdọ rẹ̀, ki o lè sinmi titi yoo fi pé ọjọ rẹ̀ bi alágbàṣe (Job 7:19; 7:1.)

7. "Nitori pe ireti wà fun igi, bi a ba ge e lulẹ̀, pe yoo si tún rúwé, ati pe ẹ̀ka rẹ̀ titun, ki yoo dẹ́kun.

8. Bi gbongbo rẹ̀ tilẹ di ògbó ninu ilẹ, ti kùkùtẹ́ rẹ̀ sì kú ni ilẹ̀.

9. Sibẹ nigba ti o ba gboorun omi, yoo sọ, yoo si yọ ẹka jade bi eweko. (Isa 55:10.)

10. Ṣugbọn eniyan kú, a si da dùbúlẹ̀; ani eniyan mí èémí rẹ̀ ìkẹhìn, nibo ni ó tún wà? (Job 13:19.)

11. Bi omi ti ntan ninu ipa odò, ti odò si nfà ti si ngbẹ (Isa 19:5.)

12. Bẹẹ ni eniyan dubulẹ̀ ti kò si dide mọ́, titi ọrun ki yoo fi si mọ́, wọn ki yoo jí, a ki yoo ji wọn kuro loju oorun wọn. (Psm 102:26; A.A. 3:21; Ifh 20:11.)

13. A! Iwọ ìbá fi mi pamọ́ ni isàoku, ki iwọ si fi mi pamọ ni ìkọ̀kọ̀ titi ibinu rẹ yoo fi rekọja, iwọ iba làná ìgbà kan silẹ fun mi, ki o si rántí mi. (Isa 26:20.)

14. Bi eniyan ba ku yoo si tun yè bi? Gbogbo ọjọ igba ti a là silẹ̀ fun mi ni emi o duro dè, titi amudọ̀tun mi yoo fi dé. (Job 7:1.)

15. Nigba naa iwọ yoo pè, emi yoo sì dá ọ lóhùn; iwọ yoo sì nífẹ̀ẹ́ sí iṣẹ ọwọ́ rẹ. (Job 13:22.)

16. Ṣugbọn ni isinsinyìí iwọ nkaye ìṣísẹ̀ mi, iwọ kò fa ọwọ́ rẹ kuro nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi. (Job 10:6; 31:4; 34:21; Owe 5:21; Jer 32:19.)

17. A fi èdídí dí irekọja mi sinu àpò, iwọ si rán aiṣedeede mi pọ̀. (Deut 32:34; Hos 13:12.)

18. "Ati nitootọ́ oke nla ti o ṣubu, o dasan, a sì ṣí apata kuro ni ipò rẹ̀. (Job 18:4.)

19. Omi a maa yinrin okuta, iwọ a si mu omi ṣàn bo ohun ti o hù jade lori ilẹ̀, iwọ si sọ ireti eniyan di òfo. (Job 7:6.)

20. Iwọ si ṣẹgun rẹ̀ laelae, oun si kọja lọ, iwọ pa àwọ̀ oju rẹ dà, o si ran an lọ kuro. (Job 34:20; Jak 1:10.)

21. Awọn ọmọ rẹ bọ́ si ipò ọlá, oun kò si mọ̀, wọn si rẹ̀ silẹ, oun ko si kiyesi wọn. (Onws 9:5; Isa 63:16.)

22. Ṣugbọn ẹran-ara rẹ̀ ni yoo ri irora, ọkàn rẹ ni yoo si maa ni ibanujẹ ninu rẹ̀."

ORI 15.

**Ọrọ Elifasi lẹẹkeji pé Jobu lo ndá ara rẹ̀ lẹbi.**

NIGBA naa ni Elifasi, ara Tema, dahun wi pe,

2. "Ọlọgbọn ha lè maa fèsì pẹlu ìmọ̀ asán, ki o si maa fi afẹfẹ ila-oorùn kún ara rẹ̀ ninu? (Job 6:26.)

3. Oun a ha lè maa fi aroye sọ̀rọ̀ ti kò lérè, tabi pẹlu ọ̀rọ̀ ninu eyi ti kò le fi ṣe rere?

4. Ani iwọ nṣá ibẹru tì, iwọ si ndí adura lọna niwaju Ọlọrun.

5. Nitori pe ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ni o nkọ́ ẹnu rẹ, iwọ si yan ahọn alárékérekè. (Psm 36:3; Owe 16:23; Job 5:12,23.)

6. Ẹnu ara rẹ ni o da ọ lẹbi, ki i ṣe emi, ani ètè ara rẹ ni o jẹri tì ọ. (Job 9:20; Luk 19:22.)

**Elufasi tun wi pe Jobu ntan ara rẹ̀.**

7. Iwọ ha jẹ́ ọkunrin ti a kọ́kọ́ bi? Tabi a ha dá ọ ṣaaju awọn oke? (Job 38:4,21; Psm 90:2; Owe 8:25.)

8. Iwọ fetisi aṣiri Ọlọrun ri bí, tabi iwọ ha dá ọgbọn duro sọdọ ara rẹ bi? (Rom 11:34; Job 12:2.)

9. Kinni iwọ mọ̀ ti awa kò mọ, oye kinni o ye ọ ti kò si ninu wa. (Job 13:2.)

10. Eléwú ogbó ati ogbologbo eniyan wà pẹlu wa, ti wọn gbó ju baba rẹ lọ. (Job 32:6,7.)

11. Itunu Ọlọrun ha kéré lọdọ rẹ, tabi ọrọ kan ṣe jẹjẹ ju lọdọ rẹ. (Job 36:15,16; 2 Kor 1:3,4; Sek 1:13.)

**Ero Elifasi ni pe Ọlọrun ni o nṣe idajọ fun Jobu.**

12. Eeṣe ti àyà rẹ fi ndà ọ́ kiri, tabi kinni nmu oju rẹ ṣe wàìwàì?

13. Ti iwọ fi yi ẹ̀mí rẹ pada lòdì sí Ọlọrun, ti o fi njẹ ki ọ̀rọ̀kọrọ̀ maa bọ lẹnu rẹ bẹẹ? (Job 33:13.)

14. Kinni eniyan ti o fi mọ́? Ati ẹni ti a ti inu obinrin bí ti yoo fi jẹ́ olódodo? (Job 14:4; Owe 20:9; Onws 7:20; Job 25:4; Psm 51:5.)

15. Kiyesi i, Ọlọrun kò gbẹkẹle awọn ẹni-mímọ́ rẹ̀, ani awọn ọrun kò mọ́ ni oju rẹ̀. (Job 4:18; 25:5.)

16. Ambọ̀tori eniyan, ẹni irira ati eleeri, ti nmu ẹṣẹ bi ẹni mu omi. (Psm 14:1,3.)

**Elifasi si sọ ohun ti yoo pari eniyan ibi.**

17. Emi o fi hàn ọ, gbọ temi, eyi ti emi sì ri, oun ni emi o si sọ.

18. Eyi ti awọn ọlọgbọn ti pa ni itàn lati ọdọ awọn baba wọn wá, ti wọn kò si fi pamọ. (Job 8:8.)

19. Awọn ti a fi ilẹ-ayé fun nikan, alejo kan kò si là wọn kọja

20. Eniyan buburu nṣe làálàá, pẹlu irora ni gbogbo ọjọ́ rẹ̀, ani títí iye awọn ọdun ti a dá pamọ́ fun ikà-ènìyàn. (Job 27:13.)

21. Iró ìbẹ̀rù nbẹ ni eti rẹ̀, ninu igbadun ni oluparun yoo dide si i. (Job 18:11; 20:25; 1 Tess 5:3.)

22. Oun kò gbagbọ pe oun o jade kuro ninu òkùnkùn; a si pinnu rẹ̀ fun idà. (ẹsẹ 30; Job 27:14.)

23. O nwò kaakiri fun ounjẹ, wi pe, 'Nibo ni o wà,' o mọ pe ọjọ òkùnkùn sunmọ tòsí. (Psm 59:15; 109:10; Job 18:12.)

24. Ipọnju ati irora-ọkan nmú un bẹ̀rù; wọn a si bori rẹ̀ bi ọba ti a múra-silẹ̀ fun ogun;

25. Nitori pe o ti nawọ rẹ̀ jade lodi si Ọlọrun, o si mura rẹ̀ le lodi si Olodumare. (Job 36:9.)

26. O súré, pẹ̀lú agidi ọkàn lati kọlu u, ani pẹlu asà ti o nipọn

27. Nitori ti o ti fi ọ̀rá rẹ̀ bo ara rẹ̀ loju, o si fi jàbàjábà ọ̀rá si ẹ̀gbẹ́ rẹ̀. (Psm 17:10.)

28. O si gbe inu ahoro ilu ìtakété, ati ninu ile ti eniyan kò le gbe, ti o mura tan lati di àlàpà.

29. Oun ko le là, bẹẹ ni ọlá rẹ̀ kò lè duro pẹ́, bẹẹ ni kò lè ri gbòngbò dilẹ̀ mu lori ilẹ. (Job 27:16,17.)

30. Oun ki yoo jade kuro ninu òkùnkùn, ọ̀wọ́-ina ni yoo jó ẹ̀ka rẹ̀, ati

nipasẹ eemi ẹnu Rẹ̀ ni yoo kọja lọ kuro (Job 5:14; 22:20; 4:9.)

31. Ki oun má ṣe gbẹkẹle asán, ki o maṣe tan ara rẹ̀ jẹ; nitori pe asán ni èrè rẹ̀ yoo jasi. (Isa 59:4.)

32. A o san an fun un ṣaaju pipe ọjọ rẹ̀, ẹka rẹ̀ ki yoo si tutù. (Job 22:16; Psm 55:23; Job 18:16.)

33. Yoo si gbọn èso aláìpọ́n rẹ̀ danu bi àjàrà, yoo si rẹ itanna rẹ̀ nù bii ti igi olífì. (Hab 3:17.)

34. Nitori pe àjọ awọn agabagebe yoo tuka, iná ni yoo si jó àgọ́ abẹtẹlẹ. (Job 16:7; 8:22.)

35. Wọn loyun iwà-ikà, wọn si bi ẹ̀ṣẹ̀, inu-ọkan wọn si pèsè ẹ̀tàn." (Psm 7:14; Isa 59:4; Hos 10:13.)

## ORI 16.

**Èsì Jobu lẹẹkeji: o fi awọn ọrẹ rẹ̀ hàn bi aláìláanú.**

NIGBA naa ni Jobu dahun o si wi pe,

2. "Emi ti gbọ iru ohun pupọ bẹẹ ri; onitùnú ayọnilẹnu eniyan ni gbogbo yin. (Job 13:4.)

3. Ọrọ asán lè ni opin bi? Tabi kinni o kò ọ́ laya ti iwọ fi dahun? (Job 6:26.)

4. Emi pẹlu le sọrọ bi ẹyin, bi ẹ ba wa ni ipò mi, emi lè kó ọ̀rọ̀ pọ̀ si yin lọrun, emi a si mi ori mi si yin. (Psm 22:7; 109:25; Matt 27:39; E.Jer. 2:15.)

5. Emi i ba fi ọ̀rọ̀ ẹnu mi gba yin ni iyanju, ati ṣiṣi ete mi iba si tu ibanújẹ́ yin

6. Bi emi tilẹ̀ sọrọ, ibanujẹ mi kò tù; bi mo si tilẹ dakẹ, nibo ni a tù mi ninu dé?

7. Ṣugbọn ni isinsinyìí, Ọlọrun dá mi lagara, oun si ti mu gbogbo alabagbe mi takété (Job 7:3; ẹsẹ 20.)

8. Iwọ si ti ká mi lara kò, eyi ti o njẹri tì mí ati ara rírù mi yii nfi hàn, o jẹri tì mí loju. (Job 10:17; 19:20.)

9. Ninu ibinu rẹ̀ o fà mi ya, o si korira mi; o pa ehin rẹ̀ keke si mi, ọta mi si gboju rẹ̀ si mi. (Psm 35:16; Job 13:24.)

10. Wọn ti fi ẹnu wọn yán si mi, wọn gbá mi ni ẹ̀rẹ̀kẹ́ ni ìgba ẹ̀gàn, wọn si kó ara wọn jọ pọ̀ si mi. (Psm 22:13; E.Jer. 3:30; Mika 5:1; Psm 35:15.)

11. Ọlọrun ti fi mi le ọwọ ẹni-buburu, o si mu mi ṣubu si ọwọ eniyan ẹlẹ́ṣẹ̀. (Job 1:15,17.)

12. Mo ti jókòó jẹ́, ṣugbọn o fà mi já o si dì mi lọrun mú, o si gbọ̀n mi túútú, o si gbe mi kalẹ ṣe àmì-ìtafàsí rẹ̀. (Job 9:17.)

13. Awọn tafàtafà rẹ̀ duro yi mi ká kiri; o là mi laya pẹ̀rẹ̀, kò si dasi, o si tú òrónro ara mi dà silẹ. (Job 19:12; 27:22; 20:25.)

14. O la ihò si mi lara lera-lera, o súré kọlu mi bi akọni òmìrán (Job 9:17; Joel 2:7.)

15. Mo ran aṣọ-àpò bo ara mi, mo si rẹ ìwo agbara mi silẹ̀ ninu erùpẹ̀. (Gen 37:34; Job 30:19.)

16. Oju mi ti pọ́n fun ẹkún, òjìji ikú si ṣú si ìpènpeju mí. (ẹsẹ 20.)

17. Bi o tilẹ jẹ pe kò sí aiṣotitọ kan lọwọ mi, adura mi si mọ́ pẹlu (Job 27:4.)

**Ọkan Jobu mọ́.**

18. A! ilẹ̀ ayé, iwọ máṣe bo ẹ̀jẹ̀ mi, ki ẹkún mi maṣe ri ibi isinmi (Isa 26:21; Psm 66:18,19.)

19. Njẹ ni isinsinyìí kiyesi i! ẹlẹri mi nbẹ lọrun, ẹri mi nbẹ loke ọ̀run. (Rom 1:9.)

20. Awọn ọrẹ mi nfi mi ṣẹ̀sín, ṣugbọn oju mi nda omije sọ́dọ̀ Ọlọrun. (ẹsẹ 7; E.Jer. 2:19.)

21. Ibaṣepe ẹnikan lè maa ṣe alagbawi fun ẹnikeji lọdọ Ọlọrun, bi eniyan kan ti nṣe alagbawi fun ẹnikeji rẹ̀. (1 A.Ọba 8:45; Psm 9:4.)

22. Nitori nigba ti iye ọdun diẹ bá dé tán, nigba naa ni emi o lọ si ibi ti emi ki yoo padà bọ̀. (Onws 12:5.)

## ORI 17.

**Jobu bẹ̀bẹ̀ si Ọlọrun nitori idajọ awọn ọrẹ́ rẹ̀.**

EMÍ mi pinya, ọjọ mi parun, ibojì duro dè mi (Psm 88:3,4.)

2. Nitootọ! awọn ẹlẹyà wà lọdọ mi, oju mi si tẹmọ́ inunibini wọn. (ẹsẹ 6; 1 Sam 1:6,7.)

3. Njẹ nisinsinyìí, fi onígbọ̀wọ́ lélẹ̀ fun mi lọ́dọ̀ rẹ; tani oluwa rẹ̀ ti yoo ba mi so ọwọ́ lù? ( Psm 119:122; Owe 6:1.)

4. Nitori pe iwọ ti sé ọkan wọn kuro ninu oye, nitori naa iwọ ki yoo gbe wọn lékè. (Job 12:20.)

5. Ẹni ti o fi awọn ọ̀rẹ hàn lati lè pin ninu ẹrù rẹ̀, oun ni oju awọn ọmọ rẹ̀ yoo mófo. (Lef 19:16; Job 11:20.)

6. "O ti sọ mí di ẹni-ifipòwe fun awọn eniyan, niwaju wọn ni mo dabi ẹni ìtutọ́ sí loju. (Job 30:9,10.)

7. Oju mi ṣu bàìbàì pẹlu nitori ibanujẹ, gbogbo ẹya ara mi si dabi òjìji (Job 16:16, 16:8.)

8. Awọn olódọdo yoo yanu si èyí, ẹni aláìṣẹ̀ si binu si awọn agabagebe. (Job 22:19.)

9. Olododo pẹlu yoo di ọ̀nà rẹ̀ mu, ati ọlọ́wọ́ mímọ́ yoo maa mu ara le siwaju si i. (Owe 4:18; Job 22:30.)

10. Ṣugbọn ẹyin ẹ gbáradì ni isinsinyìí gbogbo yin, nitori emi kò ri ọlọ́gbọn kan ninu yin. (Job 12:2.)

11. Ọjọ temi ti kọja, èrò mi ti fà já, ani ero inu mi. (Job 7:6.)

12. A sọ oru di ọsán; wọn ni, 'Imọlẹ nsunmọ ibi okunkun',

13. Bi mo tilẹ ni ireti, isà-òkú ni ile mi, mo ti té ibusun mi sinu òkùnkùn. (Job 3:13; Psm 139:8.)

14. Emi ti wi fun ọ̀fìn pe, 'Iwọ ni baba mi,' ati fun kòkòrò pe, 'Iwọ ni ìyá mi ati arabinrin mi.' (Psm 16:10; Job 21:26; 24:20.)

15. Ireti mi ha dà ni isinsinyìí? Bi o ṣe ti ireti mi ni, tani yoo ri i? (Job 7:6.)

16. Yoo ha sọkalẹ lọ sinu ìdènà isà-òkú? Nigba ti a o jumọ sinmi pọ ninu erupẹ ilẹ̀. (Jona 2:6; Job 3: 17–19.)

ORI 18.

**Ọ̀rọ̀ Bildadi lẹẹkeji; o fi Jobu hàn bi ẹni ti ki i gbọràn.**

NIGBA naa ni Bildadi, ara Sua, dahun o si wi pe,

2. "Nigba wo ni ẹyin o tó fi idi ọ̀rọ̀ tì; ẹ ro o wò lẹhin eyi ni awa o to sọ̀rọ̀.

3. Nitori kinni a ṣe nkà wá si bi ẹranko, ti a si nkà wá si bi ẹni ẹ̀gàn loju yin! ( Psm 73:22; Job 36:14.)

4. Iwọ ti o nfa ara rẹ̀ ya pẹrẹpẹ̀rẹ ninu ibinu rẹ, ṣe ki a kọ ayé silẹ̀ nitori rẹ bi? Tabi ki a ṣi apata kuro ni ipò rẹ? (Job 13:14; 14:18.)

**Bildadi sọ nipa ibi ti yoo ṣẹlẹ̀ si eniyan buburu.**

5. "Nitootọ imọlẹ eniyan buburu ni a o pa kuro, ọ̀wọ́-iná rẹ̀ ki yoo si tan imọlẹ̀; (Owe 13:9; 20:20; 24:20.)

6. Imọlẹ yoo ṣókùnkùn ninu àgọ́ rẹ̀, fitila rẹ̀ ni a o si pa pẹ̀lú rẹ̀.

7. Ìrìn ẹ̀sẹ̀ agbara rẹ̀ ni a o gé kuro, ipinnu ọ̀kan oun tikararẹ̀ ni yoo bi i ṣubu (Owe 4:12; Job 5:13.)

8. Nipa ẹsẹ̀ oun tikararẹ ni a ti i bọ inu awọ̀n, o si nrin lori ọ̀fin. (Job 22:10; Psm 9:15; 35:8.)

9. Panpẹ́ ni yoo mu un ni gìgísẹ̀, awọn ikẹkùn yoo si ṣẹgun rẹ̀ (Psm 140:5; Job 5:5.)

10. A dẹkun silẹ̀ fun un lori ilẹ̀, a si wa ọ̀fin fun un loju ọna. ( Psm 69:22.)

11. Ẹ̀rù nla yoo ba a ni iha gbogbo, yoo si lepa ẹsẹ rẹ̀. (Job 15:21; Jer 6:25; 20:3.)

12. Ọwọ ebi yoo ba agbara rẹ̀, iparun ti ṣe tan lẹba ọdọ rẹ̀ láti bi i ṣubú. (Isa 8:21.)

13. Nipa àrùn ni a o jẹ awọ ara rẹ̀, akọbi iku ni yoo jẹ agbara rẹ̀ run.

14. A o fátu kuro ninu agọ rẹ̀ ti o gbẹ́kẹ̀lé, a o si mu un tọ ọba ẹrú wá. (Job 8:22; 15:21.)

15. Awọn ti ki i ṣe tirẹ̀ ni yoo si maa jokòó ninu agọ́ rẹ̀, imi-ọjọ ni a o fun kaakiri ibugbe rẹ̀. ( Psm 11:6.)

16. Gbòngbò rẹ̀ yoo gbẹ nisàlẹ̀, a o si gé ẹka rẹ̀ kuro loke (Isa 5:24; Hos 9:1–16; Amos 2:9; Mal 4:1; Job 15: 30,32.)

17. Iranti rẹ̀ yoo parun kuro ni ayé, ki yoo si orukọ rẹ̀ ni igboro ilu. (Psm 34:16; Owe 2:22; 10:7.)

18. A o si le e lati inu imọlẹ sinu òkùnkùn, a o si le e kuro ni ayé. (Job 5:14; 27:21–23.)

19. Ki yoo ni ọmọ bibi-inu rẹ̀, tabi ọmọ-ọmọ ninu awọn eniyan rẹ̀, bẹẹ ni ki yoo sí ẹnikan ti yoo ṣẹ́kù fun un ninu ile rẹ̀. (Isa 14:22; Jer 22:30.)

20. Ẹnu yoo ya awọn ti ìwọ̀-oòrùn si igba ọjọ́ rẹ̀, gẹgẹ bi ẹ̀rù iwárìrì ti bá awọn ti ìlà-oòrùn.

21. Nitootọ́ iru-bẹẹ ni ibùjókòó awọn eniyan buburu, eyi si ni ipò ẹni ti kò mọ Ọlọrun." (Jer 9:3; 1 Tess 4:5.)

## ORI 19

**Jobu da Bildadi lóhùn; o si ba awọn ọrẹ rẹ̀ wi.**

NIGBA naa ni Jobu dahun o si wi pe,

2. "Yoo ti pẹ tó ti ẹyin o fi maa bà mi ninu jẹ́, ti ẹyin o fi maa fi ọ̀rọ̀ ṣẹ́ mi si wẹ́wẹ́?

3. Ìgbà mẹwa ni ẹ̀yin ti ngàn mi, ṣe oju kò ti yin lati jẹ mi niyà?

4. Bi o ba tilẹ̀ jẹ pe, "Mo ṣina nitootọ́, iṣina mi wa lara emi tikarami. (Job 6:24.)

5. Bi o tilẹ̀ jẹ́ pe ẹyin ngbe ara yin si mi nitootọ́, ti ẹ si nfi ẹ̀gàn mi gun mi loju (Psm 35:26; 38;16.)

6. Ki ẹ mọ ni isinisinyìí pe: Ọlọrun ni o bì mí ṣubu, o si nà àwọ̀n rẹ̀ yi mi ka (Job 27:2; 18:8–10.)

7. Kiyesi i, emi nkigbe pe, "Ìwà-ìpá", ṣugbọn a kò gbọ temi; mo kigbe soke, bẹẹ ni kò sí idajọ. (Job 30:20.)

**Ọlọrun ni olupilẹṣẹ̀ ìjìyà yìí.**

8. O ṣọgbà dí ọ̀nà mi ti emi kò le kọja, o si mu okùnkùn ṣú si ipa ọ̀nà mi (Job 3:23; 30:26.)

9. O ti bọ́ ogo mi, ó sì ṣí adé kuro lori mi. (Psm 89:44; 89:39.)

10. O ti bà mi jẹ́ ni ìhà gbogbo, emi sì pin; ireti mi ni o si ti fàtu bí igi: (Job 12:14; 7:6; 24:20.)

11. O si tinabọ ibinu rẹ̀ si mi, o si kà mi si bi ọkan ninu awọn ọta rẹ̀. (Job 16:9; 13:24.)

12. Ẹgbẹ́ ogun rẹ̀ si dàpọ̀ si mi, wọn si tẹgun si mi, wọn si dó yi àgọ́ mi ka. (Job 30:12.)

**Awọn eniyan kọ̀ ọ́ silẹ.**

13. O mu awọn arakunrin mi jinna si mi rérè, ati awọn ojúlùmọ̀ mi di àjèjì sí mi nitootọ́.

14. Awọn àjọbí mi fà sẹhin, awọn ọ̀rẹ́ mi timọ́timọ́ si ti gbàgbé mi (ẹsẹ 19.)

15. Awọn ara inu ile mi ati awọn ọmọbinrin iranṣẹ mi kà mí sí àjèjì, emi jásí ajeji eniyan loju wọn. (Gen 14:14; Onws 2:7.)

16. Mo pe iranṣẹ mi, oun kò si da mi lohun, mo fi ẹnu mi bẹ̀ ẹ́.

17. Èémí mi sú aya mi, ati òórùn mi su awọn ọmọ inu iya mi

18. Ani awọn ọmọde fi mi ṣẹ̀sín: mo dide, wọn si sọ̀rọ̀ ẹ̀gàn sí mi. (2 A.Ọba 2:23.)

19. Gbogbo awọn ọrẹ̀ mi tímọ́tímọ́ korira mi, awọn olufẹ mi si pẹ̀hìndà sí mi. ( Psm 38:11; 55:13.)

**Jobu bẹ̀bẹ̀ fun aanu.**

20. Egungun mi lẹ̀ mọ́ awọ-ara mi àti mọ́ ẹran-ara mi, mo si bọ́ nipa awọ ehín mi. (Job 33:21; Psm 102:5.)

21. Ẹ ṣaanu fun mi, ẹ ṣaanu fun mi, ẹyin ọ̀rẹ́ mi, nitori ọwọ́ Ọlọrun ti bà mí. (Job 6:14; Psm 38:2.)

22. Nitori kinni ẹyin ṣe lepa mi, bi Ọlọrun? Eeṣe ti ẹran ara mi kò tẹ́ yín lọ́rùn! (Job 16:11.)

23. A! Ìbáṣe pe a le kọwé ọ̀rọ̀ mi ni isinsinyìí, ìbáṣe pe a lẹ̀ da a sinu iwe! (Isa 30:8.)

24. Ki a fi kalamu irin ati ti ọ̀jé kọ wọ́n sinu apata fun laelae (Jer 17:1.)

**Jobu ni ìgbẹ́kẹ̀lé ninu Oludande rẹ̀.**

25. Ati emi, emi mọ̀ pe Oludande mi nbẹ láàyè, àti pé ni ìkẹhìn oun ni yoo dide duro lori erupẹ ilẹ (Job 16:19; Psm 78:35; Jer 50:34.)

26. Ati lẹhin igba ti a ba ti pa awọ̀-ara mi run, nigba naa, laisi ẹran-ara mi ni emi o ri Ọlọrun. (Matt 5:8; 1 Kor 13:12; 1 Jhn 3:2.)

27. Ẹni ti emi o ri fun ara mi, ti oju mi o si wò, ki yoo si ṣe elomiran: Ọkàn mi sì dákú ni inu mi! (Psm 73:26.)

28. Bi ẹyin ba wi pe, "Awa o ti lepa rẹ̀ tọ!" ati pe, "Gbòngbò ọ̀rọ̀ naa ni a ri ni ọwọ́ mi." (Psm 69: 126.)

29. Ki ẹyin o bẹ̀rù idà; nitori pe ibinu ni nmu ìjìyà idà wá; ki ẹyin lè mọ̀ pe idajọ kan nbẹ (Job 22:4.)

## ORI 20.

**Ọ̀rọ̀ Sofari lẹẹkeji: o sọ nipa ibi ati iparun ti o nduro de eniyan buburu.**

NIGBA naa ni Sofari, ara Naama, dahun o si wi pe,

2. "Nitori naa ni èrò inu mi da mi lohùn, ati nitori eyi naa ni mo ṣe ṣaijáfara.

3. Mo ti gbọ́ ibawi ti o mu ẹ̀gàn bá mi, lati inu òye mi wa ni ẹ̀mí mi si ndá mi lohùn. (Job 19:3.)

4. Iwọ kò mọ eyi ri ni igba atijọ, lati igba ti a sọ eniyan lọ́jọ̀ silẹ ayé? (Deut 4:32.)

5. Pe, orin ayọ̀ eniyan buburu igba kukuru ni, ati pe, ni iṣẹju kan ni ayọ àgàbàgebè. (Psm 37:35; 73:19.)

6. Bi ọlanla rẹ̀ tilẹ gòkè de ọ̀run, ti ori rẹ̀ si kan ikuukuu awọsanma (Isa 14:13,14; Obad 3,4.)

7. Ṣugbọn yoo ṣègbé laelae bi igbe ara rẹ̀; awọn ti o ti ri i rí, yoo wi pe, 'Oun ha dà?' (Job 4:20; 7:10; 8:18.)

8. Yoo fò lọ bi àlá, a ki yoo sì ri i, ani a o lé e lọ bi ìran òru. (Psm 73:20; 90:5; Job 18:18; 27:21–23.)

9. Oju ti o ti ri i rí pẹlu, ki yoo si ri i mọ́, bẹẹ ni ibujokòó rẹ̀ ki yoo si ri i mọ́. (Job 7:8,9.)

10. Awọn ọmọ rẹ̀ yoo maa wa ojurere lọdọ tálákà, ọwọ́ rẹ̀ ni yoo si ko ọrọ̀ rẹ̀ padà. (Job 5:4; 27:16,17.)

11. Egungun rẹ̀ kún fun agbara igbà ewe rẹ̀, ṣugbọn yoo ba a dubulẹ ninu erùpẹ̀. (Job 13:26; 21:26.)

12. "Bi iwa buburu tilẹ dùn ni ẹnu rẹ̀, bi o tilẹ pa a mọ nisalẹ ahọn rẹ̀ (Owe 20:17; Psm 10:7.)

13. Bi o tilẹ da a si, ti kò si kọ ọ silẹ, ti o pa a mọ́ sibẹ ni ẹnu rẹ̀,

14. Sibẹ ounjẹ rẹ yoo yipada ninu ikùn rẹ, yoo si jásí oró paramọ́lẹ̀ ninu rẹ.

15. O ti gbe oró mì, yoo si tun bì í jade, Ọlọrun yoo pọ ọ yọ jade lati inu rẹ̀ wá.

16. Ó ti fa oró paramọlẹ̀ mu, ahọn ejò olóró ni yoo pa a. (Deut 32:24, 33.)

17. Ki yoo ri awọn ipa-odo, odo ti nṣan fun oyin ati òrí-àmọ́. (Job 29:6; Deut 32:13,14.)

18. Eso làálàá rẹ̀ ni yoo mú pada, ki yoo si gbe e mì, ninu èrè iṣẹ rẹ̀ ni ki yoo si ri igbadun. (ẹsẹ 10,15.)

19. Nitori ti o ninilara, o si ti pẹhìndà si talaka, nitori ti o fi agbara gbe ile ti oun kò kọ́. (Job 24:2–4.)

20. Nitori ojúkòkòrò rẹ̀ ko jẹ́ ki ọkàn rẹ̀ sinmi, ki yoo si le fi pamọ ninu awọn ohun ti ọkan rẹ̀ nfẹ. (Onws 5:13,14.)

21. Ko jẹ ki ohun-kohun ṣẹ́kù, nitori naa ọrọ̀ rẹ̀ ki yoo duro pẹ́. (Job 15: 29.)

22. Ninu títọ́ ẹ̀kún rẹ̀ ni yoo wa ninu ìhámọ́, ọwọ́ gbogbo awọn oniyọnu ni yoo dide si i lórí.

23. Nigba ti o ba si maa fi kún inu rẹ yó, ni Ọlọrun yoo fa riru ibinu rẹ̀ si i lori, yoo si rọ̀jò rẹ si i lori nigba ti o ba njẹun lọwọ. (Psm 78:30,31.)

24. Yoo sá kuro lọwọ ohun ìjà irin, ṣugbọn ọfà bàbà ni yoo baa. (Isa 24:18; Jer 48:43; Amos 5:19.)

25. A sì ta á, o si yọ jáde sita ara rẹ̀, bẹẹ ni ṣonṣo didan naa yọ jáde sita lati inú òrónro rẹ̀: ẹ̀rù-nlá sì bà lé e. (Job 16:13; 18:11.)

26. Ọ̀kùnkùn biribiri ni a ti pamọ́ fun iṣura rẹ̀, ina ti a kò fẹ ni yoo jo o run; yoo si jẹ eyi ti o kù ninu àgọ́ rẹ̀ run. (Job 18:18; Psm 21:9.)

27. Ọrun yoo fi ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ han, ayé yoo si dide duro si i. (Deut 31:28.)

28. Ohun-ini ile rẹ̀ ni a o kó lọ, ati ohun-ini rẹ̀ yoo ṣàn danu lọ ni ọjọ́

ibinu Ọlọrun. (Deut 28:31; Job 21: 30.)

29. Eyi ni ipin eniyan buburu lati ọdọ Ọlọrun wá, ati ogún ti a yàn silẹ fun un lati ọdọ Oluwa wa. (Job 27: 13.)

ORI 21.

**Èsì Jobu lẹẹkeji sí ọrọ Sofari.**

SUGBỌN Jobu dahun, o si wi pe,

2. "Ẹ fi pẹlẹpẹlẹ tẹti silẹ si ohùn mi, ki eyi jasi itunu yin.

3. Ẹ fara dà á fun mi, emi yoo sọrọ, lẹhin ti mo bá sọrọ tán, iwọ maa fi ṣẹsín nṣó. (Job 16:10.)

4. Bi o ṣe temi ni, aroye mi ha nṣe sí eniyan bi? Eeṣe ti ọkan mi yoo fi ṣe ai-balẹ? (Job 6:11.)

5. Ẹ wo mi fín, ki ẹnu si yà yin, ki ẹ si fi ọwọ lé ẹnu yin. (Ondj 18:19; Job 29:9; 40:4.)

6. Ani nigba ti mo ranti, ẹrù bà mi, iwárìrì si mu mi lara.

**Eniyan buburu maa mnilari ni ayé rẹ.**

7. Nitori kinni eniyan buburu fi wà láàyè, ti wọn gbo, ani ti wọn di alagbara ni ipa! (Job 12:6; Psm 73:3,12; Jer 12:1.)

8. Iru-ọmọ wọn fi idi kalẹ loju wọn pẹlu wọn, ati ọmọ-ọmọ wọn loju wọn. (Psm 17:14.)

9. Ile wọn wà laisí ewu, bẹẹ ni ọpa-inà Ọlọrun kò si lara wọn. (Psm 73:5.)

10. Akọ-malu wọn a maa gùn, ki i si sé, abomalu wọn a maa bi, ki i si ṣẹnú; (Eks 23:26.)

11. Wọn a maa rán awọn ọmọ wọn wẹwẹ jade bi agbo ẹran, awọn ọmọ wọn a si maa jó.

12. Wọn nkọrin si ohùn tamborini ati dùrù, wọn si nyọ si ohùn fèrè. (Psm 81:2; Job 30:31.)

13. Wọn lo ọjọ wọn ninu ọrọ; ni iṣe-jukan wọn a lọ si isà-òkú. (Job 36:11.)

14. Nitori naa ni wọn ṣe wi fun Ọlọrun pe, Lọ kuro lọdọ wa, nitori pe awa kò fẹ mọ ipa ọna rẹ! (Job 22:17; Owe 1:29.)

15. Kinni Olodumare jásí ti awa o fi maa sin in? Ere kinni a o si jẹ bi awa ba gbadura si i? (Eks 5:2; Job 34:9; Mal 3:14.)

16. Kiyesi i, alaafia wọn kò sí nipa ọwọ wọn, imọ eniyan buburu jìnnà si mi réré. (Job 22:18.)

**Ọlọrun a maa ṣe bi o ti fẹ si ẹni-rere ati si ẹni-buburu pẹlú.**

17. "Igbà melo ni ti a fi npa fitila eniyan buburu kú? (Igba melo ni) ti iparun wọn fi ndé bá wọn? (Igbà melo si ni ti) Ọlọrun fi npín irora ká ninu ibinu rẹ. (Job 18:5,6,12.)

18. Wọn dabi àgékù oko niwaju afẹfẹ, ati bi ìyàngbò, ti ẹfúùfù-nlá nfẹ lọ. (Psm 1:4.)

19. Ọlọrun to ẹṣẹ rẹ jọ fun awọn ọmọ rẹ, jẹ ki o san an fun wọn, ki wọn si mọ. (Eks 20:5.)

20. Oju rẹ yoo ri iparun ara rẹ, yoo si maa mu ninu ríru ibínú Olodumare. (Psm 75:8; Isa 51:17; Jer 25:15; Ifh 14:10.)

21. Nitori pe alaafia kinni o ni ninu ile rẹ lẹhin rẹ, nigba ti a ba ge iye oṣù rẹ kuro? (Job 14:5.)

22. Ẹnikẹni le kọ Ọlọrun ni ìmọ? Oun ni o sa nṣe idajọ ẹni ibi giga (Isa 40:13,14; Rom 11:34.)

23. Ẹni ti o kú ninu pipe agbara rẹ, ti o wà ninu ìrọra ti ailewu.

24. Ara rẹ kun fun ọrá, egungun rẹ si tutù fun mùdùnmúdùn

25. Ẹlomiran a si ku ninu kíkorò ọkan rẹ, ti kò si fi inu didun jẹun.

26. Wọn o dubulẹ bakan naa ninu erùpẹ, kokoro yoo si ṣubo wọn. (Onws 9:2; Job 24:20.)

**Jobu mọ pe awọn ọrẹ rẹ ki yoo gbọ tirẹ.**

27. "Kiyesi i, emi mọ èrò inu yin ati àrékérekè ọkàn yin lati ṣe lòdì si mi.

28. Nitori ti ẹyin wi pe, 'Nibo ni ile awọn ọmọ alade? Nibo si ni àgọ awọn

eniyan buburu gbe wà? (Job 12:21; 8:22.)

29. Ẹyin kò ha bèèrè lọwọ awọn ti nkọja lọ ni ọnà, ẹyin kò ha gba ẹri wọn gbọ pe,

30. "Eniyan buburu ni a fi pamọ fun ọjọ iparun, a o si mu wọn jade ni ọjọ idaamu. (Owe 16:4; 2 Pet 2:9; Job 20:28; Rom 2:5.)

31. Tani yoo sọ ipa-ọna rẹ ko o lòju, tani yoo si san an pada fun un ni eyi ti o ti ṣe?

32. Nigba ti a ba si gbe e sin, wọn yoo si maa ṣọ iboji òkú rẹ.

33. Ògúlùtu ọfin si dun mọ ọn, gbogbo eniyan si tọ ọ lẹhin, eniyan aìníye si ti lọ siwaju rẹ. (Job 3:22; 17:16.)

34. E ha ti ṣe ti ẹyin fi ntù mi ninu lásán! Kò sì sí ohun ti o kù ninu idahun yin bikoṣe èké (Job 16:2.)

ORI 22.

**Ọrọ Elifasi lẹẹkẹta: o nfi hàn pe Jobu nfi ẹsùn kan Ọlọrun.**

NIGBA naa ni Elifasi, ara Tema, dahun wi pe,

2. "Eniyan le ṣe rere fun Ọlọrun? Nitootọ Ọlọgbọn nṣe rere fun ara rẹ (Luk 17:10.)

3. Ohun ayọ hà ni fun Olodumare pe, olódodo ni iwọ? Tabi èrè ha ni fun un ti iwọ mu ọnà rẹ pé?

4. Ṣe nitori pe iwọ bẹru Rẹ ni o ṣe ba ọ wi ti o si ba ọ lọ sinu idajọ bí? (Job 14:3; Psm 143:2.)

5. Iwa-buburu rẹ kò ha tobi, ati ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lainíye? (Job 11:6; 15:5.)

**O ṣe itolẹsẹsẹ awọn ẹ̀ṣẹ̀ Jobu.**

6. Nitootọ iwọ gba ohun ẹ̀jẹ́ lọwọ arakunrin rẹ lainídi, iwọ si tú aṣọ awọn oníhòhò. (Eks 22:26; Deut 24:6,17; Esk 18:12,16.)

7. Iwọ kò fi omi fun aláàrẹ̀ mu, iwọ si háwọ́ ounjẹ fun ẹni ti ebi npa. (Matt 10:42; Job 31:31.)

8. Alagbara eniyan ni, o ni ilẹ, ọlọla eniyan ni o si tẹdo sinu rẹ.

9. Iwọ ti rán awọn opó padà lọ lọ́wọ ọ̀fo, ọrẹ ti o yẹ fun awọn ọmọ aláìní baba ni iwọ kò fi fun wọn. (Job 24:3; Isa 10:2.)

10. Nitori naa ni idẹkun ṣe yi ọ ká kiri, ati ibẹru òjiji nyọ ọ lẹnu.

11. Ìmọ́lẹ̀ rẹ di òkùnkùn ki o má bà ríran, ọpọlọpọ omi si bo ọ mọ́lẹ̀. (Job 5:14; Psm 69:2.)

12. "Ọlọrun kò ha jẹ Ẹmi giga ọrun? Sa wo ori awọn irawọ bi wọn ti ga to! (Job 11:7–9.)

13. Iwọ si wi pe, "Kini Ọlọrun mọ̀" Oun ha lè ṣèdájọ́ latinú ikuukuu awọsánmà dudu wá bí? (Psm 10:11.)

14. Ikuukuu awọsánmà ti o nipọn ni o bò ó lara, ti kò fi le ríran; o si nrin ninu ayika ọrun. (Job 26:9.)

**O si nfẹ ki Jobu ronupiwada.**

15. Ṣe iwọ fẹ rin ipa-ọ̀nà igbàani ti awọn eniyan buburu ti rìn

16. Ti a ge lulẹ kuro ninu ayé láìpé ọjọ wọn, ipilẹ wọn ti de bi odò ṣiṣan. (Job 15:32; 14:19; Matt 7:26,27.)

17. Awọn ẹni ti o wi fun Ọlọrun pe, 'Lọ kuro lọdọ wa! Ati pé kinni Olodumare yoo ṣe fun wa."

18. Sibẹ o fi ohun rere kun ile wọn! Ṣugbọn ìmọ̀ràn eniyan buburu jinna sí mi! (Job 12:6; 21:16.)

19. Awọn olódodo ri i, wọn si yọ̀, awọn alailẹ́ṣẹ̀ si fi wọn rẹrin ẹlẹya pe: (Psm 58:10; 107:42.)

20. 'Lotitọ awọn ọ̀tá wa ni a ge kuro, ina si jó iyoku wọn run.' (Psm 18:39; Job 15:30.)

**O si rọ Jobu lati ronupiwada ki Ọlọrun ba le mu un pada bọ sipo.**

21. Fa ara rẹ sunmọ Ọlọrun, iwọ ó si ri alaafia; nipa eyiyi, rere yoo de ba ọ. (Jer 9:24; Gal 4:9.)

22. Emi bẹ̀ ọ, gba ofin lati ẹnu rẹ wá, ki o si to ọ̀rọ̀ rẹ sí àyà rẹ. (Psm 138:4.)

23. Bi iwọ ba yipada sọdọ Olodumare, yoo sì gbe ọ ró, bi iwọ ba si mu ẹṣẹ jinna rere kuro ninu àgọ́ rẹ. (Job

8:5; Isa 19:22; A.A. 20:32; Job 11: 14.)

24. Bi iwọ ba tẹ́ wura daradara silẹ lori erùpẹ̀ ati wura ofiri labẹ okuta odò. (Psm 19:10.)

25. Ti o si fi Olodumare ṣe iṣura rẹ, ati okuta iyebiye rẹ. (Isa 33:6; Matt 6:20.)

26. Lotitọ nigba naa ni iwọ o ni inu didun ninu Olodumare, iwọ o si gbe oju rẹ soke sọdọ Ọlọrun. (Job 27:10; Isa 58:14.)

27. Bi iwọ ba gbadura rẹ sọdọ rẹ̀, yoo si gbọ́ tirẹ, iwọ o si san ẹ̀jẹ́ rẹ. (Job 33:26; Isa 58:9; Job 34:28; Psm 22:25.)

28. Iwọ o si gbìmọ̀ ohun kan pẹlu, yoo si fi idi rẹ̀ mulẹ fun ọ; imọlẹ yoo si mọ́ sipa ọ̀nà rẹ. (Psm 145:19.)

29. Nigba ti wọn ba rẹ̀ ọ silẹ̀, nigba naa ni iwọ o wi pe, Igbesoke nbẹ! Ọlọrun yoo si gba onirẹ̀lẹ̀ là! (Owe 29:23; Matt 23:12; 1 Pet 5:5.)

30. Yoo gba ẹni ti ki i ṣe alaijẹbi la, a o si gba a nipa mímọ́ ọwọ́ rẹ̀." (Job 42:7,8; 2 Sam 22:21.)

ORI 23.

**Ẹ̀sì Jobu si Eliasi lẹẹkẹta.**

NIGBA naa ni Jobu si dahun wi pe,

2. "Ani loni ni ọran mi korò; ọwọ́ mi si wuwo si ikerora mi. (Job 7:11; 6:2,3.)

3. A! Emi ìbá mọ̀ ibi ti emi iba ti wá Ọlọrun rí! Ki emi lè tọ ọ lọ si ibujokòó rẹ̀, (Deut 4:29; Psm 9:4.)

4. Emi ìbá si to ọ̀ràn naa niwaju rẹ̀, ẹnu mi ìbá si kún fun àròyé. (Job 13:18.)

5. Emi iba si mọ ọ̀rọ̀ ti oun iba fi dá mi lohùn, òye ohun ti ìbá wi a si ye mi.

6. Yoo ha fi agbara nla ba mi wijọ bi? Agbẹdọ̀! Oun yoo si ṣe àkíyèsì mi: (Job 9:4.)

7. Nibẹ ni olododo le jíròrò pẹlu rẹ, bẹẹ ni emi o si bọ́ lọwọ onidájọ́ mi lae-lae. (Job 13:3,16.)

8. Si wo! Bi emi bá lọ si iha ila-oò-rùn, oun kò si nibẹ, ati ni ipadasẹ́hìn mi, emi ko si roye rẹ̀: (Job 9:11.)

9. Niha apa òsì mi, emi kò ri i, o fi ara rẹ̀ pamọ niha apa ọ̀tún, ti emi kò lè ri i.

10. Ṣugbọn oun mọ ọna ti emi ntọ̀, nigba ti o ba dan mi wò, emi o jade bi wura. (Psm 139:1–3.)

11. Ẹsẹ̀ mi ti tẹle ipasẹ irin rẹ̀, ọna rẹ̀ ni mo ti kiyesi, ti nkò si yà kuro. (Psm 44:18.)

12. Bẹẹ ni emi kò pada sẹhin kuro ninu ofin ẹnu rẹ̀, emi si pa ọrọ ẹnu rẹ̀ mọ ju ofin inu mi lọ. (Jhn 4:32,34.)

13. Ṣugbọn onínúkan ni oun, tani yoo si yi i padà? Eyi ti ọkan rẹ̀ si ti fẹ́, eyi naa ni o nṣe. (Job 9:12; 12:14; Psm 115:3.)

14. Nitootọ́ ohun ti o ti yàn silẹ fun mi ni o nṣe, ọpọlọpọ iru bẹẹ ni o wà ni ọkan rẹ̀. (1 Tess 3:3.)

15. Nitori naa ni ara kò ṣe rọ̀ mi niwaju rẹ̀, nigba ti mo ba ro o, ẹ̀rù a bà mi.

16. Nitori pe Ọlọrun ti pá mi láyà, Olodumare si ndaamu mi. (Psm 22: 14; Jer 52:46.)

17. Nitori ti a kò ti ge mi kuro niwaju okunkun, bẹẹ ni ko pa okunkun-biribiri mọ́ kùrò niwaju mi. (Job 10: 18,19; 19:8.)

ORI 24.

**Ijiya ẹṣẹ ẹni-ibi ni ki i fi igbagbogbo farahàn.**

EṢE ti Olodumare kò ṣe pa àkókò mọ́ fun idajọ. "Eesi ti ṣe ti awọn ojúlùmọ̀ rẹ ko fi ri ọjọ rẹ̀? (Psm 31:15; Jer 46:10.)

2. Awọn kan ṣí àmì ààlà ilẹ̀, wọn si fi agbara kó agbo ẹran lọ, wọn si bọ́ wọn. (Deut 19:14; 27:17; 28:31.)

3. Wọn a si da kẹtẹkẹtẹ alainibaba lọ, wọn a si gba ọ̀dá-malu opó ni ohun ògo. (Eks 22:26; Deut 24:6,10,12,17; Job 22:6.)

4. Wọn a bi alaini kuro loju ọ̀nà,

awọn talaka ayé a si fara wọn pamọ. (Deut 24:14; Owe 28:28.)

5. Kiyesi i, bi kẹtẹkẹtẹ igbẹ ninu ijù ni wọn njade lọ si iṣẹ wọn; wọn a tete dide lati wá ohun ọdẹ; ijù pese ounjẹ fun wọn ati fun awọn ọmọ wọn. (Job 39:5–8; Psm 104:23.)

6. Olukuluku a si ṣa ọkà ounjẹ-ẹran rẹ ninu oko, wọn a si ká ọgba-ajara eniyan buburu.

7. Nihoho ni wọn sun laini aṣọ, wọn kò si ni ibora ninu òtútù. (Eks 22:26; Job 22:6.)

8. Ọwara òjò òkè-nla si pa wọ́n, wọ́n si lẹ̀mọ́ apata nitori ti kó si aabò. (E.Jer. 4:5.)

9. Wọn já ọmọ-alainibaba kúrò lẹnu-ọmu, wọn si gba ògò lọwọ talaka. (Deut 24:17.)

10. Wọn rin kiri nihoho laini aṣọ, awọn ti ebi npa rẹrù ìdì-ọkà.

11. Awọn ẹni ti nfun òróró ninu agbala wọn, ti wọn si ntẹ ifunti àjàrà, oungbẹ sin ngbẹ wọn.

12. Awọn eniyan nkerora lati ilu wá, ọkan awọn ẹni ti o gbọgbẹ kigbe sókè; sibẹ Ọlọrun kò kiyesi ìjìyà wọn. (Jer 51:52; Esk 26:15; Job 9:23,24.)

13. "Awọn ni ẹni ti o ṣọtẹ si imọlẹ, wọn kò mọ ipa ọna rẹ, bẹẹ ni wọn kò duro nipa ọ̀nà rẹ. (Isa 5:20; Jhn 3:19.)

14. Panipani á dìde ní afẹmọjumọ lati pa talaka ati aláìní, ati loru á di olè. (Mika 2:1; Psm 10:8.)

15. Oju alágbèrè pẹlu duro de wiri-wiri ọjọ, o ni, 'Oju ẹnikan ki yoo ri mi,' o si fi ìbòjú bojú rẹ. (Owe 7:9; Psm 10:11.)

16. Ni òkùnkùn wọn a maa tọ ojule gbogbo, Ni ọsàn wọn a fi ara pamọ sinu ile; wọn kò mọ imọlẹ. (Eks 22:2.)

17. Nitori pe òru dúdú ni owurọ fun gbogbo wọn; nitori ti wọn wà ni irẹpọ ẹ̀rù òru-dúdú. (Psm 91:5.)

18. Iwọ wi pe, "Iru wọn ni a yara gbá kọja lọ loju omi; ifibu ni ìpín wọn ni ayé, ẹnikan ko rìn kọja mọ́ ni ọ̀nà ọgba-ajara wọn. (Job 9:26; Psm 90:5.)

19. Ọgbẹlẹ̀ ati ooru ni o nmu omi òjò-dídì yọ́ gbẹ, bẹẹ ni isà-oku ṣe nrun awọn ẹlẹ́ṣẹ̀. (Job 6:17; 21:13.)

20. A gbàgbé wọn ni orita-mẹrin ìlú, Orukọ wọn ni a kò sì rántí mọ́ bẹẹ ni a ṣẹ́ iwa buburu wọn, bi igi. (Psm 31:12; Owe 10:7.)

21. "Wọn nfi àgàn ti ko bi ri ṣe ìjẹ jẹ, wọn kò si ṣe rere si opó. (Job 22:9.)

22. Sibẹ naa Ọlọrun fa ọjọ alagbara gùn pẹlu agbara rẹ. Wọn si gberasọ nigba ti wọn kò nireti ayé. (Deut 28:66.)

23. O si fun wọn ni ààbò, ati ninu eyi ni a si tì wọn lẹhin, oju rẹ̀ si wà ni ipa-ọna wọn. (Job 12:6; 11:11.)

24. A gbe wọn lékè nigba diẹ, wọn kọja lọ, a si rẹ̀ wọ́n silẹ, a si mu wọn kuro ni ọ̀nà, bi awọn ẹlomiran gbogbo, a si ge wọn kuro bi ori ṣírí ìtú-ọkàbà-bà. (Psm 37:10; Job 14:21; Isa 17:5.)

25. Njẹ, bi ko bá rí bẹẹ ni isinsinyìí, tani yoo mu mi leke, ti yoo sì fi ọ̀rọ̀ mi ṣe ọ̀rọ̀ aṣán. (Job 6:28; 27:4.)

## ORI 25.

**Ọ̀rọ̀ Bildadi lẹẹkẹta: kò si olootọ eniyan niwaju Ọlọrun.**

NIGBA naa ni Bildadi, ara Sua, dahun wi pe,

2. "Ijọba ati ẹ̀rù nbẹ lọdọ Ọlọrun, oun ni o nṣe ìlàjà ni ibi gigagiga rẹ̀. (Job 9:4; Ifh 1:6; Job 22:12.)

3. A ha lè mọ iye awọn ọmọ-ogun rẹ̀ bí? Tabi ara tani imọlẹ rẹ̀ kò mọ́ sí? (Jak 1:17.)

4. Nigba naa, bawo ni eniyan yoo ha ṣe mọ́ niwaju Ọlọrun? Tabi ẹni ti a bi ninu obinrin yoo ha ṣe mọ́? (Job 4:17; Psm 143:2; Job 14:4.)

5. Kiyesi i, òṣùpá paapaa kò mọ́lẹ̀, ani awọn irawọ kọ̀ mọ́ ni oju rẹ̀. (Job 31:26; 15:15.)

6. Ámbọ̀tori eniyan ti o jẹ́ ìdin, ati ọmọ eniyan, ti o jẹ́ kòkòrò! (Job 7:17; Psm 22:6.)

ORI 26.

**Idahun Jobu si oro Bildadi iketa: o mọ titobi ati ọlanla Ọlọrun.**

SUGBỌN Jobu si dahun wi pe,
2. "Bawo ni iwọ ṣe ran ẹni ti kò ni ipá lọwọ, bawo ni iwọ ṣe gba apa ẹni ti kò ni agbara là? (Psm 71:9.)
3. Bawo ni iwọ ṣe gba ẹni ti kò ni ọgbọ́n ni ìmọ̀ràn, tabi ọna pupọ wo ni iwọ gba fi ìmọ̀ fún un.
4. Pẹlu iranlọwọ tani iwọ fi sọ̀rọ̀, ati ẹmi tani o ti ọ̀dọ̀ rẹ wa?
5. Òjìji awọn òkú nísàlẹ̀ wárìrì; awọn omi ati awọn olùgbé rẹ̀.
6. Ihoho ni isà-òkú wà niwaju Ọlọrun, ibi iparun (Abaddoni) kò ní ààbò lori. (Psm 139:8,11; Heb 4:13.)
7. O na ariwa sóde lori òfo, ó si fi ayé rọ̀ lori ohun-àìsí. (Job 9:8.)
8. O di awọn omi pọ̀ ninu ikuukuu awọsanma rẹ̀ ti o nipọn; ikuukuu awọsanma kò si ya nisalẹ̀ wọn. (Owe 30:4.)
9. O si bò oju itẹ rẹ̀, o si tẹ́ ikuukuu awọsanma rẹ̀ si i lori. (Psm 97:2.)
10. O fi ìdè yi omi-okun ká, titi de ààlà imọlẹ ati okunkun. (Job 38:8–11; Owe 8:29; Job 38:19,20,24.)
11. Ọwọ̀n opò ọ̀run wárìrì, ẹnu si yà wọn si ibawi rẹ̀.
12. O fi ipa rẹ damu omi-okun, nipa òye rẹ̀ o lu agberaga Rahabu. (Eks 14:21; Isa 51:15; Jer 31:35.)
13. Nipa eemi rẹ̀ ni o ti ṣe ọrun lọ́ṣọ, ọwọ rẹ̀ ni o fi mọ ejo ti nsare lọ. (Job 9:8; Isa 27:1.)
14. Kiyesi i, eyi ni diẹ ninu ọnà rẹ̀, ohùn eyi ti a gbọ ti kere to! ṣugbọn àará ipa rẹ̀ tani oye rẹ̀ lè yé?" (Job 36:29.)

ORI 27.

**Jobu jẹri si otitọ tí o nsọ.**

PẸLUPẸLU Jobu si tun sọ kún ọ̀rọ̀ owe rẹ̀ o si wi pe, (Job 13:12; 29:1.)
2. "Bi Ọlọrun ti nbẹ ẹni ti o gba ẹ̀tọ́ mi lọ, ati Olodumare ti o bà mi lọ́kàn jẹ́. (Job 34:5; 9:18.)
3. Niwọn igba ti ẹ̀mí mi nbẹ ninu mi, ati ti eemi Ọlọrun nbẹ ni ihò imu mi. (Job 32:8; 33:4.)
4. Ete mi ki yoo sọrọ èké, bẹẹ ni ahón mi ki yoo sọ̀rọ̀ ẹ̀tàn. (Job 6:28.)
5. Ki a má ri pe emi nda yin láre, titi emi o fi kú emi ki yoo si mu ìwà-otítọ́ mi kuro lọ̀dọ̀ mi. (Job 2:9; 13:15.)
6. Ododo mi lemi dimu ṣinṣin, emi ki yoo si fi i silẹ̀: àyà mi ki yoo si gan ọjọ kan ninu ọjọ ayé mi. (Job 2:3; 13:18; A.A. 23:1.)

**Jobu korira ẹni-ibi.**

7. Ki ọta mi o dabi eniyan buburu, ati ẹni ti ndide si mi o dabi ẹni aláìṣòdodo.
8. Nitori pe kinni ireti àgàbàgebè, nigba ti Ọlọrun ba ge e kuro, nigba ti Ọlọrun ba mu ẹmi rẹ̀ lọ? (Job 8:13; 11:20.)
9. Ọlọrun ha lè gbọ́ adura rẹ̀, nigba ti ipọnju bá dé si i? (Job 35:12; Owe 1:28; Isa 1:15; Jer 14:12; Mika 3:4.)
10. Oun ha lè ni inu-didun si Olodumare, oun ha lè maa ké pe Ọlọrun nigba gbogbo? (Job 22:26,27.)
11. Emi o kọ yin ni èkọ́ ni ti ọwọ Ọlọrun: eyi ti nbẹ lọdọ Olodumare ni emi ki yoo fi pamọ́.
12. Kiyesi i, gbogbo yin ni o ti ri i; eeṣe nigba naa ti ẹyin fi di asán bẹẹ pátápátá?
13. "Eyi ni ipin eniyan buburu lọdọ Ọlọrun, ati ogun awọn aninilara, ti wọn o gba lọwọ Olodumare. (Job 20:29; 15:20.)
14. Bi awọn ọmọ rẹ̀ ba di pupọ, fun idà ni, awọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ ki yoo yó fun ounjẹ. (Deut 28:41; Hos 9:13; Job 20:10.)
15. Awọn ti o kù ninu tirẹ̀ ni ajakalẹ-àrùn: yoo sinku rẹ̀: awọn opó rẹ̀ ki yoo si sọkun. (Psm 78:64.)
16. Bi o tilẹ kó fadaka jọ bi erupẹ, ti o si da aṣọ jọ bi amọ̀. (Sek 9:3.)
17. O le maa ko o jọ, ṣugbọn awọn

olootọ́ ni yoo lò ó; awọn alaiṣẹ̀ ni yoo si pin fadaka naa. (Owe 28:8; Onws 2:26.)

18. Oun kọ́ ile rẹ̀ bi kòkòrò aṣọ, ati bi àtíbàbà ti oluṣọ kọ́.

19. Yoo dubulẹ̀ ni ọlọ́rọ̀, ṣugbọn ki yoo ni àkójọ mọ́, o la oju rẹ̀, ọrọ̀ rẹ̀ kò sì si mọ́. (Esk 29:5; Job 7:8,21.)

20. Ẹ̀rù nla bá a bi omi ṣiṣan, ẹ̀fúfù nla jí i gbe lọ loru. (Job 15:21; 20:8.)

21. Ẹfúùfù ila-oorùn gbe e lọ, oun si lọ; ati bi ìjì nla o si fa a kuro ni ipò rẹ̀. (Job 21:18; 7:10.)

22. Nitori pe Olodumare kọlu u, lalai dasí; oun si fi ikanju sá kuro ni ọwọ́ rẹ̀. (Jer 13:14; Esk 5:11; Job [illegible]:20.)

23. Awọn eniyan yoo si patẹwọ si i lori, wọn o si ṣe ṣiọ̀ si i lati ipo rẹ̀. (E.Jer. 2:15; Job 18:18.)

## ỌRI 28.

**Ọna wo ni a le gbà ri ọgbọ́n tootọ.**

NITOOTỌ iho ti a ti nwa fadaka nbẹ, ati ibi ti a ti nda wura.

2. Ninu ilẹ̀ ni a ti nwa irin, bàbà ni a si nda lati inu okuta wá. (Deut 8:9.)

3. Eniyan fi opin si òkùnùn, o si ṣe awari okuta òkùnkùn ati ti inu ojiji iku si iha gbogbo.

4. Wọn wa iho ilẹ̀ jinna si ibi ti awọn eniyan ngbe, awọn ibi ti ẹsẹ̀ eniyan ti gbàgbe, wọn sọkalẹ̀ si isalẹ, wọn rọ́ si isalẹ jinna si awọn eniyan, wọn si nlọ siwa sẹhìn.

5. Bi o ṣe ti ilẹ̀ ni, ninu rẹ̀ ni ounjẹ ti njade wá, ṣugbọn nisalẹ̀-ilẹ̀ ni o nyi soke bi eyi ti a nfi iná ṣe. (Psm 104:14.)

6. Okuta ibẹ ni ibi okuta Safiri, ó sì ní erupẹ wura.

7. "Ipa ọna naa ni ẹyẹ kò mọ̀, ati oju gúnnugún kò ri i rí.

8. Awọn ọmọ kinniun kò rin ibẹ̀ rí, bẹẹ ni kinniun ti nke ramúramù ko kọjá nibẹ̀ ri.

9. O fi ọwọ́ rẹ̀ lé akọ apata, o yi oke-nla po lati idi rẹ̀ wá. (Deut 8:15; 32:13.)

10. O si la ipa-odò ṣíṣàn ninu apata, oju rẹ̀ si ri ohun iyebiye gbogbo.

11. O si sé iṣàn odo ki o má ṣe kún akunya, o si mu ohun ti o pamọ hàn jade wá si imọlẹ.

12. "Ṣugbọn nibo ni a o gbe wá ọgbọn ri, nibo si ni ibi òye wà? (ẹsẹ 23,28.)

13. Eniyan kò mọ iye rẹ̀, bẹẹ ni a kò lè ri i ni ilẹ awọn alààyè. (Owe 3:15.)

14. Ọgbun wi pe, "Kò si ninu mi", omi-okun si wi pe, "Kò si ninu mi.

15. A kò lè fi wura rà a, bẹẹ ni a kò lè fi oṣuwọn wọn fadaka ni iye rẹ̀.

16. A kò le fi wura Ofiri diyele e, pẹlu okuta oniksi iyebiye, ati okuta Safiri.

17. Wura ati okuta Kristali kò tó ẹgbẹ rẹ̀, bẹẹ ni a kò lè fi ohun èlò wura ṣe pàṣípàrọ̀ rẹ̀. (Owe 8:10; 16:16.)

18. A kò lè darukọ iyùn tabi okuta perli; iye ọgbọ́n si ju okuta rubi lọ. (Owe 3:15; 8:11.)

19. Okuta tọpasi ti Etiopia kò tó fi wéra pẹlu rẹ̀, bẹẹ ni a kò lè fi wura daradara diye le e. (Owe 8:19.)

20. "Nibo ha ni ọgbọn ti jade wá; tabi nibo ni ibi oye wà? (ẹsẹ 23,28.)

21. A ri i pe, o pamọ kuro ni oju awọn alààyè gbogbo, o si fara sin fun ẹyẹ oju ọ̀run.

22. Ibi iparun (Abaddoni) ati iku wi pe, 'Awa ti fi etí wa gburo rẹ̀. (Job 26:6.)

23. Ọlọrun ni o moye ipa ọ̀nà rẹ̀, o si mọ ipo rẹ̀, (ẹsẹ 23–28.)

24. Nitori pé o woye de opin ayé, o si ri gbogbo isalẹ ọ̀run. (Psm 33:13; Owe 15:3.)

25. Nigba ti o fi iwọn fun afẹ́fẹ́, ti o si fi oṣuwọn wọn omi. (Psm 135:7; Job 12:15.)

26. Nigba ti o paṣẹ fun òjò, ti o si la ọ̀nà fun mànàmáná aará: (Job 37:6,11,12; 37:3; 38:25.)

27. Nigba naa ni o rí i, o si sọ ọ jade, o pèsè rẹ̀ silẹ, ani o si wadi rẹ̀ rí.

28. Ati fun eniyan ni o wi pe, "Kiyesi i; ìbẹ̀rù Oluwa, eyi ni ọgbọ́n

ati lati jade kuro ninu iwa-buburu eyi ni oye!" (Deut 4:6; Psm 111:10; Owe 1:7, 9:10.)

## ORI 29

**Jobu sọrọ nipa igbesiaye rẹ.**

PẸLUPẸLU Jobu si tun gbẹnu lẹ ọrọ rẹ o si wi pe, (Job 13:12; 27:1.)

2. "A! ibaṣe pe emi wà bi ni igba awọn oṣu atijọ, bi ni ọjọ ti Ọlọrun pa mi mọ́. (Jer 31:28.)

3. Nigba ti fitila rẹ tàn si mi lori, ati nipa imọlẹ rẹ emi rin ninu okùnkùn já. (Job 11:17.)

4. Bi mo ti ri nigba ọ̀dọ́ mi, nigba ti aṣiri Ọlọrun wà ninu àgọ́ mi. (Psm 25:14.)

5. Nigba ti Olodumare wà sibẹ pẹlu mi, nigba ti awọn ọmọ mi wà yi mi ká.

6. Nigba ti emi nfi òrí-àmọ́ wẹ iṣisẹ̀ mi, ati ti apata ntu iṣàn òróró jade wá fun mi. (Job 20:17; Deut 32:13,14.)

7. Nigba ti mo jade là aarin ilu lọ si ẹnu ibode, nigba ti mo tẹ́ itẹ́ mi ni ìgboro.

8. Nigba naa ni awọn ọdọmọkunrin ri mi, wọn si sápamọ́, awọn àgbà dide duro.

9. Awọn ọmọ-alade dakẹ ọ̀rọ̀ sisọ, wọn a si fi ọwọ́ wọn lé ẹnu. (ẹsẹ 21; Job 21:5.)

10. Awọn ọlọla dakẹ, ahọ́n wọn si lẹ̀mọ́ èrìgì ẹnu wọn. (ẹsẹ 22.)

11. Nitori pe nigba ti eti gbọ, o si surẹ fun mi, ati nigba ti oju si ri mi, o jẹri mi.

12. Nitori ti mo gba talaka ti nsọkun, ati alainibaba, ati alaini oluranlọwọ. (Job 31:16,17,21.)

13. Ìre ẹni ti o fẹrẹ ṣegbe wá si ori mi, emi si mu àyà opó kọrin fun ayọ̀. (Job 31:18,20.)

14. Emi si mu ododo wọ̀, o si bò mi lara; idajọ mi dabi aṣọ igunwa ati ade ọba. (Psm 132:9; Isa 59:17; 61:10; Ef 6:14.)

15. Mo ṣe oju fun afọju, ati ẹsẹ̀ fun amọkun.

16. Mo ṣe baba fun talaka, ati ọràn ti emi kò mọ̀, mo wadi rẹ̀ ri. (Owe 29:7.)

17. Mo si ká ehin ẹ̀rẹ̀kẹ̀ eniyan buburu, mo si já ohun ọdẹ naa kuro ni ehin rẹ̀. (Psm 3:7.)

18. Nigba naa ni mo wi pe, 'Emi o kú ninu itẹ́ mi, emi o si mu ọjọ mi pọ̀ si i bi iyanrin. (Psm 30:6.)

19. Gbongbo mi ta lọ si ibi omi, ìrì si sẹ si ara ẹ̀ka mi titi ni òru. (Job 18:16; Jer 17:8.)

20. Ogo mi gbèrú lọdọ mi, ọrun mi si padà di titun ni ọwọ mi. (Gen 49:24; Psm 18:34.)

21. Emi ni eniyan ndẹti silẹ si, wọn a si duro, wọn a si dakẹ ninu ìmọ̀ràn mi. (ẹsẹ 9.)

22. Lẹhin ọ̀rọ̀ mi wọn kò si tun sọ mọ, ọrọ mi bọ si wọn leti. (ẹsẹ 10; Job 32:2.)

23. Wọn a si duro dè mi bi ẹni pe fun òjò: wọn si yanu wọn gbòrò bi ẹni pe fun ojo ìrúwé.

24. Emi si rẹrin si wọn nigba ti wọn kò ba gba a gbọ́; imọlẹ oju mi ni wọn kọ̀ lè mu rẹ̀wẹ̀si.

25. Mo la ọna silẹ fun wọn, mo si jokòó bi Olóyè, mo si jokòó bi ọba ninu ogun, bi ẹni ti ntu aṣọ̀fọ̀ ninu. (Job 1:3; 31:37; 4:4.)

## ORI 30

**Ijiya Jobu.**

ṢUGBỌN ni isinsinyìí awọn ti mo gbà ni aburo nfi mi ṣẹ̀sín, baba awọn ẹni ti emi kẹ́gàn lati tò pẹlu awọn ajá agbo-ẹran mi. (Jọb 12:3.)

2. Ere kinni emi yoo jẹ nipa agbara ọwọ wọn, awọn ẹni ti agbara wọn ti tán?

3. Nitori aini ati ìyàn wọn ngirin jẹ ohun gbígbẹ ni ilẹ̀ ijù ti o ti di ahoro.

4. Awọn ẹni ti nja ewe-iyọ̀ lẹba ìgbẹ́, gbongbo igikigi ni ohun jijẹ wọn.

5. A lé wọn jade kuro laarin eniyan, wọn si hó lé wọn bi ẹni pe si olè.

6. Wọn nilati maa gbé inu pàlàpálá okuta afonifoji, ninu ihò ilẹ̀ ati okuta.

7. Ninu igbẹ ni wọn ndún, wọn kó ara wọn jọ pọ̀ labẹ ẹ̀gún-ọ̀gán.

8. Awọn ọmọ ẹni ti òye kò yé, ani ọmọ awọn eniyan lásán, a si lé wọn kuro lori ilẹ̀.

9. "Njẹ ni isinsinyìí emi di ẹni-orin fun wọn, ani emi di ẹni-ifiṣọ̀rọ̀sọ fun wọn. (Job 12:4; 17:6.)

10. Wọn korira mi, wọn sá kuro jinna si mi, wọn kò si kọ̀ lati tutọ si mi loju. (Num 12:14; Deut 25:9; Isa 50:6; Matt 26:67.)

11. Nitori ti Ọlọrun ti tu okùn iyè mi, o si pọ́n mi loju; awọn pẹlu si de ijanu niwaju mi. (Rut 1:21; Psm 88:7.)

12. Awọn eniyan lásán dide ni apa ọtun mi, wọn ti mi ni ẹsẹ̀ kuro, wọn si la ipa-ọna iparun silẹ dè mi. (Psm 140:4,5; Job 19:12.)

13. Wọn da ipa-ọna mi rú, wọn ran ìdààmú mi lọ́wọ́, awọn ti kò ni oluranlọwọ;

14. Wọn de si mi bi yiya omi-gburu, ni ariwo nla ni wọn nrọ́ wá.

15. Ẹ̀rù nla ni a mu bà mi, wọn lepa ọkàn mi bi ẹfúùfù, alaafia mi si kọja lọ bi ikuukuu awọsanma. (Job 3:25; 31:23; Hos 13:3.)

16. Ati ni isinsinyìí ọkan mi si dà jade si mi, ọjọ ipọnju dì mí mú. (Psm 22:14; 42:4.)

17. Òru gún mi ninu egungun mi, eyi ti o bù mi jẹ kò sì sinmi. (ẹsẹ 30.)

18. Nipa agbara nla aṣọ mi di pípadà, o sì lẹmọ mi lara yika bi ọrùn aṣọ ileke mi.

19. O ti mu mi lọ sinu ẹrẹ̀, emi si dabi ekuru ati eerú, (Psm 69:2,14.)

20. Emi ke pè ọ, iwọ kò si gbọ temi, emi dide duro, iwọ si fi oju lile wò mi. (Psm 19:7.)

21. Iwọ pada di ẹni-ikà si mi, ọwọ́ agbara rẹ ni iwọ fi de ara rẹ lọna si mi. (Job 10:3; 16:8,14; 19:6,22.)

22. Iwọ gbé mi soke si ẹfúùfù, iwọ mu mi fò lọ, bẹẹ ni iwọ si sọ mi di asán patapata. (Job 9:17; 27:21.)

23. Emi sa mọ pe iwọ o mu mi lọ sinu ikú, ati si ile-àpèjọ fun gbogbo aláàyè. (Job 9:22; 10:8; 3:19; 17:13.)

24. "Sibẹ, ẹni ti o nṣubu lọ ninu iparun kò ha ní na ọwọ́ rẹ̀ bi? Tabi kẹ́ ninu iparun rẹ̀ fun iranlọwọ bi? (Job 19:7.)

25. Emi kò ha sọkun bí fun ẹni ti o wà ninu ìṣẹ́, ọkan mi kò ha bàjẹ́ fun talaka bi? (Psm 35:13,14; Rom 12:15.)

26. Nigba ti mo fojusọna fun alaafia, ibi si dé, nigba ti emi duro de imọlẹ, òkùnkùn si de. (Job 3:25,26; Jer 8:15; Job 19:8.)

27. Ikun mi nru, ko si sinmi, ọjọ ipọnju ti ba mi.

28. Emi nrin kiri ninu òkùnkùn laisi oòrùn, emi dide duro ni awujọ, mo si kigbe. (Psm 38:6; 42:9; 43:2; Job 19:7.)

29. Emi jasi arakunrin akátá, emi di ẹgbẹ́ awọn abo-ògòngò. (Mika 1:8.)

30. Àwọ̀ mi di dúdú lara mi, egungun mi si jórun fun ooru. (Psm 119:83; E.Jer. 4:8; Psm 102:3.)

31. Duru mi pẹlu si di ti ọ̀fọ̀, atı fèrè mi si di awọn ti nsọkun. (Psm 107:1,2.)

## ORI 31.

**Ó dá ara rẹ̀ lare.**

EMI ti ba oju mi dá majẹmu, njẹ emi o ha ti ṣe tẹjumọ wundia? (Matt 5:28.)

2. Nitori pe kinni yoo ṣe ìpín mi lati ọdọ Ọlọrun wá, tabi kinni yoo ṣe ogun mi lati ọdọ Olodumare ibi giga wá? (Job 20:29.)

3. Ko ha ṣe pe iparun ni o maa nṣubu lu awọn eniyan buburu ni, ati jamba fun awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀? (Job 21:30; 34:22.)

4. Oun kò ha ri ipa-ọna mi, oun kò ha si ka gbogbo ìṣísẹ̀ mi? (2 Kro 16:9; Owe 5:21.)

5. Bi o bá ṣe pe emi ba fi aiṣotitọ rin, tabi ti ẹsẹ̀ mi sì yara si ẹ̀tàn. (Mika 2:11.)

6. (Ki a diwọn mi ninu iwọn òdodo, ki Ọlọrun lè mọ iduroṣinṣin mi!) (Job 6:2,3; 27:5,6.)

7. Bi ẹsẹ̀ mi ba yà kuro loju ọ̀nà, ti àyà mi si tẹle ifẹ oju mi, bi àbàwọ́n kan ba si lẹ̀mọ́ mi lọwọ. (Job 23:11; 9:30.)

8. Njẹ ki emi o gbin ki ẹlomiran si mu un jẹ, ani ki a fa irú-ọmọ mi tu. (Lef 26:16; Job 20:18.)

9. "Bi a ba mu àyà mi fi ẹtan fa si obinrin kan, tabi mo bá lọ ba ni bùba lẹnu-ọ̀nà ile aladugbo mi. (Job 24:15.)

10. Njẹ ki aya mi o lọ ọlọ fun ẹlomiran, ki awọn ẹlomiran tẹ ara wọn ba lori rẹ̀. (Jer 8:10.)

11. Nitori pe ẹ̀ṣẹ̀ buburu ni eyí; ani ẹ̀ṣẹ̀ ti o yẹ fun ìyà ni lọdọ awọn onidajọ. (Gen 38:24; Deut 22:22-24.)

12. Nitori pe iná ni èyí ti o njo iparun, oun yoo si jó dé gbongbo ohun ibisi mi gbogbo. (Job 15:30; 26:6; 20:28.)

13. "Bi mo ba si ṣe aika ọ̀ràn iranṣẹkunrin mi tabi iranṣẹbinrin mi si, nigba ti wọn ba nba mi jà; (Deut 24:14,15.)

14. Kinni emi o ha ṣe nigba ti Ọlọrun bá dide; nigba ti o ba si ṣe ìbẹ̀wò, kinni emi o ṣe da a lohun?

15. Ẹni ti o dá mi ni inu kọ́ ni o da oun naa? Ẹnikan naa kọ́ ni o mọ wá ni inú? (Mal 2:10.)

16. "Bi mo bá fa ọwọ́ sẹhin fun ifẹinu talaka, tabi bi mo bá sì mu oju opó kùnà? (Job 20:19; 22:7,9.)

17. Tabi ti mo ba nikan bu òkèlè mi jẹ, ti alainibaba kò jẹ ninu rẹ̀. (Job 22:7; 29:12.)

18. (Nitori pe lati ìgbà èwe mi wá ni a ti tọ́ ọ dagba pẹlu mi bi ẹni pe baba, emi sì nṣe ìtọju rẹ̀ lati inu iya mi wa.)

19. Bi emi ba ri ẹni ti nsègbé lọ nitori aini aṣọ, tabi talaka kan laini ìbora; (Job 22:6; 29:13.)

20. Bi ẹgbẹ rẹ̀ ko ba sure fun mi, tabi bi ara rẹ̀ ko ba si gbona nipasẹ irun agutan mi. (Deut 31:20.)

21. Bi mo ba si gbe ọwọ mi soke si alainibaba, nitori pe mo ri iranlọwọ ni ẹnu-bode. (Job 22:9.)

22. Nigba naa jẹ ki apa mi wọ́n kuro lóri ejika mi, ki apa mi sì ṣẹ́ lati egungun rẹ̀ wá. (Job 38:15.)

23. Nitori pe iparun lati ọdọ Ọlọrun wá ní ẹ̀rù-nla fun mi, ati nitori Ọlánlá rẹ̀ emi kò lè duro. (ẹsẹ 3; Job 13:11.)

24. Bi o ba ṣe pe mo fi wura ṣe igbẹkẹlé mi, tabi bi mo ba wi fun wura didara pe, iwọ ni igbẹkẹle mi; (Mk 10:24.)

25. Bi mo ba yọ̀ nitori ọrọ̀ mi pọ, ati nitori ọwọ mi dẹ lọpọlọpọ. (Psm 62:10.)

26. Bi mo ba bojuwo oorùn nigba ti nràn, tabi oṣupa ti nrìn ninu dídán imọlẹ̀ rẹ̀ (Deut 4:19; Esk 8:16.)

27. Ti a sì fi ọ̀nà-àṣírí tan àyà mi lọ, ti ẹnu mi sì fẹnuko ọwọ́ mi.

28. Eyi pẹlu ni ẹ̀ṣẹ̀ ti a o jẹ níyà lati ọdọ awọn onidajọ, nitori pe emi iba ti ṣèké si Ọlọrun ti o wà loke. (ẹsẹ 11.)

29. Bi o ba ṣe pe mo yọ̀ si iparun ẹni ti o korira mi, tabi bi mo ba si gbera soke, nigba ti ibi ba a. (Owe 17:5.)

30. (Bẹẹ ni emi kò si jẹ́ ki ẹnu mi o ṣẹ̀ nipa bi bèèrè ọkàn rẹ̀ pẹlu èpè) (Matt 5:44.)

31. Bi awọn eniyan inu àgọ́ mi kò bá wí pe, 'Tani o wà ti koi tìi ni anító ẹran (ounjẹ)?' (Job 22:7.)

32. (Alejo kò wọ ni igboro rí, emi si ilẹkun mi silẹ fun èrò.) (Gen 19:2,3; Rom 12:13.)

33. Bi mo ba bo irekọja mi mọlẹ, bi Adamu, ni pipa ẹbi mi mọ́ ni aya mi, (Gen 3:8; Owe 28:13.)

34. Nitori pe ọpọlọpọ eniyan ni mo bẹru, ẹ̀gàn awọn idile ni nba mi lẹru, ti mo fi pa ẹnu mọ́, ti emi kò si fi jade sode. (Esk 23:2.)

35. Ibaṣe pe ẹnikan le gbọ́ temi! Kiyesi i, ami mi! Ki Olodumare o da mi lohun! Ki emi si ri iwe ẹ̀sùn naa ti ọta mi ti kọ! (Job 19:7; 30:20,24, 28; 35:14.)

36. Nitootọ emi iba gbe e le ejika mi, emi iba si dì í bi ade mọ́ ori mi.

37. Emi iba si sọ iye ìṣísẹ̀ mi fun un bi ọmọ-alade ni emi iba sunmọ ọdọ rẹ̀. (ẹsẹ 4; Job 1:3; 29:25.)

38. Bi ilẹ̀ mi ba si ké lati fi mi sùn, tabi ti aporo rẹ̀ pẹlu si sọkun; (Gen 4:10,11.)

39. Bi mo ba jẹ eso oko mi laináwó si i, tabi ti mo si ṣe iku pa ẹni ti o ni in: (Lef 19:13; 1 A.Ọba 21:19; Jak 5:4.)

40. Ki ẹ̀gún òṣùṣù o hù dípò alikama, ati wèrèpè dípó ọkà-bàbà. (Ọrọ Jobu pari.) (Gen 3:18.)

## ORI 32.

**Elihu binu si Jobu nitori pe o da ara rẹ̀ lare.**

BẸẸ ni awọn ọkunrin mẹtẹta wọnyìí dakẹ lati dá Jobu lohun, nitori o ṣe olododo loju ara rẹ̀. (Job 33:9.)

2. Nigba naa ni inu bi Elihu, ọmọ Barakeli, ara Busi, lati ìbátan idile Ramu; o binu si Jobu, nitori ti o da ara rẹ̀ lare, kàkà ki o da Ọlọrun lare. (Gen 22:21; Jer 25:23.)

3. Inu si bi i si awọn ọrẹ Jobu mẹtẹta, nitori ti wọn kò ni idahun, bi o tilẹ jẹ pe wọn da jobu lẹ́bi. (Job 11:6; 15:16; 22:5.)

4. Njẹ Elihu ti duro titi Jobu fi sọrọ tán, nitori ti awọn wọnyìí dagba ju oun lọ ni iye ọjọ́.

5. Nigba ti Elihu ri pe idahun ọ̀rọ̀ kò si lẹnu awọn ọkunrin mẹtẹta wọnyìí, nígba naa ni o binu.

6. Elihu, ọmọ Barakeli, ara Busi, dahun o si wi pe, "Ọmọde ni emi, agba si ni ẹyin; njẹ nitori naa ni mo duro, mo si nbẹ̀rù lati fi ìmọ̀ mi hàn yín. (Job 15:10.)

7. Emi wi pe, 'Ọjọ́-jọjọ ni iba sọ̀rọ̀, ati ọpọlọpọ ọdún ni iba maa kọni ni ọgbọ́n.'

8. Ṣugbọn ẹmi kan ni o wà ninu eniyan, ati imisi Olodumare ni o si maa nfun wọn loye. (Job 27:3; 33;4; 1 A.Ọba 3:12; Owe 2:6.)

9. Eniyan nlanla ki i ṣe ọlọgbọn, bẹẹ ni awọn agba ni òye idajọ kò yé. (1 Kor 1:26.)

10. Nitori naa ni emi ṣe wi pe, 'Ẹ dẹti silẹ si mi, emi pẹlu yoo fi ìmọ̀ mi hàn.'

11. "Kiyesi i, emi ti duro de ọ̀rọ̀ yin, emi feti si àròyé yin, nigba ti ẹyin nwa ọ̀rọ̀ ti ẹ̀yin o sọ.

12. Ani mo fiyesi yin timutinu, si kiyesi i, kò si ẹnikan ninu yin ti o lẹ já Jobu níkoro, tabi ti o le dá a lohun ọ̀rọ̀ rẹ̀!

13. Ki ẹyin má baa wi pe, 'Awa wá ọgbọ́n lawari: Ọlọrun ni o le bi i ṣubu, kì í ṣe eniyan.' (Jer 9:23.)

14. Bi oun kò ti sọrọ si mi, bẹẹ ni emi ki yoo fi ọ̀rọ̀ yin da a lohun.

15. "Ẹnu si ya wọn, wọn kò si dahun mọ́, wọn kò si sọrọ mọ́.

16. Emi o ha duro, nitori ti wọn kò si fọhun, wọn dakẹ jẹ́, wọn kò si dahun mọ́?

17. Bẹẹ ni emi o si dahun nipa temi, emi pẹlu yoo si fi ìmọ̀ mi hàn.

18. Nitori pe emi kun fun ọ̀rọ̀, ẹ̀mí ti nbẹ ninu mi nrọ̀ mi. (A.A. 18:5.)

19. Kiyesi i, ikun mi dabi ọti-waini, ti kò ní oju-iho; o mura tan lati bẹ́ bi igo-awọ titun. (A.A. 9:17.)

20. Emi o sọ, ki ara lè rọ̀ mi, emi o ṣi ètè mi, emi o si dahun.

21. Lotitọ emi ki yoo ṣe ojusaju eniyan, bẹẹ ni emi ki yoo si ṣe ipọ́nni fun ẹnikan. (Lef 19:15; Matt 22:16.)

22. Nitori pe emi kò mọ̀ bi a ti npọnni, ni ṣiṣe bẹẹ Ẹlẹda mi yoo mu mi kuro lọ́gán. (1 Tess 2:5.)

## ORI 33.

**Ọlọrun maa nlo irora lati na eniyan.**

NJẸ nitori naa, Jobu, emi bẹ ọ, gbọ ọ̀rọ̀ mi, ki o si feti si ọ̀rọ̀ mi!

2. Kiyesi i nisinsinyìí, emi yà ẹnu mi, ahọ́n mi si sọ̀rọ̀ ni ẹnu mi.

3. Ọ̀rọ̀ mi yoo si fi iduroṣinṣin ọkàn mi hàn, ètè mi yoo si sọ ìmọ̀ mi jade dajudaju. (Job. 6:28; 27:4; 36:4.)

4. Ẹmí Ọlọrun ni o ti dá mi, ati imisi Olodumare ni o ti fun mi ni ìyè. (Gen 2:7; Job 27:3.)

5. Bi iwọ bá le dá mi lohun, to ọ̀rọ̀ rẹ

lẹsẹẹsẹ niwaju mi, ki o si mu iduro rẹ.(ẹsẹ 32; Job 13:18.)

6. Kiyesi i, bi iwọ jẹ ti Ọlọrun, bẹẹ ni emi naa; lati erupẹ wa ni a si ti da mi pẹlu.

7. Kiyesi i, ẹ̀rù mi ki yoo ba ọ, bẹẹ ni ọwọ́ mi ki yoo wuwo si ọ lara. (Job 9:34; 13:21; 2 Kor 2:5.)

8. Nitootọ iwọ sọ leti mi, emi si gbọ ọ̀rọ̀ rẹ wi pe,

9. 'Emi mọ́, laini irekọja, alaiṣẹ ni emi, bẹẹ ni aiṣedéédé kò sí lọwọ mi. (Job 13:23; 10:7; 16:17.)

10. Kiyesi i, ẹ̀fẹ̀ ni o nfẹ̀ si mi, o kà mi si ọta Rẹ. (Job 13:27; 14:16.)

11. O kan ẹsẹ̀ mi sinu àbà, o kiyesi ipa-irin mi gbogbo. (Job 13:27; 14:16.)

12. "Kiyesi i, ninu eyi iwọ ṣina! emi o da ọ lohun pe: Ọlọrun tobi ju eniyan lọ!

13. Nitori kinni iwọ ṣe nba a sọ pe: 'Oun ki yoo ṣe iṣiro kan nitori iṣẹ rẹ? (Job 15:25; Isa 45:9.)

14. Nitori pe Ọlọrun sọrọ lẹ́ẹ̀kan, ani lẹẹkejì ṣugbọn eniyan kò roye rẹ̀. (Psm 62:11.)

15. Ninu àlá, ni ojuran òru, nigba ti oorun ìjìkà bá kun eniyan lọ, ni itoogbe lori ibùsùn. (Num 12:6; Job 4:13.)

16. Nigba naa ni o nṣi eti eniyan, a si fi èdìdí di ẹkọ wọn (nipa fifi ikilọ dẹruba wọn) (Job 36:10,15.)

17. Ki o le fa eniyan sẹhin kuro ninu ète rẹ̀, ki o si pa igberaga mọ́ kuro lọdọ eniyan.

18. O si fa ọkàn rẹ̀ pada kuro ninu ihò, ati ẹmi rẹ̀ lati ṣegbe lọwọ idà. (ẹsẹ 24,28,30.)

19. "A fi irora nà án lori ibùsùn rẹ̀, ati ìjà igbagbogbo ninu egun-gun rẹ̀. (Job 30:17.)

20. Ki ẹmi rẹ̀ ba lè kọ ounjẹ, ati ki ọkan rẹ̀ si lè kọ ounjẹ didun. (Psm 107:18.)

21. Ẹran ara rẹ̀ si ṣègbé, titi a kò sì fi lè ri i mọ́; egungun rẹ̀ ti a kò ti ri, si ta jade. (Job 16:8; 19:20.)

22. Ani ọkàn rẹ̀ sunmọ ọ̀gbun, ati ẹmi rẹ̀ sunmọ ọdọ awọn iranṣẹ iku. (Psm 88:3.)

23. Bi oniṣẹ kan ba wà lọdọ rẹ̀, ẹni ti nṣe alagbawi, ọ̀kan ninu ẹgbẹrun lati fi ọna pipe han ni: (Mika 6:8.)

24. Nigba naa ni yoo fun un ni oore-ọ̀fẹ́, ti o si wi pe, 'Gba a kuro ninu lilọ sinu ihò, emi ti ri irapada! (Isa 38:17.)

25. Ara rẹ̀ yoo tutù yọ̀yọ̀ ju ti ọmọ kekere, yoo si tun pada si ọjọ́ ìgbà èwe rẹ̀. (2 A.Ọba 5:14.)

26. O gbadura sọdọ Ọlọrun, oun yoo si ṣe oju rere si i, o si mu eniyan ri oju rẹ̀ pẹlu ayọ̀, oun yoo san ododo rẹ̀ pada fun eniyan. (Job 22:27; 34:28; 22:26; Psm 51:12.)

27. Oun yoo kọrin fun eniyan, yoo si wi pe, 'Emi ṣẹ̀, mo si ti yi eyi ti o tọ́ po, a kò si ṣẹsan rẹ̀ fun mi; (Luk 15:21; Rom 6:21.)

28. O ti gba ọkan mi kuro ninu lilọ sinu ihò, ẹmí mi yoo si ri imọlẹ!' (Psm 103:14; Job 22:28.)

29. Wo o! nkan wọnyìí ni Ọlọrun maa nṣe fun eniyan nigba meji, ati nigba mẹta, (Ef 1:11; Kor 12:6; Filp 2:13.)

30. Lati mu ọkan rẹ̀ pada kuro ninu ihò, ki a baa lè tan ìmọ́lẹ̀ ìyè si i. (Psm 56:13.)

31. Jobu! kiyesi i gidigidi, ki o si feti-silẹ si mi; pa ẹnu rẹ mọ́, emi o si maa sọ!

32. Bi iwọ ba si ni ohun kan lati wi, da mi lohun, ki o si wi nitori pe emi nfẹ lati le da ọ lare.

33. Bi bẹẹ bá kọ, gbọ temi; sì dakẹ jẹ; emi o si kọ ọ ni ọgbọn. (Psm 34:11.)

ORI 34.

**Ọlọrun ki i ṣe alaiṣooto.**

NIGBA naa ni Elihu dahun o si wi pe.

2. "Ẹyin ọlọgbọn, ẹ gbọ ọ̀rọ̀ mi, ki ẹ si dẹtisilẹ si mi, ẹyin ti ẹ ni imoye.

3. Nitori pe eti a maa dán ọ̀rọ̀ wò, bi ẹnu ti maa ntọ ounjẹ wò. (Job 12:11.)

4. Ẹ jẹ ki a yàn fun ara wa; ohun ti o tọ́, ẹ jẹ ki a mọ ohun ti o dara laarin wa. (1 Tess 5:21.)

5. Nitori pé Jobu wi pe, 'Olododo ni emi; Ọlọrun si ti gbà ẹ̀tọ́ mi lọ. (Job 33:9; 27:2.)

6. Emi ha lè purọ si ẹ̀tọ́ mi bí? Ọgbẹ́ mi kò ni àwòsan, bi o ti lẹ jẹ pe emi kò ni ẹṣẹ.' (Jer 15:18; 30:12.)

7. Ọkunrin wo ni o dabi Jobu, ti nmu ẹ̀gàn bi ẹni mu omi. (Job 15:16.)

8. Ti nba awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ kẹ́gbẹ́, ti o si nba awọn eniyan buburu rìn. (Psm 50:18.)

9. Nitori o saa ti wi pe, 'Èrè kan kò si fun eniyan, ti yoo fi maa ṣe inu didun si Ọlọrun,' (Job 21:15; 35:3.)

10. Njẹ nitori naa ẹ feti-silẹ si mi, ẹ̀yin eniyan amòye: o di èèwọ̀ fun Ọlọrun ti iba fi huwa buburu, ati fun Olodumare, ti iba fi ṣe aiṣedéedé (Job 8:3.)

11. Nitori pe ẹsan iṣẹ eniyan ni yoo san fun un, yoo si mu olukuluku ri gẹgẹ bi ipa-ọna rẹ̀. (Psm 62:12; Matt 16:27; Rom 2:6; 2 Kor 5:10; Ifh 22:12.)

12. Nitooto Ọlọrun ki yoo huwakiwa, bẹẹ ni Olodumare ki yoo yi idajọ po, (Job 8:3.)

13. Tani o fi itọju ayé le e lọwọ, tabi tani o to gbogbo ayé lẹsẹẹsẹ? (Job 38:5,6.)

14. Bi o bá gbé àyà rẹ̀ le kìkì ara rẹ̀, ti o si gba ọkàn rẹ̀ ati ẹ̀mí rẹ̀ sọdọ ara rẹ̀, (Psm 104:29.)

15. Gbogbo eniyan ni yoo parun pọ, eniyan a si tun pada di erùpẹ̀. (Isa 40:6,7; Gen 3:19.)

16, Njẹ nisinsinyìí, bi iwọ ba ni oye, gbọ eyi, fetisi ohùn ẹnu mi.

17. Ẹni ti o korira otitọ lè ṣe olori bi? Iwọ yoo ha si da olootọ ati alagbara lẹbi? (2 Sam 23:3.)

18. O ha tọ́ lati wi fun ọba pé, 'Eniyan buburu ni ìwọ, tabi fun awọn ọmọ-alade pé, Alaijámọ́ nkan ni ẹyin? (Eks 22:28.)

19. Ambọtori fun ẹni ti kìí ṣe ojusaju awọn ọmọ-alade, tabi ti kò ka ọlọ́rọ̀ si ju talaka lọ, nitori pé iṣẹ́ ọwọ rẹ̀ ni gbogbo wọn jẹ́. (Deut 10:17; Gal 2:6; Job 31:15.)

20. Ni iṣẹju kan ni wọn o kú, awọn eniyan a si di yíyọ lẹnu laarin ọ̀gànjọ́, wọn a si kọja lọ; a si mu awọn alagbara kuro laláìsí ọwọ́ eniyan nibẹ. (Eks 12:29; Job 12:19.)

21. Nitori pe oju rẹ̀ nbẹ ni ipa-ọna eniyan, oun si ri irin rẹ̀ gbogbo. (Job 31:4.)

22. Ko si òkùnkùn, tabi ojiji ikú, nibi ti awọn oniṣẹ́-ẹṣẹ̀ yoo gbe sa pamọ́ si. (Psm 139:12; Amos 9:2,3.)

23. Nitori pe oun kò fi akoko silẹ fun ẹnikan, ni igba ti oun yoo lọ siwaju Ọlọrun fun idajọ.

24. Ó fọ́ awọn alagbara tútú laini-iwadi, a si fi ẹlomiran dipo wọn. (Dan 2:21.)

25. Nitori pe o mọ iṣẹ́ wọn, o si yí wọn po ni oru, bẹẹ ni wọn di fífún pa. (ẹsẹ 11,20.)

26. O kọlu wọn bi eniyan buburu, nibi ti awọn ẹlomiran ti ri wọn. (Job 26:12.)

27. Nitori ti wọn pẹ̀hìndà si i, wọn kò si fiyesi ipa-ọna rẹ̀ gbogbo. (1 Sam 15:11; Psm 28:5; Isa 5:12.)

28. Nitori pe wọn mu ki igbe ẹkún awọn talaka lọ dé ọdọ rẹ̀, oun si gbọ́ igbe ẹkún olupọnju. (Job 35:9; Jak 5:4; Eks 22:23.)

29. Nigba ti o ba fun un ni ìfàyàbalẹ̀–ọkàn, tani yoo da a lẹbi, nigba ti o ba pa oju rẹ̀ mọ́, tani yoo le ri i? Bẹẹ ni o ṣe e si orilẹ-èdè tabi ṣi eniyan kanṣoṣo. (1 Kro 22:9.)

30. Ki àgàbàgebè ma baa jọba, ki wọn má baa di idẹwò fun eniyan. (ẹsẹ 17.)

31. Nitori pe ẹnikan ha le wi fun Ọlọrun pe, emi jiya laiṣẹ?

32. Eyi ti emi kò rí, iwọ fi kọ mi, bi mo ba si dẹ́ṣẹ̀, emi ki yoo ṣe bẹẹ mọ́. (Job 35:11; Psm 25:4.)

33. Oun o ha san ẹsan ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ gẹgẹ bi iwọ ti nfẹ bi, nitori ti iwọ kò gba? Ni-

tori pe iwọ ni o ni lati yàn, ki i ṣe emi, Nitori naa sọ otitọ́ inu rẹ jade?

34. Awọn eniyan amòye yoo wi fun mi, ati pẹlupẹlu ẹnikẹni ti nṣe ọlọgbọn ti o si gbọ mi, yoo si sọ.

35. Jobu ti fi àìmọ̀ sọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ rẹ̀ si ṣe alaigbọ́n. (Job 35:16.)

36. Ifẹ mi ni ki a dán Jobu wò de opin, nitori idahun rẹ̀ nipa ọ̀nà eniyan buburu. (Job 23:10; 22:15.)

37. Nitori pé o fi ìṣọ̀tẹ̀ kún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, o pa àtẹ́wọ́ ni àwùjọ wa, o si sọ ọ̀rọ̀ di pupọ si Ọlọrun."

## ORI 35.

ELIHU sọ pẹlu o si wi pe,

2. "Iwọ rò pe eyi ha tọ́, ti iwọ wi pe, òdodo mi ni eyi niwaju Ọlọrun." (Job 32:2.)

3. Ti o si fi bèèrè pe, 'Ere kinni yoo já sí fun mi? Èrè kinni emi o fi jẹ ju bi mo ba ṣẹ̀ lọ?' (Job 34:9; 9:30,31.)

4. Emi o da ọ lohun ati awọn ẹgbẹ rẹ pẹlu rẹ.

5. Ṣiju wo ọ̀run, ki o ri i, si bojuwo ikuukuu awọsanma ti o ga ju ọ lọ. (Job 22:12.)

6. Bi iwọ ba ṣẹ̀ kinni iwọ fi ṣẹ̀ si i? Tabi bi irekọja rẹ ba di pupọ, kinni iwọ fi eyi ṣe si i? (Owe 8:36; Jer 7:19.)

7. Bi iwọ ba si ṣe olododo, kinni iwọ fi fun un, tabi kinni oun ri gbà lati ọwọ́ rẹ wá? (Job 22:2,3; Owe 9:12; Luk 17:10.)

8. Ìwà buburu rẹ, eniyan bi tirẹ lo kàn; ati ododo rẹ fun ọmọ eniyan.

9. Nipa ọpọlọpọ ininilara, awọn eniyan kigbe, wọn kigbe nitori apá awọn alagbara. (Eks 2:23; Job 12:19.)

10. Ṣugbọn kò si ẹni ti o wi pe, 'Nibo ni Ọlọrun Ẹlẹda mi wà, ti o fi orin fun mi ni òru? (Job 27:10; Psm 42:8; 149:5; A.A. 16:25.)

11. Ti o nkọ́ wa lẹ́kọ̀ ju awọn ẹranko ayé lọ, ti o si mú wa gbọ́n ju awọn ẹyẹ oju ọrun lọ? ( Psm 94:12; Luk 12:24.)

12. Nigba naa ni wọn ke, ṣugbọn Ọlọrun kò dahun nitori igberaga awọn eniyan buburu, (Owe 1:28.)

13. Nitootọ Ọlọrun ki yoo gbọ igbe asán, bẹẹ ni Olodumare ki i ka a si. (Job 27:9; Owe 15:29; Isa 1:15; Jer 11:11.)

14. Bi o tilẹ ṣe pe iwọ wi pe, 'Iwọ ki i ri i, ọ̀ràn idajọ nbẹ niwaju rẹ̀, ti iwọ si nduro de E. ( Psm 27:5,6.)

15. Ṣugbọn ni isinsinyìí nitori ti ibinu rẹ̀ ko ti ṣẹ́ ọ níṣẹ̀ẹ́, oun kò ha le mọ ọpọlọpọ ẹ̀ṣẹ̀ bi? (Onws 8:11.)

16. Nitori naa ni Jobu ṣe ya ẹnu rẹ̀ lasán, o sọ ọ̀rọ̀ di pupọ laisi imọ̀. (Job 34:37,35.)

## ORI 36.

**Idajọ Ọlọrun, ọna ẹni ti i ṣe àwámárídì.**

ELIHU si tẹ siwaju wi pe,

2. "Bun mi laye diẹ, emi o si fi hàn ọ, nitori ti mo ni ọ̀rọ̀ lati sọ gbe Ọlọrun.

3. Emi o mu imọ mi ti ọna jinjin wá, emi o si fi ododo fun Ẹlẹda mi. (Job 8:3; 37:23.)

4. Nitori pe ọ̀rọ̀ mi ki yoo ṣèké nitootọ́, ẹni ti o pé ni imọ wà pẹlu rẹ. (Job 33:3; 37:16.)

5. Kiyesi i, Ọlọrun ni agbara, kò si gan ẹnikẹni, o ni agbara ni ipa ati òye. ( Psm 22:24; Job 12:13.)

6. Oun ki i da ẹmi eniyan buburu sí, ṣugbọn o fi òtítọ́ fun awọn talaka. (Job 8:22; 5:15.)

7. Oun ki i mu oju rẹ̀ kuro lara olódodo, ṣugbọn pẹlu awọn ọba ni wọn wà lori itẹ́; ani o fi idi wọn mulẹ laelae, a si gbe wọn leke. (Psm 33:18; 113:8.)

8. Bi a ba si dè wọ́n ninu ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀, ti a si fi okùn ipọnju dè wọ́n, (Psm 107:10; ẹsẹ 15:21.)

9. Nigba naa ni o nfi iṣẹ wọn han fun wọn, ati irekọja wọn, wi pe wọn ti gbe ara wọn ga. (Job 15:25.)

10. A ṣi wọn leti pẹlu si ọna ẹ̀kọ́, a si

pàṣẹ ki wọn o pada kuro ninu aiṣedee-de. (Job 33:16; 2 A.Ọba 17:13.)
11. Bi wọn ba gbọ́, ti wọn si sin in, wọn o lo ọjọ wọn ninu aasìkí, ati ọdun wọn ninu afẹ́. (Isa 1:19,20.)
12. Ṣugbọn bi wọn kò bá gbọ́, wọn o ti ọwọ idà ṣègbé, wọn a si ku laini òye. (Job 15:22; 4:21.)
13. Ṣugbọn awọn àgàbàgebè ni àyà kó ibinu jọ; wọn kò kigbe fun iranlọwọ nigba ti o bá dè wọn. (Rom 2:5.)
14. Nigba naa ni ọkan wọn yoo ku léwe, ẹmi wọn a si ṣègbé laarin awọn alaimọ́. (Job 15:32; 22:16.)
15. Oun ngba òtòṣi ninu ipọnju rẹ̀, a si ṣi wọn leti ninu inilara. (Psm 119:67; ẹsẹ 10.)
16. Bẹẹ ni a si fa ọ lọ kuro ninu ìṣẹ́ si ibi ti o gbòrò, ti ko si ìhágágá; ati ohun ti a si gbe kalẹ ni tabili rẹ̀ a jẹ kiki ọ̀rá. (Hos 2:14; Psm 118:5–9; 23:5.)
17. "Ṣugbọn iwọ kun fun idajọ awọn eniyan buburu; idajọ ati otitọ di ọ mu.
18. Ṣọra ki ibinu má baa tan ọ lọ sinu ijiya; ma si ṣe jẹ ki titobi irapada mu ọ ṣinà. (Job 34:33; Jona 4:4,9; Job 33:24.)
19. Njẹ igbe rẹ ha le pọ̀ tó eyi ti yoo mu ipọnjú rẹ kuro bi, tabi ipá agbara rẹ?
20. Ma ṣe ṣàfẹ́rí òru, nigba ti a nge awọn orilẹ-ede kuro ni ipò wọn. (Job 34:20,25.)
21. Maa ṣọ́ra ki o ma ṣe yi pada si aiṣedéedé, nitori èyí ni iwọ ti ṣàyàn ju ìfarada ni ọjọ ìpọnju lọ. (Psm 66:18; Heb 11:25.)
22. Kiyesi i, Ọlọrun a gbeni ga nipa agbara rẹ̀, tani olukọni bi oun? (Isa 40:13; 1 Kor 2:16.)
23. Tani o la ọna-iṣẹ rẹ̀ silẹ fun un, tabi tani o lè wi pe, 'Iwọ ti ṣe aiṣedee-de. (Job 34:13; Job 8:3.)
24. Ranti ki o gbe iṣẹ rẹ̀ ga, ti eniyan ti fi kọrin. (2 Sam 7:26; Psm 35:27; 59:16.)
25. Olukuluku eniyan ni o nwo o, eniyan a maa wo o ni òkèrè.
26. Kiyesi i, Ọlọrun tobi, àwa kò si mọ̀ bi o ti tobi tó! bẹẹ ni a kò lè wadi iye ọdun rẹ̀ rí. (Psm 102:24.)
27. Nitori pe oun ni o fa kíkán omi òjò silẹ, o nkán bi òjò lati inu ikuukuu rẹ̀. (Psm 147:8.)
28. Ti ikuukuu awọsanma nrọ̀ sílẹ̀, ti o si nkán lọ́pọ̀lọpọ̀ sí ori eniyan.
29. Njẹ ẹnikẹni lè mọ ìtànká ikuukuu awọsanma, tabi ariwo àgọ́ rẹ̀? (Job 37:11,16; 26:14.)
30. Kiyesi i, o tan imọlẹ yi ara rẹ̀ ká, o si fi ìsàlẹ̀ omi okun bo ara rẹ mọ́lẹ̀.
31. Nitori pe nipa wọn ni o nṣe idajọ eniyan, o fun ni ní ounjẹ lọpọlọpọ. (Job 37:13; Psm 136:25.)
32. O fi mànàmáná bo ọwọ rẹ̀ meje-ji, o si ran an si ohun-àmì. (Job 37;15.)
33. Ariwo àrá rẹ̀ nfi i hàn, ọ̀wọ́-ẹran pẹlu ni a wí fun nipa ìjì rẹ̀ ti o nbọ̀!" (Job 37:2.)

ORÍ 37.

SI eyi pẹlu ni àyà fò mi, ti o si ṣi kuro ni ipò rẹ̀.
2. Feti silẹ, ki ẹ si gbọ iro ohun rẹ̀, ati iro ti o ti ẹnu rẹ̀ jade wá. (Job 36:33.)
3. O ṣe ilana rẹ̀ nisalẹ abẹ́ ọrun gbogbo, mànàmáná rẹ̀ si de opin ilẹ ayé. (ẹsẹ 12.)
4. Lẹhin mànàmáná ohùn kan ké ramúramù, o fi ohùn ọlanla rẹ̀ sán àárá: oun ki yoo si dá àárá duro nigba ti a ba ngbọ ohùn rẹ̀. (Psm 29:3.)
5. Ọlọrun fi ohun rẹ̀ sán àará iya-nilẹnu, ohun nlánlà ni o nṣe ti awa kò lè mọ̀. (Job 5:9; 36:26.)
6. Nitori ti o wi fun òjò-didi pe, 'Iwọ rọ̀ silẹ ayé,' ati pẹlu fun ọ̀wọ́-òjò, ati fun apàrajò, 'Mu agbara le'. (Job 38:22; 36:27.)
7. O fi edídí dí ọwọ gbogbo eniyan, ki gbogbo wọn lè mọ̀ iṣẹ rẹ̀. (Job 12:14.)
8. Nigba naa ni awọn ẹranko wọnú iho lọ, wọn si wà ni ibuba wọn. (Psm 104:22.)

9. Lati iha gusu ni iji ajayika ti jade wá, ati otútù lati inu afẹ́fẹ́ ti ntuka. (Job 9:9; Psm 147:17.)

10. Nipa ẹmi Ọlọrun a fi ìdì-omi funni, ibu-omi a si dìpọ̀ kiakia. (Job 38:29; Psm 147:17.)

11. O fi omi pupọ mu ikuukuu awọsanma wúwo, a si fi mànàmáná imọlẹ rẹ̀ tu ikuukuu awọsanma ká. (Job 36:27,29; ẹsẹ 15.)

12. Awọn wọnyìí nyi kakiri nipa ilana rẹ, ki wọn lè ṣe ohunkohun ti o pa laṣẹ fun wọn lori ilẹ ayé. (Psm 148:8; Isa 14:21; 27:6; Owe 8:31.)

13. O mu un wa, ibaa ṣe fun ibawi ni, tabi fun rere ilẹ̀ rẹ̀, tabi fun àánú. (Eks 9:18; 1 Sam 12:18; Job 38:26; 1 A.Ọba 18:45.)

14. Jobu dẹti silẹ si eyi, duro jẹ, ki o si ro iṣẹ iyanu Ọlọrun. (Psm 11:2.)

15. Iwọ mọ àkókò igba ti Ọlọrun sọ wọn lọ́jọ̀, ti o si mu imọlẹ ikuukuu awọsanma rẹ̀ mọlẹ.

16. Iwọ mọ bi a ti gbe ikuukuu awọsanma duro jẹ́, iṣẹ iyanu ẹni ti o pe ni ìmọ̀. (ẹsẹ 5,14,23; Job 36:4.)

17. Iwọ ẹni ti aṣọ rẹ̀ ngbona, nigba ti ayé ba dakẹ nitori atẹgun iha-gusù.

18. Iwọ ha ba a tẹ́ pẹpẹ oju-ọ̀run, ti o duro ṣinṣin, ti o si dabi digi ti a yọ́? (Job 9:8; Psm 104:2; Isa 44:24.)

19. Kọ́ wa ni èyí ti a lè wi fun un; nitori pé awa kò le làdí ọ̀rọ̀ nitori òkùnkùn.

20. A o ha wi fun un pe, Emi fẹ sọ̀rọ̀? Tabi bi ẹnikan ba sọ̀rọ̀ a o ha gbe e mì bí?

21. Pàápàá, ẹnikan kò lè wo ìmọ́lẹ̀ nigba ti o bá tan ìtanṣán rẹ̀ ni awọsánmà, nigba ti afẹ́fẹ́ bá fẹ́ ti ó si gbá ikuukuu kúrò.

22. Ìmọ́lẹ̀ dídán bi i wúrà ti inu ìhà aríwá jádé; lọdọ Ọlọrun ni ọlánlá ẹ̀rùnlá wà;

23. Nipa ti Olódùmarè, awa kò le wadi rẹ̀ rí, o rekọja ni ipá, oun ki i ba idajọ ati ọpọlọpọ otitọ jẹ́.

24. Nitori naa eniyan a maa bẹru rẹ̀, oun kii ṣe ojusaju ẹnikẹni ti o gbọn ni inú." (Matt 10:28; 11:25; 1 Kor 1:26.)

## ORI 38.

**Ọlọrun pe Jobu nìjà.**

NIGBA naa ni OLUWA dá Jobu lohun lati inu ìjì-àjàyíká wa o si wi pe, (Job 40:6.)

2. "Tani eyi ti nfi ọrọ aini ìmọ̀ ṣú ìmọ̀ràn lóju. (Job 42:3; 35:16; 1 Tim 1:7.)

3. Di ẹ̀gbẹ́ ara rẹ ni amure bi ọkunrin ni isinsinyìí, nitori pe emi o bèèrè lọwọ rẹ ki o si da mi lohun. (Job 40:7.)

**Iṣẹda Ohun gbogbo ti Ọlọrun ṣe.**

4. "Nibo ni iwọ wà nigba ti mo fi ipilẹ ayé sọlẹ? Wi bi iwọ bá moye! (Psm 104:5; Owe 8:29.)

5. Tani o fi iwọn rẹ̀ lélẹ̀, bi iwọ ba mọ̀, tabi tani o ta okun wíwọ̀n sori rẹ̀.

6. Lori ibo ni a gbe kan ipilẹ rẹ̀ mọ́, tabi tani o fi okuta igun rẹ̀ lélẹ̀? (Job 26:7.)

7. Nigba ti awọn irawọ owurọ jumọ kọrin pọ̀, ti gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun nhó ìhó ayọ̀? (Job 1:6.)

8. "Tabi tani o fi ilẹkun sé omi òkun mọ́, nigba ti ó ya jade bi ẹni pe o ti inu tú jade wá? (Gen 1:9.)

9. Nigba ti mo fi ikuukuu awọsanma ṣe aṣọ rẹ̀, ati òkùnkùn ṣiṣu ṣe ọ̀já ìgbànú rẹ̀? (Owe 30:4.)

10. Ti mo si paṣẹ ààlà fun un, ti mo si ṣe bèbè ati ilẹkun. (Job 26:10.)

11. Ti mo si wi pe, "Nihinyìí ni iwọ o de, ki o ma si rekọja, nihinyìí si ni igberaga riru omi rẹ yoo gbe dúró mọ. (Psm 89:9.)

12. Iwọ ha paṣẹ fun owurọ lati igba ọjọ rẹ̀ wa bi, kí iwọ si mu ila-oorun mọ ipo rẹ̀? (Psm 74:16.)

13. Ki o baa lè di opin ilẹ ayé mú, ki a baa lè gbọn awọn eniyan buburu kuro ninu rẹ̀. (Psm 104:35.)

14. O si yipada bi amọ̀ ti a tẹ èdìdí sí, gbogbo rẹ̀ si fi ara hàn bi ẹni pe ninu aṣọ ìgúnwà.

15. A si fa imọlẹ wọn sẹhìn kuro lọdọ eniyan buburu, apá giga wọn ni a si ṣẹ́. (Job 18:5; Psm 10:15.)

**Eniyan kò le ṣe awari ohun ijinlẹ iṣẹda Ọlọrun.**

16. Iwọ ha wọ inu isun okun lọ ri bi tabi rìn lori isàlẹ̀-ilẹ̀ ibú nla? (Psm 77:19.)

17. A ha ṣi ilẹkun ikú silẹ fun ọ ri bí, tabi o ti ri ilẹkun ojiji ikú? (Psm 9:13.)

18. Iwọ ha moye gbígbòòrò ayé bi? Sọ bi iwọ ba mọ gbogbo rẹ̀? (Job 28:24.)

19. "Ọ̀nà wo ni o lọ si ibugbe imọlẹ, bi o ṣe ti òkùnkùn ni, nibo ni ipo rẹ̀?

20. Ti iwọ o fi mu un lọ si ibi àlà rẹ̀, ti iwọ o si mọ ipa-ọ̀nà lati lọ si ile rẹ̀? (Job 26:10; 24:13.)

21. Iwọ mọ eyi, nitori ni igba naa ni a bi ọ, iye ọjọ rẹ si pọ! (Job 15:7.)

22. Iwọ ha wọ inu iṣura idì-òjò lọ ri bí, iwọ ha ti ri ile iṣura yìnyín ri bi? (Job 37:6.)

23. Ti mo ti fi pamọ de igba ìyọnu, de ọjọ ogun ati ijà? (Eks 9:18; Jos 10:11; Isa 30:30; Esk 13:11,13; Ifh 16:21.)

24. Ọ̀nà wo ni imọlẹ fi npinra rẹ ká, tabi ti afẹ́fẹ́ ìlà-oorun ntàn ká kiri lori ilẹ ayé. (Job 26:10; 27:21.)

25. Tani o la ipadò fun ẹkún ìṣàn omi, ati ọ̀nà fun mànàmáná-àará? (Job 28:26.)

26. Lati mu un rọ̀jò sori ilẹ, nibi ti eniyan kò si, ni aginju nibi ti eniyan kò si. (Job 36:27; Psm 107:35.)

27. Lati mu ijù tutù, ati ilẹ alairo, ati lati mu ewekọ rú jade? (Psm 104:13,14.)

28. Òjò ha ni baba bi, tabi tani o bi kíkán-silẹ̀ ìirì. (Psm 147:8; Jer 14:22.)

29. Lati inu tani idì-omi ti jade wá, tani o si bi ìdìpọ̀-ìrì ti ọrun? (Psm 147:16,17.)

30. Omi di lile koko bi ẹni pe okuta, oju ibú nla si dìpọ̀.

31. Iwọ le fi ọja de awọn irawọ meje (Pleiade) tabi iwọ le tu ìdè irawọ Orionu? (Job 9:9; Amos 5:8.)

32. Iwọ le mu awọn irawọ Massaroti jade wá ni igba àkókò wọn? Tabi iwọ le ṣe amọna Beari pẹlu awọn ọmọ rẹ̀?

33. Iwọ mọ awọn ofin ilana ọ̀run? Ṣe iwọ lè fi ètò-ofin rẹ̀ lelẹ ni ayé? (Job 31:35.)

34. "Iwọ lè gbe ohùn rẹ soke dé ikuukuu awọsanma, ki ọpọlọpọ omi lè bò ọ́? (ẹsẹ 37; Job 22:11; 36:27,28.)

35. Iwọ lè rán manamana ki wọn lè lọ, ki wọn si wi fun ọ pe, 'Awa ni yìí?' (Job 36:32; 37:3.)

36. Tani o fi ọgbọn mu ikuukuu awọsanma, tabi tani o fi oye sinu Meteori? (Gen 1:6,7; Psm 51:6; Onws 2:26; Job 32:8.)

37. Tani o le fi ọgbọ́n ka iye ikuukuu awọsanma, tani o si le mu igo omi ọrun dà jade,

38. Nigba ti erupẹ kojọ pọ̀, ati ogulutu dimọra wọn?

**Eniyan kò le ṣe awari ohun-ijinlẹ nipa ẹranko ati ẹyẹ.**

39. "Iwọ ha lè dẹ ọdẹ fun abo kìnnìun bi, tabi ki o si tẹ́ ebi ẹgbọrọ kìnnìun lọrun? (Psm 104:21.)

40. Nigba ti wọ́n ba mọ́lẹ̀ ninu ihò wọn, ti wọn si ba ni ibùba de ohun ọdẹ? (Job 38:8; Psm 17:12.)

41. Tani npèsè ohun jijẹ fun ẹyẹ ìwò, nigba ti awọn ọmọ rẹ̀ nkepe Ọlọrun, ti wọn si nfò kiri nitori aini ounjẹ. (Psm 147:9; Matt 6:26.)

## ORI 39.

IWỌ mọ àkókò igba ti awọn ewurẹ ori apata nbimọ? Iwọ kiyesi igba ti abo-agbọnrin nbimọ bi? (Psm 29:9.)

2. Iwọ lè ka iye oṣù ti wọn nmúṣẹ, tabi iwọ mọ àkókò igba ti wọn nbi?

3. Wọn tẹ ara wọn ba, wọn bimọ wọn, wọn si mu ọdọmọde wọn jáde wá? (1 Sam 4:19.)

4. Awọn ọmọ wọn nlagbara si i, wọn dagba lori ọ̀dàn, wọn jade lọ, wọn kò si tún pada wá sọdọ wọn mọ́.

5. "Tani o tú kętękętę-oko silę lọ, tabi tani o tú idè kętękętę igbẹ́? (Job 6:5; 11:12; 24:5.)
6. Ẹni ti mo fi aginju ṣe ile fun, ati ilẹ iyọ̀ ni ibugbe rẹ̀. (Job 24:5; Jer 2:24; Hos 8:9; Psm 107:34.)
7. O nrẹ́rìń si ariwo ìlú, bẹẹ ni oun kò sì gbọ́ igbe darandaran.
8. Ìtò lẹ́sẹẹsẹ oke-nla ni ibùjẹ oko rẹ̀, oun a si maa wá ewe tútù gbogbo rí.
9. "Àgbánréré ha ṣe tán lati sin ọ bi? Tabi o jẹ duro ni alẹ́ ni ibùjẹ ẹran rẹ? (Num 23:22; Deut 33:17.)
10. Iwọ ha lè fi okun dẹ àgbánréré ninu aporo, tabi o ha jẹ fa itulẹ ninu aporo oko tọ ọ lẹhin bi?
11. Iwọ ha lè gbẹkẹle e, nitori agbara rẹ̀ pọ̀, iwọ ha sì lè fi iṣẹ rẹ lé e lọwọ?
12. Iwọ ha ni igbẹkẹle ninu rẹ pé, yoo mu èso oko rẹ wá sibi ìpàkà rẹ; pe, yoo si ko ọkà jọ sinu àká rẹ?
13. Ìyẹ́ abo-ògòngò nfi igberaga fì, ìyẹ́ ati idi-ìyẹ́ rẹ ha jẹ ti ifẹ bí?
14. O fi ẹyin rẹ̀ silẹ lori ilẹ, a sì mu wọn gbona ninu ekuru.
15. O si gbagbe pé, ẹsẹ̀ le tẹ wọn fọ́, tabi pe, ẹranko igbẹ le tẹ wọn fọ́ mọlẹ.
16. O nhuwa aláìláàjò si awọn ọmọ rẹ̀ bi ẹni pé wọn ki i ṣe tirẹ̀, asán ni iṣẹ rẹ̀ nitori àìbẹ̀rù rẹ̀. (E.Jer. 4:3; ẹsẹ 22.)
17. Nitori pe Ọlọrun kò fi ọgbọ́n fun un, bẹẹ ni kò si pin oye fun un. (Job 35:11.)
18. Nigba ti o gbe ara soke lati fò, o gan ẹṣin ati ẹlẹṣin.
19. "Njẹ iwọ ni o fi agbara fun ẹṣin? Ṣe iwọ ni o fi yọ̀yọ̀ wọ ọrùn rẹ̀ ni aṣọ? (Psm 147:10.)
20. Ṣe iwọ ni o nmu un fò soke bi ẹlẹngà? Ogo èemí imu rẹ̀ ẹ̀rù-nla ni. (Joel 2:5; Jer 8:16.)
21. O fi ẹsẹ̀ halẹ ninu aporo, o si yọ̀ si agbara rẹ̀; o njade lọ lati pade awọn ihamọra ogun. (Jer 8:6.)
22. O yọ ṣùtì si ẹ̀rù, àyà ko si fò ó; bẹẹ ni ki i si pada sẹhin kuro lọwọ idà.
23. Apó ọfà nmi pẹkẹpẹkẹ lara rẹ̀, ati ọ̀kọ̀ didan ati apata.
24. Oun fi kikorò oju ati ibinu nla gbe ilẹ mi, bẹẹ ni oun kò si le duro jẹ nigba ti iró ipe bá dún. (Jer 4:19; Esk 7:14; Amos 3:6.)
25. O wi ni igba ìpè pe, 'àháà!' o si gbọrun ogun lokere réré, aará awọn balogun, ati iho-igbe wọn. (Jos 6:5; Amos 1:14; 2:2.)
26. Ṣe nipa ọgbọ́n rẹ (Jobu) ni àwòdì nfo soke, ti o si nna iyẹ apá rẹ̀ siha gusu?
27. Ṣe nipa aṣẹ rẹ ni idì ma nfò sókè, ti o si lọ ntẹ́ ìtẹ́ rẹ̀ si òkè giga? (Jer 46:16; Obad 4.)
28. O ngbe lori apata, o si fi pàlàpálá okuta ati ibi orí òkè ṣe ibugbe rẹ̀.
29. Lati ibẹ lọ ni o maa nwa ohunọdẹ kiri, oju rẹ̀ si riran ni okere réré.
30. Awọn ọmọ rẹ̀ pẹlu a maa mu ẹ̀jẹ̀, nibi ti òkú ba gbe wà, nibẹ ni oun o wà pẹlu. (Matt 24:28; Luk 17:37.)

## ORI 40.

**Jobu rẹ ara rẹ̀ silẹ niwaju Ọlọrun.**

OLUWA da Jobu lohun si i pẹlu, o si wi pe. (Job 33:13; 13:3; 23:4; 31:35.)
2. "Ẹni ti nwá ẹ̀sùn yoo ha le bá Olódùmarè wíjọ bi? Ẹni ti nba Ọlọrun jiyan, jẹ ki o dahun!"
3. Nigba naa ni Jobu da Oluwa lohun, o si wi pe:
4. "Kiyesi i, ẹ̀gbin ni emi; ohùn kinni emi o da? Emi o fi ọwọ mi le ẹnu mi. (Job 42:6; 29:9.)
5. Ẹẹkan ni mo sọ̀rọ̀, ṣugbọn emi ki yoo si tun sọ mọ́, lẹẹmeji ni, ṣugbọn emi kò sì ní ṣe bẹẹ mọ́." (Job 9:3,15.)

**Ọlọrun pe Jobu nija.**

6. Nigba naa ni OLUWA dá Jobu lohun lati inu iji àjàyíká wa o si wi pe: (Job 38:1.)
7. "Di ẹgbẹ rẹ ni amure giri bi ọkunrin, emi o bi ọ léèrè, ki iwọ si wi fun mi. (Job 38:3; 42:4.)

8. Iwọ yoo ha mu idajọ mi di asan? Iwọ o si da mi lẹbi, ki a ba lè da ọ láre? (Isa 14:27; Rom 3:4.)

9. Iwọ ni apa bi Ọlọrun bi, tabi iwọ le fi ohùn sán àárá bi oun? (2 Kro 32:8; Jer 17:5; Job 37:5.)

10. "Fi ọlanla ati ọla-itayọ ṣe ara rẹ l'ọ́sọ̀ọ́, ki o si fi ogo ati ẹwà ọ̀ṣọ́ bo ara rẹ láṣọ. (Psm 93:1; 104:1.)

11. Mu irunu ibinu rẹ jade, kiyesi ẹni iwa igberaga, ki o si rẹ ẹ silẹ, (Isa 42:25; 2:12; Dan 4:37.)

12. Wo ẹni ti o ní ìwà ìgbéraga, ki o sì rẹ̀ ẹ́ silẹ̀, ki o si tẹ eniyan buburu mọ́lẹ̀ ni ipò wọn. (1 Sam 2:7; Isa 13:11; 63:3; Job 36:20.)

13. Fi wọ́n pamọ pọ̀ ninu erupẹ, ki o si di ojú wọn ni ikọ̀kọ̀.

14. Nigba naa ni emi o yin ọ pé, ọwọ́ ọ̀tún ara rẹ lè gba ọ là. (Psm 20:6; 60:5; 108:6.)

**Ọlọrun ti o dá erinmi kò lè ṣe doju ìjà kọ fun ẹniyan.**

15. Njẹ ni isinsinyii kiyesi Behemotu (Erinmi) ti mo dá bi mo ti da ọ, a maa jẹ koriko bi ọda-malu. (ẹsẹ 19.)

16. Wo o ni isinsinyìí, agbara rẹ̀ wa ni ẹgbẹ rẹ̀, ati ipa rẹ̀ ninu iṣan ikun rẹ̀.

17. Oun a maa mu ìrù rẹ̀ le bi igi kedari, iṣan itan rẹ̀ dìjọ pọ̀.

18. Egungun rẹ̀ ni iwo-idẹ, ọpa-ẹsẹ̀ rẹ dabi ọpa irin.

19. Oun ni akọkọ nipa iṣẹ Ọlọrun; ẹni ti o da a ni o fi idà rẹ̀ le e lọwọ. (Job 41:33; ẹsẹ 15.)

20. Nitootọ òkè nlanlà ni o nmu ohun-jijẹ wà fun un, nibi ti gbogbo ẹranko igbẹ maa nṣiré. (Psm 104:26.)

21. O dubulẹ labẹ igi Lotosi, ninu iféfèé bíbò ati ẹrẹ̀.

22. Igi Lotosi ṣiji wọn bò ó, igi willo odò yi i ká. (Iṣa 44:4.)

23. Kiyesi i, bí odò nla ti npariwo tó, oun kò bẹ̀rù, o wà láìléwu bi odò Jọrdani paapaa ti nṣan bọ́ si ẹnu rẹ̀.

24. Ẹnikan ha le fi iwọ̀ mú un loju tabi fi ọ̀kọ̀ gun imu rẹ̀? (Owe 1:17.)

## ORI 41.

**Ọlọrun ti o da ọ, ni agbara ju eniyan lọ.**

IWỌ le fi iwọ fa Lefiatani (ọ̀nì-nla) jade, tabi mu ahọn rẹ̀ ninu okùn? (Psm 104:26; Isa 27:1.)

2. Iwọ le fi okùn bọ ọ ni imu, tabi fi iwọ̀ gun un ni ẹ̀rẹ̀kẹ́? (Isa 37:29.)

3. Oun o ha jẹ bẹ̀bẹ̀ jọjọ lọ́dọ̀ rẹ bi? Oun o ha ba ọ sọ ọ̀rọ̀ pẹ̀lẹ́?

4. Oun o ha ba ọ dá majẹmu lati mu un ṣe iranṣẹ rẹ laelae bi?

5. Iwọ ha le ba a ṣire bi ẹni pe ẹyẹ ni, tabi iwọ ha lè de e lókùn fun awọn ọmọbinrin iranṣẹ rẹ?

6. Ẹgbẹ awọn apẹja yoo ha tà á bi, wọn o ha pin in laarin awọn oniṣowò?

7. Iwọ ha le fi ọ̀kọ̀-irin gun awọ rẹ̀, tabi ori rẹ̀ pẹlu ọ̀kọ̀-ipẹja.

8. Fi ọwọ rẹ le e lara, iwọ o ranti ija naa, iwọ ki yoo ṣe bẹẹ mọ́!

9. Kiyesi i, ireti eniyan di asán; ara rẹ̀ rọ̀ wọ̀ ọ̀ ni wiwo irí rẹ̀.

10. Ẹnikan ko jẹ gbójú-gbóyà lati ru u soke; njẹ tani o le duro niwaju rẹ̀? (Job 3:8.)

11. Tani o ṣaaju ṣe fun mi, ti emi iba fi san fun un? Ohunkohun ti nbẹ labẹ ọ̀run gbogbo temi ni. (Rom 11:35; Eks 19:5; Deut 10:14; Psm 24:1; 50:12; 1 Kor 10:26.)

12. "Emi ki yoo ṣàìsọ ni ti awọn ọ̀pá-ẹrẹ̀ rẹ̀, tabi ipá rẹ̀, tabi iduro rẹ̀ ti o ni ẹwà.

13. Tani lè ṣi aṣọ ara rẹ̀? Tani le gun un yọ kọjá aṣọ lile iṣẹpo-meji rẹ̀.

14. Tani o le ṣi ilẹkun iwaju rẹ̀? Ayika ehín rẹ ìbẹ̀rù nla ni.

15. Ìpẹ́ lile ẹ̀hìn rẹ̀ ni igberaga rẹ̀, o pade pọ̀ tímọ́tímọ́ bi àmì edìdí.

16. Ekinni fi ara mọ ekeji tobẹẹ ti afẹ́fẹ́ kò lè wọ aarin wọn.

17. Wọn fi ara mọra ekinni si ekeji rẹ̀, wọ́n lẹ̀ pọ̀ mọra a kò sì lè yà wọ́n.

18. Sínsín rẹ̀ ntan imọlẹ̀ jade, ojú rẹ̀ si dabi ìpenpejú owurọ. (Job 3:9.)

19. Lati ẹnu rẹ̀ ni ọ̀wọ́-iná ti njade wá, ipẹ́pẹ́ iná a si ta jáde.

20. Lati iho-imu rẹ̀ ni eefin ti njade wá, bi ẹni pe lati inu ìkòkò gbigbona ati ifefe ti njó.

21. Eemi rẹ̀ tinabọ eedú, ọ̀wọ́-ina si ti ẹnu rẹ̀ jade.

22. Ni ọrùn rẹ ni agbara wà, ati ìbẹ̀rù-nlá njo niwaju rẹ.

23. Jàbàjábá ẹran rẹ̀ dìjọ pọ̀, wọn duro gírí ni ara rẹ̀, a kò si le ṣi wọn ni ipo.

24. Àyà rẹ̀ le gbágígbágí bi okuta, ani o le bi iyá-ọlọ.

25. Nigba ti o ba gbe ara rẹ̀ soke, awọn alagbara a bẹru, nitori ibẹru nla, wọn a ṣubu lura wọn.

26. Bi ida ba tilẹ̀ bà a kò lè ràn án, ki i ṣe ọ̀kọ̀, àkàsì tabi ọ̀kọ̀-gigun.

27. Ó ka irin sí bi koriko gbígbẹ, ati idẹ sí bi igi ti o ti dibàjẹ́.

28. Ọfà kò lè mu un sá, okuta kànnàkànnà lọdọ rẹ̀ dabi àkékù koriko.

29. Ó ka àkàsì si bi àkékù ìdì koriko, o rẹrin si ariwa ọ̀kọ̀-gigun ti a jù.

30. Isalẹ̀ abẹ́ rẹ̀ dabi ìfọ́sílẹ̀ ìkòkòamọ̀ mímú, o si tẹ́ ara rẹ̀ bi ọlọ ipaka sori ẹrẹ̀.

31. O mu ibu omi hó bi ìkòkò, o ṣe agbami okun bi ìkòkò ohun ikunra.

32. O mu ipa-ọna tàn lẹhin rẹ̀, eniyan a si rò pe ibú dàbí ewú arugbo.

33. Lori ilẹ ayé ko si iru rẹ̀, ti a da laini ìbẹ̀rù. (Job 40:19.)

34. O bojuwo ohun giga gbogbo, o si di ọba lori gbogbo awọn ọmọ agberaga.

ORI 42.

**Jobu ronupiwada.**

NIGBA naa ni Jobu da OLUWA lohun o si wi pe,

2. "Emi mọ̀ pe, iwọ le ṣe ohun gbogbo, ati pe, ko si ète rẹ ti a le dilọwọ. (Gen 18:14; Matt 19:26; Mk 10:27; Luk 18:27; 2 Kro 20:6; Isa 14:27.)

3. 'Tani ẹni ti nfi imọran pamọ́ laini imọ?' Nitori naa ni emi ṣe nsọ eyi ti emi kò mọ̀, ohun ti o ṣe iyanu jọjọ niwaju mi, ti emi kò mòye. (Job 38:2; Psm 40:5; 131:1; 139:6.)

4. 'Emi bẹ ọ, gbọ́, emi o si sọ, emi o bèèrè lọwọ rẹ, ki o si bun mi ni òye.' (Job 38:3; 40:7.)

5. Emi ti fi gbigbọ eti gburo rẹ, ṣugbọn ni isinsinyìí oju mi ti ri ọ. (Job 26:14; Ondj 13:22; Isa 6:5.)

6. Njẹ nitori naa emi korira ara mi, mo si ronupiwada ninu ekuru ati eerú." (Esra 9:6; Job 40:4.)

**Adura Jobu fun awọn ọrẹ rẹ̀.**

7. Bẹẹ ni o si ri, lẹhin igba ti OLUWA ti sọ ọ̀rọ̀ wọnyìí tán fun Jobu, OLUWA si wi fun Elifasi, ara Tema pe, "Mo binu si ọ ati si awọn ọ̀rẹ́ rẹ mejeeji, nitori pe ẹyin ko sọrọ ni ti emi, ohun ti o tọ bi Jobu iranṣẹ mi ti sọ. (Job 32:3; 40:3–5; ẹsẹ 1–6.)

8. Nitori naa ẹ mu akọ ẹgbọrọ malu meje, ati àgbò meje, ki ẹ si tọ Jobu iranṣẹ mi lọ, ki ẹ si fi rú ẹbọ sisun fun ara yin: Jobu iranṣẹ mi yoo si gbadura fun yin: nitori pe adura rẹ̀ ni emi o gbà; ki emi má baa ṣe si yin bi iṣina yin, ni ti pe ẹyin kò sọ̀rọ̀ ohun ti o tọ́ si mi bi Jobu iranṣẹ mi." (Num 23:1; Job 1:5; Jak 5:15,16.)

9. Bẹẹ ni Elifasi, ara Tema, ati Bildadi, ara Sua, ati Sofari, ara Naama lọ, wọn si ṣe gẹgẹ bi OLUWA ti paṣẹ fun wọn: OLUWA si gba adura Jobu.

**Ìgbé ayé Jobu lẹhin adanwo rẹ̀.**

10. OLUWA si yi ìgbésíayé Jobu pada, nigba ti o gbadura fun awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀: OLUWA si busi ohun gbogbo ti Jobu ní rí ni ilọpo meji. (Psm 14:7; 126:1.)

11. Nigba naa ni gbogbo awọn arakunrin rẹ̀, ati gbogbo awọn arabinrin rẹ̀, ati gbogbo awọn ti o ti ṣe ojulumọ rẹ̀ sì tọ ọ wá, wọn ba a jẹun ninu ile rẹ̀, wọn si ṣe idaro rẹ̀, wọn si ṣipẹ̀ fun un nitori ibi gbogbo ti OLUWA ti mu ba a: olukuluku eniyan pẹlu si bun un ni ẹyọ owó kọ̀ọkan ati olukuluku ni oruka wura etí kọọkan. (Job 19:13.)

12. Bẹ̀ẹ̀ ni OLUWA bukun igbẹhin Jobu ju iṣaaju rẹ̀ lọ; o si ni ẹgbaa-meje agutan, ẹgbaa-mẹta rakunmi, ati ẹgbẹrun àjàgà ọda-malu, ati ẹgbẹrun abo kẹtẹkẹtẹ. (Job 1:10; 8:7; 1:3.)

13. O si ni ọmọkunrin meje ati ọmọbinrin mẹta. (Job 1:2.)

14. O si sọ orukọ akọbi ni Jemima; ati orukọ ekeji ni Kẹsia; ati orukọ ẹkẹta ni Keren-happuki.

15. Ati ni gbogbo ilẹ naa, a ko ri obinrin ti o ni ẹwà bi ọmọbinrin Jobu; baba wọn si pin ilẹ fun wọn ninu awọn arakunrin wọn.

16. Lẹhin eyi Jobu wà ni ayé ni ogoje ọdun, o si ri awọn ọmọ rẹ̀ ọkunrin ati awọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ ọkunrin, ani iran mẹrin. (Job 5:26; Owe 3:16.)

17. Bẹ̀ẹ̀ ni Jobu kú, o gbó, o si kún fun ọjọ́. (Gen 25:8.)

19

# IWE PSALMU

## IWE KINNI.

### ORIN 1.

**Ayọ̀ ẹni-iwabi-Ọlọrun.**

IBUKUN ni fun ọkunrin naa ti ko rin ni ìmọ̀ awọn eniyan buburu, ti ko duro ni ọ̀nà awọn ẹlẹ́ṣẹ̀, ati ti ko si jókòó ni ibùjokòó awọn ẹlẹ́gàn. (Owe 4:14; Job 21:16; Psm 17:4; 26:5; Jer 15:17.)

2. Ṣugbọn didùn-inu rẹ̀ wa ninu ofin Oluwa; ati ninu ofin rẹ̀ ni o nṣe àṣàrò lọsan ati loru. (Psm 119:35; Jos 1:8; Psm 119:1.)

3. Yoo si dabi igi ti a gbin si etí ipa odo, ti nso èso rẹ̀ jade ni akoko rẹ̀; ewé rẹ̀ ki yoo si rẹ̀; ati ohunkohun ti o ṣe ni yoo maa ṣe dédé. (Jer 17:8; Esk 47:12; Gen 39:3; Psm 128:2.)

**Òsì ẹni-aiwabi-Ọlọrun.**

4. Awọn eniyan buburu ko ri bẹ̀ẹ̀: ṣugbọn wọn dabi iyangbo ti afẹfẹ nfẹ lọ. (Job 21:18; Isa 17:13.)

5. Nitori naa awọn eniyan buburu ki yoo dide duro ni idajọ, bẹ̀ẹ̀ ni awọn ẹlẹṣẹ ki yoo le duro ni àwùjọ awọn olododo. (Psm 5:5; 9:7, 8:16; 111:1; 149:1.)

6. Nitori Oluwa mọ ọ̀nà awọn olododo: ṣugbọn ọ̀nà awọn eniyan buburu ni yoo ṣègbé. (Psm 37:18; 2 Tim 2:19; Psm 9:3–6.)

### ORIN 2.

**Kikọ Messiah silẹ̀.**

EṢE ti awọn orilẹ-ede fi ndi rikiṣi, ati tí awọn eniyan ngbiro ohun asan? (A.A. 4:25; Psm 21:11.)

2. Awọn ọba ayé kẹ́sẹ̀ jọ, ati awọn ijoye ngbìmọ̀ pọ̀ si Oluwa ati si Ẹni-àmìòróró rẹ̀ pe. (Psm 48:4–6; 74:18,23; Jhn 1:41.)

3. "Ẹ jẹ ki a fa idè wọn ja, ki a si mu okùn wọn kuro ni ọdọ wa." (Jer 5:5.)

**Oluwa yoo fi wọn ṣẹlẹ́yà.**

4. Ẹni ti o jókòó ni ọrun yoo rẹrin; Oluwa yoo yọ̀ ṣùti si wọn. (Psm 59:8; 37:13; Owe 1:26.)

5. Nigba naa ni yoo sọrọ si wọn ni ibinu rẹ̀, yoo si yọ wọn lẹnu ninu ibanujẹ rẹ̀ kikan. (Psm 21:8,9; 78:49,50.)

6. Ṣugbọn mo ti fi Ọba mi jẹ lori Sioni, òkè mímọ́ mi. (Psm 3:4.)

**Messiah yoo yọ ayọ̀ Iṣẹgun.**

7. Emi o si rohin ipinnu Oluwa: O ti wi fun mi pe, "Iwọ ni Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ. (A.A. 13:33; Heb 1:5.)

8. Beere lọwọ mi, emi o sì fi awọn orilẹ̀-èdè fun ọ ni ogún rẹ, ati iha opin ilẹ ni ilẹ-ini rẹ. (Psm 22:27.)

9. Ọpa irin ni iwọ o fi fọ wọn; iwọ o si run wọn wómú-wómú, bi ohùn èlò amọ̀." (Psm 89:23; Ifh 2:27; 12:5.)